**ÌWÉ ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́**

# YOR 321
# SÍNŃTÁSÌ YORÙBÁ II

Òǹkọ̀wé Kọ́ọ̀sì

**Ọ̀jọ̀gbọ́n Oyè Táíwò**
Ẹ̀ka Ìmọ̀ Ẹ̀dá-Èdè áti Èdè Áfíríkà
Yunifásítì Ibadan, Ibadan
oyepaultaiwo@gmail.com;
po.taiwo@mail1.ui.edu.ng
08053506069; 08024661260

**NATIONAL OPEN UNIVERSITY OF NIGERIA**
National Open University of Nigeria
Headquarters
14/16 Ahmadu Bello Way
Victoria Island
Lagos

Abuja Annex
245 Samuel Adesujo Ademulegun Street
Central Business District
Opposite Arewa Suites
Abuja
e-mail: centralinfo@nou.edu.ng
URL: www.nou.edu.ng

National Open University of Nigeria

First Printed

ISBN:
All Rights Reserved

Printed by ……………..
For
National Open University of Nigeria

**ÀKÓÓNÚ** **OJÚ-ÌWÉ**

Ìfáárà
Ohun tí o máa kọ́ ní Abala Ẹ̀kọ́ yìí
Àfojúsùn Kọ́ọ̀sì Yìí
Èròǹgbà Kọ́ọ̀sì Yìí
Ìṣẹ́ Ṣíṣe ni Abala Ẹ̀kọ́ yìí
Ìwé Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
Ìpín Ẹ̀kọ́
Ìwé Ìtọ́kasí àti Ìwé Fún Kíkà
Ìgbéléwọ̀n
Ìdánwò Àṣekágbá àti Ìgbéléwọ̀n
Ìlànà Máàkì Gbígbà
Àtúnyẹ̀wò Abala Ẹ̀kọ́ àti Ìlànà Ìgbékalẹ̀
Ọ̀nà láti ṣe Àṣeyọrí nínú Abala Ẹ̀kọ́ yìí
Bí O Ṣe Lè Ka Abala Ẹ̀kọ́ Yìí Ní Àkàyé
Ìkúnnilọ́wọ́/Olùkọ́ àti Ìkọ́ni
Ìsọníṣókí

**Ìfáárà**

Abala Ẹ̀kọ́ yìí jẹ́ kírẹ́dìtì onídàá mẹ́ta (three credit units). Módù márùn-ún ni mo fi ṣàgbékalẹ̀ rẹ̀.

Commented [O.J1]: kírẹ́dîtì

**Ohun tí O máa Kọ́ ní Abala Ẹ̀kọ́ yìí**

**Àfojúsùn Abala Ẹ̀kọ́**

**Èròǹgbà Abala Ẹ̀kọ́**

**Iṣẹ́ Ṣíṣe ní Abala Ẹ̀kọ́**

**Ìwé Ìdánilẹ́kọ̀ọ́**
A ti pèsè àwọn wọ̀nyí fún ẹ ní abala ẹ̀kọ́ yìí:

- Ìtọ́ni abala ẹ̀kọ́;
- Ìpín Ẹ̀kọ́;
- Recommended texts/Ìwé Àkànlò;
- Ètò Iṣẹ́ Àyànṣe; àti
- Ètò Ìgbékalẹ̀

**Ìpín Ẹ̀kọ́**
YOR 321 jẹ́ abala ẹ̀kọ́ oní-kírẹ́dîtì mẹ́ta fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ìgboyè àkọ́kọ́. Módù márùn-ún ni ó wà ní abala ẹ̀kọ́ yìí. Ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn ní ìpín mẹ́rin. Ìyẹn ni pé ìpín ogún ni ó wà ní ìwé ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí. Bí módù máràárún ṣe lọ nìyí:

## ÀKÓÓNÚ

**Módù 1: Ìmọ̀-Èdè àti Ìlò-Èdè, àti Àwòrán Atọ̀ka-Igi**

Commented [O.J2]: Atọ́ka

Ìpín 1: Ìmọ̀-Èdè
Ìpín 2: Rírú Òfin Èdè
Ìpín 3: Àwòrán Atọ́ka-Igi
Ìpín 4: Ìbátan Láàárín Ẹ̀wọ́n

## Módù 2: Àwòrán Atọ́ka-Igi àti Ìhun Àpólà Orúkọ

Ìpín 1: Fífi ẹ̀yán/ẹ̀pọ́n hàn nínú àwòrán atọ́ka-igi
Ìpín 2: Àmúpé, Àfikún àti Asọdọ̀tọ̀
Ìpín 3: Ìhun Àpólà Orúkọ
Ìpín 4: Àmúpè, Àfikún àti Asọdọ̀tọ̀ nínú Àpólà Orúkọ (APOR)

## Módù 3: Ẹ̀pọ́n Aṣàfikún nínú Ìhun Àpólà Ìṣe (APIṢ)

Ìpín 1: Ìhun Àpólà Ìṣe
Ìpín 2: Àpólà Aṣẹ̀pọ́n (APEP) Aláìlàbọ̀ gẹ́gẹ́ bí Ẹ̀pọ́n Aṣàfikún Aṣáájú Ọ̀rọ̀-Íṣe

Commented [O.J3]: Ìṣe

Ìpín 3: Àpólà Aṣẹ̀pọ́n (APEP) Ẹ̀pọ́n Aṣàfikún Aṣáájú Ọ̀rọ̀-Ìṣe
Ìpín 4: Ẹ̀pọ́n Aṣàfikún Atẹ̀lé Ọ̀rọ̀-Íṣe

Commented [O.J4]: Ìṣe

## Módù 4: Ẹ̀pọ́n Aṣàmúpé nínú Ìhun Àpólà Ìṣe (APIṢ)

Ìpín 1: Àpólà Orúkọ (APOR) àti Àpólà Aṣàmúpé (APAM) gẹ́gẹ́ Ẹ̀pọ́n Aṣàmúpé
Ìpín 2: Àpólà Aṣẹ̀pọ́n (APEP) gẹ́gẹ́ bi Àmúpé IṢ nínú APIṢ

Ìpín 3: Àpapọ̀ APOR àti APEP Alàbọ̀ gẹ́gẹ́ bí Àmúpé
Ìpín 4: Tẹlẹ́ǹtẹ̀lé Ẹ̀pọn nínú Ìhun Àpólà Ìṣe

## Módù 5: Ìhun Àpólà Aṣẹ̀pọ́n (APEP) àti Ìhun Àpólà Apàrísídà (APAPR)

Ìpín 1: Ọ̀rọ̀-Aṣẹ̀pọ́n (EP)
Ìpín 2: Àpólà Aṣẹ̀pọ́n (APEP)
Ìpín 3: Ọ̀rọ̀-Apàrísídà (APR)
Ìpín 4: Fọ́nrán-Ìhun Àpólà Apàrísídà (APAPR)

**Ìwé Ìtọ́kasí àti Ìwé Fún Kíkà**
Àkójọ àwọn ìwé ìtọ́kasí wà ní òpin ìpín kọ̀ọ̀kan. Mo rọ̀ ẹ́ láti ṣàwárí àwọn ìwé wọ̀nyí, yẹ̀ wọ́n wò kí o sì ká wọ́n láti ní ìmọ̀ síwájú sì i. Yóò tún ṣe ọ ní àǹfàní bí ó bá ka àwọn ìwé mìíràn tí ó kún ojú òṣùwọ̀n lórí ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn àkòrí tí a ṣàgbéyẹ̀wò.

Commented [O.J5]: kà

**Ìgbéléwọ̀n**
Oríṣi ìgbéléwọ̀n méjì ni o máa ṣalábàápàdé. Àwọn méjèèjì ni Iṣẹ́ Ṣìṣe àti Ìdánwò òpin simẹ́sítà.  A ń retí pé kí o ṣe ìdánwò ní òpin abala ẹ̀kọ yìí.

**Iṣẹ́ Ṣìṣe**
Ní òpin ìpín kọ̀kan, mi ti ṣètò Iṣẹ́ Ṣìṣe fún ọ, o gbọ́dọ̀ gbìyànjú láti ṣe wọ́n nípa lílo gbogbo ìmọ̀, ọgbọ́n àti ìfitóniléti tí o ti gbà nínú ìpín náà. Lórí ẹ̀rọ ìtànẹ́ẹ̀tì ni o ti máa ṣe àwọn Iṣẹ́ Ṣìṣe tí o sì máa gba èsì lẹ́ṣẹkẹṣẹ̀. Èyí yóò sì fòpin sí pípẹ́ tí èsì ìdánwò máa ń pẹ́ kí o tó tẹ akẹ́kọ̀ọ́ lọ́wọ́. Gbìyànjú láti fi Iṣẹ́ Ṣìṣe tìrẹ sọwọ́ sí ilé-ìwé rẹ ní ọjọ́ tí a popongo rẹ̀ lórí òpó ítánẹ́ẹ̀tì Yunifásítì àti ni Ibi Ìkẹ́kọ̀ọ́ rẹ. Ìdá ọgbọ̀n nínú ọgọ́rùn-ún (30%) ni Iṣẹ́ Ṣìṣe jẹ́ nínú ìgbéléwọ̀n àṣekáagbá rẹ.

Commented [O.J6]: mo

Commented [O.J7]: polongo

**Ìdánwò Àṣekágbá àti Ìgbéléwọ̀n**
Ìdánwò Àṣekágbá jẹ́ ìdá àádọ́rùn-ún nínú ọgọ́rùn-ún (70%) jẹ́ nínú jẹ́ nínú ìgbéléwọ̀n àṣekáagbá rẹ. Bákan náà, lórí ẹ̀rọ òpó ìtánẹ́ẹ̀tì ti Yunifásítì ní o ti máa ṣe ìdánwò gẹ́gẹ́ bí mo ṣe sọ ṣáájú. A óò sì ṣa àwọn ìbéèrè jọ láti inú gbogbo ìpín abala ẹ̀kọ̀. Nítorí náà, a ń retí pé kí o ka ìwé ìdánilẹ́kọ̀ọ́ dáadáa kí àkókò ìdánwò tó dé. Bákan náà pẹ̀lú, ó yẹ kí o mọ́jú tó ìṣàmúlò ẹ̀rọ kọ̀ǹpútà rẹ dáadáa fún àǹfàní ara rẹ.

**Ètò Ìlànà Máàkì GBígbà**
Àpapọ̀ máàkì fún abala ẹ̀kọ́ ni 100%. Ìdá ọgbọ̀n nínú ọgọ́rùn-ún (30%) jẹ́ máàkì fún Iṣẹ́ Ṣìṣe àti ìdá àádọ́rùn-ún nínú ọgọ́rùn-ún (70%) jẹ́ máàkì ìdánwò. Mo gbà ọ̀ ní ìmọ̀ràn pé kí o sa gbogbo ipá rẹ láti ṣàṣeyege nínú Iṣẹ́ Ṣíṣe àti nínú ìdánwò kí o ba lé ṣàṣeyọrí ní ìkẹyìn.

Commented [O.J8]: bà á lè

**Àtúnyẹ̀wò Abala Ẹ̀kọ́ àti Ètò Ìgbékalẹ̀**

**Àwọn Ohun tí o máa nílò fún Abala Ẹ̀kọ́ yìí**

**Bí o ṣe lè Gbádùn Abala Ẹ̀kọ̀ yìí**
Ó yẹ kí àwọn ìpín wọ̀nyí tọ́ ẹ gẹ́gẹ́ bí olùkọ́ ṣe máa tọ́ ẹ. Nítorí náà, ó yẹ kí o fara balẹ̀ ka ìpín kọ̀ọ̀kan. O sì gbọ̀dọ̀ gbìyànjú láti ṣe gbogbo àwọn ìdárayá tí ó wà nínú ìpín kọ̀ọ̀kan. A ṣe ìgbékalẹ̀ ìpín kọ̀ọ̀kan bákan náà – ìfáárà, èròǹgbà àti Àkóónú Ìdánilẹ́kọ̀ọ́. Ìfáárà jẹ́ ìtọ́wò péréte abala ẹ̀kọ̀, èròǹgbà ń ṣàfihàn àwọn nǹkan tí ó yẹ kí o mọ̀, a ṣètò ẹ̀kún-rẹ́rẹ́ àlàyé ní Àkóónú Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

Commented [O.J9]: tọ́ ẹ sọ́nà

**Olùkọ̀ àti Ẹ̀kọ́**
Yunifásítì yòó pèsè àwọn olùkọ́ ní ọlọ́kan-ò-jọ̀kan àwọn ibùdó ìdánilẹ́kọ̀ọ́ láti kọ́ ẹ lórí àwọn abala tí ó ta kókó. Ò yẹ kí àwọn olùkọ́ wá fojú kàn láti kọ́ ẹ ní àwọn àkókò tí a ti lá kalẹ̀. Àwọn olùkọ́ wọ̀nyí yóò máa gbé ẹ sórí ìwọ̀n láti mọ bí o ṣe ń tẹ̀síwájú sí, yóò sì máa ṣàwílé lórí ìtẹ̀síwájú rẹ.

**Ìsọníṣókí**

**ÀWỌN ÀGÉKÚRÚ ÀTI ÀROKÒ TÍ A LÒ**

| | | |
|---|---|---|
| +AB[1] | = | Àbọ̀ |
| +ABIṢOL | = | Àbọ̀ Ọ̀rọ̀-Ìṣe Olùwà |
| +ABOLIṢ | = | Àbọ̀ Olùwà Ọ̀rọ̀ -Ìṣe |
| AF | = | Ẹ̀yán Aṣàfihàn |
| AJ | = | Ẹ̀yán/Ọ̀rọ̀-Àpèjúwe |
| AK | = | Ẹ̀yán Àṣòǹkà |
| AM | = | Aṣàmúpé |
| APAM | = | Àpólà Aṣàmúpé |
| APAPR | = | Àpólà Apàrísídà |
| APAS | = | Àpólà Àsopọ̀ |
| APEP | = | Àpólà Aṣẹ̀pọ́n |
| APIB | = | Àpólà Ìbá-Ìṣẹ̀lẹ̀ |
| APIBKO | = | Àpólà Àsìkò àti Ibá-Ìṣẹ̀lẹ̀ |
| +APIR | = | Àpólà Ìbéèrè |
| APIṢ | = | Àpólà Iṣe |
| +APIT | = | Àpólà Ìtẹnumọ́ |
| +AṢ | = | (Atọ́ka) Àṣẹ |
| APIṢ | = | Àpólà Iṣe |
| APKO | = | Àpólà Àsìkò |
| APOD | = | Àpólà Ìyísódì |
| APOR | = | Àpólà Orúkọ |
| APR | = | (Ọ̀rọ̀-) Apàrísídà |
| AROG | = | Arọ́pò-Orúkọ Gígùn |
| AROK | = | Arọ́pò-Orúkọ Kúkúrú |
| AS | = | Ọ̀rọ̀-Àsopọ̀ |
| EP | = | Ọ̀rọ̀-Aṣẹ̀pọ́n |
| +EPIṢABEP | = | Ẹpọ́n Ọ̀rọ̀-Ìṣe Àbọ̀ Ẹ̀pọ́n |
| IB | = | Atóka Ibá-ìṣẹ̀lẹ̀ |
| +IR | = | (Atọ́ka) Ìbéèrè |
| IṢ | = | Ọ̀rọ́-Ìṣè |
| +IṢOLAB | = | Ọ̀rọ̀-Ìṣe Olùwà Àbọ̀ |
| +IṢABOL | = | Ọ̀rọ̀-Ìṣe Àbọ̀ Olùwà |
| +IT | = | (Atọ́ka) Ìtẹnumọ́ |
| KO | = | Atọ́ka Àsìkò |
| OD | = | Atọ́ka Ìyísòdì |
| +OL | = | Olùwà |

Commented [O.J10]: APAR ńkọ́ dípò APAPR?

Commented [O.J11]: Ṣe kì í ṣe àpólà méjì ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni èyí: Àpólà Àsìkò àti Àpólà Ibá-Ìṣẹ̀lẹ̀?

[1] Àmì yìí + lẹ́gbẹ̀ẹ́ àrokò fi hàn pé àrokò bẹ́ẹ̀ jẹ́ èyí tí mo dálábàá. Awọn àrokò tí kò ní i jẹ́ àrokò ti Èdè-Ìperí.

| | | |
|---|---|---|
| $^{+}$OLABIṢ | = | Olùwà Àbọ̀ Ọ̀rọ̀-Ìṣe |
| $^{+}$OLEPIṢAB | = | Olùwà Ẹ̀pọ́n Ọ̀rọ̀-Ìṣe Àbọ̀ |
| $^{+}$OLEPIṢABEP | = | Olùwà Ẹ̀pọ́n Ọ̀rọ̀-Ìṣe Àbọ̀ Ẹ̀pọ́n |
| $^{+}$OLEPIṢEP | = | Olùwà Ẹ̀pọ́n Ọ̀rọ̀-Ìṣe Ẹ̀pọ́n |
| $^{+}$OLIṢ | = | Olùwà Ọ̀rọ̀-Ìṣe |
| $^{+}$OLIṢAB | = | Olùwà Ọ̀rọ̀-Ìṣe Àbọ̀ |
| $^{+}$OLIṢABEP | = | Olùwà Ọ̀rọ̀-Ìṣe Àbọ̀ Ẹ̀pọ́n |
| $^{+}$OLIṢEP | = | Olùwà Ọ̀rọ̀-Ìṣe Ẹ̀pọ́n |
| OR | = | Ọ̀rọ̀-Orúkọ |
| SOO | = | Sílébù Olóhùn Òkè |
| + | *dúró fún* | so mọ́ *b.a. IṢ + OR (sọ + ọ̀rọ̀ → sọ̀rọ̀)* |
| ( ) | *dúró fún* | wọ̀fún tàbí àkámọ́ afìwọ̀fúnhàn |
| → | *dúró fún* | tún un kọ/ ṣe ìtumọ̀ gẹ́gẹ́ bí |
| * | *dúró fún* | Àìṣeégbà |
| [ ] | *dúró fún* | ìkámọ́ apààlà |
| { } | *dúró fún* | mú ọ̀kan nínú ohun tí a tò jọ |
| abbl | *dúró fún* | àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ |
| b.a | *dúró fún* | bí àpẹẹrẹ |
| i.n.p | *dúró fún* | ìyẹn ni pé |
| ø | *dúró fún* | òfo |

## MÓDÙ 1 ÌMỌ̀-ÈDÈ ÀTI ÌLÒ-ÈDÈ, ÀTI ÀWÒRÁN ATỌ́KA-IGI

Àfojúsùn módù yìí ni láti ṣàlàyé Ìmọ̀-Èdè àti Ìlò-Èdè, kí á sì fi ìyàtọ̀ tó wà láàárin àwọn méjèèjì hàn. Módù yìí á tún fi yé ọ bí a ṣe ń fi àwòrán atọ́ka-igi ṣàlàyé oríṣiríṣi ìhún ìsọ̀rí sínńtáàsì. Ìmọ̀ tí elédè ní nínú èdè rẹ̀ ni ó ràn án lọ́wọ́ láti ṣe àgbékalẹ̀ onírúurú gbólóhùn tàbí ìpèdè nínú èdè náà. Ìmọ̀ yìí jẹ́ àbímọ́ tí ó fún elédè ní àǹfàní láti fún ìró, ọ̀rọ̀ tàbí akójọpọ̀ ọ̀rọ̀, tàbí odidi gbólóhùn ní ìtumọ̀. Ìlò èdè ni a le pè ní ìṣàgbélalẹ̀ ìmọ̀-èdè ti èèyàn ni nínú èdè kan, bóyá nípa afọ̀ ṣíṣé tàbí ní onírúurú ọ̀nà tí à ń gbà lo èdè. Ìmọ̀-èdè elédè máa ń farahàn nígbà tí ó bá le sọ bí ìpèdè kan bá jẹ́ aṣeégbà tàbí àìṣeégbà; tàbí bí ìpèdè méjì bá ní ìtumọ̀ kan náà. Àwọn onímọ̀ gírámà gbà pé ìmọ̀-èdè tì elédè ní yàtọ̀ sí bí elédè se má ń lo ìmọ̀ náà nínú ọ̀rọ̀ sísọ. Ìdí ni pé nígbà tí a bá ń sọ̀rọ̀, oríṣiríṣi ìdíwọ́ tàbí àṣìṣe òun àṣìwí máa ǹ wáyé, ti kò sì níi ṣe pèlú ìmọ̀ tí olúwa rẹ̀ ní nínú èdè náà.

Èdè kọ̀ọ̀kan ló ní òfin àti ìlànà tí ó ń ṣàkóso atọ̀jọ àwọn ìró, ọ̀rọ̀, àti gbólóhùn inú èdè. Bí a bá si rú ọ̀kankan nínú òfin yìí, ìpèdè náà á jẹ́ àìṣeégbà. Elédè mọ̀ bí ìsọ kan nínú èdè rẹ̀ bá ṣeégbà tàbí kò ṣeégbà. Àmọ́, kò ṣeé ṣe fún èlédè láti sọ àwọn òfin tó dè é tí irú ìsọ bẹ̀ẹ̀ ṣe jẹ́ aṣeégbà tàbí àìṣeégbà. Àwọn onímọ̀ ẹ̀dá-èdè ni wọ́n máa ń láti ṣàwárí àwọn òfin wọ̀nyí ni ìbámù pẹ̀lú àwọn ohun tí elédè fara mọ́.

Ní mòdú yìí, wà á kọ́ nípa ìmọ̀-èdè àti ìlò-èdè, òfin èdè àti rírú òfin èdè, ìdàrọ gbólóhùn. Wà á tún kọ́ nípa àwọn nǹkan tó ṣeéṣe kí ó mu àṣìṣe tàbí àṣìwí wáyé nínú àfọ̀ síṣe. Lẹ́yìn náà, wà á kọ́ bí a ti ń fi àwòrán atọ́ka-igi ṣàlàyé oríṣiríṣi ìhún ìsọ̀rí sínńtáàsì. Àwọn àkòrí wọ̀nyí ni o máa kà ní módù yìí:

Ìpín 1: Ìmọ̀-Èdè
Ìpín 2: Rírú Òfin Èdè
Ìpín 3: Àwòrán Atọ́ka-Igi
Ìpín 4: Ìbátan Láàárín Ẹ̀wọ́n

Commented [O.J12]: láàárín
Commented [O.J13]: ìṣàgbékalẹ̀
Commented [O.J14]: ṣe
Commented [O.J15]: ń
Commented [O.J16]: módù
Commented [O.J17]: ìhun

**ÌPÍN 1 ÌMỌ̀-ÈDÈ**


**1.0** Ìfáárà
**2.0** Èròǹgbà àti Àfojúsùn
**3.0** Ìbéèrè Ìṣáájú
**4.0** Àkóónú Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
**4.1** Ìfihàn Ìmọ̀-Èdè
**4.2** Ìdàrọ Gbólóhùn
**5.0** Ìsọnísọ́kí
**6.0** Iṣẹ́ Ṣíṣe
**7.0** Ìwé Ìtọ́kasí/Àwọn Ìwé Fùn Kíkà


Commented [O.J18]: A lè yọ èyí kúrò fún ìdọ́gba gẹ́gẹ́ bí Ọ̀jọ̀gbọ́n Ọlátẹ́jú ti wí.

## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Ìmọ̀-Èdè ni ìmọ̀ àbímọ́ tí ó fún èèyàn ní àǹfàní láti fi ìtumọ̀ tí àwọn ìró ní hàn. Elédè máa ń ṣàmúlò gbogbo ìmọ̀ tí wọ́n ní nípa èdè wọn nínú ìsàfọ̀ tàbí àfọ̀. Ní ìpín yìí, á máa kọ́ ẹ̀kọ́ lórí Ìmọ̀-Èdè

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN

Lẹ́yín tí o bá ti ka ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí tán, wàá lè ṣàlàyé ìmọ̀-èdè ati bí elédè ṣe ń ṣàmúlò ìmọ̀-èdè yìí láti ṣàgbéjáde ìpèdè èdè náà.

## 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢÁÁJÚ

Báwo ni Ìmọ-èdè elédè ṣe ń farahàn

Commented [O.J19]: Báwo ni Ìmọ-èdè elédè ṣe ń farahàn?

## 4.0 ÀKÓÓNÚ ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

### 4.1 Ìfihàn Ìmọ̀-Èdè

Nigbà tí a bá ń ṣàfọ̀, elédè máa ń ṣàmúlò gbogbo ìmọ̀ tí wọ́n ní nípa èdè wọn nínú ìsàfọ̀ tàbí àfọ̀, ìṣàmúlò ìmọ̀ yìí ni a ń pè ní ìmọ̀-èdè. Ìmọ̀-èdè kìí ṣe ìpèdè tí a lè gbé lé ìwọ̀n rara. Dípò bẹ́ẹ̀, a máa ń tọ́ka sí i gẹ́gẹ́ bí ìmọ̀ àbímọ́ tí ó fún èèyàn ní àǹfàní láti fi ìtumọ̀ tí àwọn ìró ní hàn. Èyí yàtọ̀ sí lílo èdè ní pàtó bí a bá ń ṣàfọ̀ tí a ń pè ní ìlò-èdè. Àwọn onímọ̀ pín girama èdè sí méjì: **ìmọ̀-èdè àti ìlò-èdè**.

Gírámà (onídàrọ) èdè kan jẹ́ ìṣàpèjúwe kíkún tí ó máa ń ṣàgbéjáde **ìmọ̀ ìmọ̀ọ̀nú/ìmọ̀sínú** ìmọ̀-èdè tí elédè kan ní kedere. Èyí já sí pé ìmọ̀-èdè tí èyàn ní jẹ́ ìmọ̀ ìmọ̀ọ̀nú èdè rẹ̀. Èyí tùmọ̀ sí pé a kò lè mọ̀ọ́mọ̀ rí àwọn ìlànà àti òfin tí ó ń ṣàkóso àtòjọ àwọn ìró, ọ̀rọ̀, àti gbólóhùn; ṣùgbọ́n a lè mọ ìgbà tí a bá ṣàṣìṣe tàbí rú àwọn òfin àti ìlànà náà. Bí àpẹẹrẹ, bí ẹnìkan bá ní gbólóhùn yìí *Ọpẹ́ sọ pé Òjó ran ara wọn lọ́wọ́* jẹ́ àìṣeégbà, ìdí ni pé ẹni ọ̀hún ní ìmọ̀ àmọ̀sínú nípa ìlànà girama pé arọ́pò-orúkọ atọ́kapadà-sólùwà gbọ́dọ̀ wà ní ìbámu ní iye pẹ̀lú olùwà tí ó tọ́ka padà sí. Bẹ́ẹ̀ sì ni *ara wọn* kò wà ní ìbámu pẹ̀lú *Òjó, ara rẹ̀* ní ó bá à mu.

Commented [O.J20]: túmọ̀

Bí a bá sọ pé èyàn ní ìmọ̀ èdè kan, ohun tí a ń sọ ni pé ẹni ọ̀hún lè lo èdè tí a ń wí yìí láti ṣàgbéjáde ìpèdè èdè náà kí ó sì loye rẹ̀. **Ipa** láti lo èdè náà kìí ṣe èyí tí èyàn ṣẹ̀ṣẹ̀ ń kọ́ láti ọ̀dọ̀ ẹnìkan. Èyàn lè kọ́ tàbí mọ èdè rẹ̀ láìjẹ́ pé ẹnìkan kọ́ ọ ní èdè náà. Bí a bá sì kọ́ elédè ní èdè rẹ̀, ẹ̀kọ́ èdè bẹ́ẹ̀ yóò jẹ́ ìwọ̀ǹba kíún lẹ́yìn ìgbà tí elédè ti lè lo èdè rẹ̀ dáadáa. Ìmọ̀ tí ó fà á tí èyàn ṣe ni ipa láti lo èdè rẹ̀ jẹ̀ **ìmọ̀ àìsọjáde**, àfojúsùn onímọ̀ girama sì ni láti mọ̀ọ́mọ̀ ṣàwárí ìmọ̀ àìsọjáde tí elédè ní yìí

Commented [O.J21]: èèyàn tàbí ènìyàn

Commented [O.J22]: èèyàn tàbí ènìyàn

Àwọn òfin inú èdè ni elédè ń lò ní ìgbà tí ó bá ń sọ̀rọ̀. Bí àpẹẹrẹ, elèdè Yorùbá yóò fi ìyàtọ̀ hàn láàárín àwọn ìwònyí.

1a. Òjó lọ sí oko .
b. Lọ́ sí oko, Òjó

d *Lọ oko sí Òjó
e. *Sí Òjó lọ oko
ẹ. *Oko sí lọ Òjó

Elédè Yorúbá mọ̀ pé gbólóhùn (1a) ati (1b) ṣe é gbà, ṣùgbọ̀n àwọn tó kú, (1d) dé (1ẹ), kò ṣe é gbà. (Gbólóhùn (1a) ati (1b) jẹ́ gbólóhùn aṣeégbà nígbà tí àwọn gbólóhùn (1d) de (1ẹ) jẹ́ gbólóhùn àìṣeégbà). Nínú ìmọ̀ ẹ̀dá-èdè, àwọn gbólóhùn àìṣeégbà (fún ìdí kan tàbí òmíràn) ni ó máa ń gba àmì (tàbí àrọkọ̀) ìràwọ̀ (*).

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé a tẹnu mọ́ ọn pé ìmọ̀-èdè tí elédè ní jẹ́ ìmọ̀ gírámà àìkọ́ni tí ó jẹ́ ìmọ̀ ìmọ̀sínú tí ó wá ní ọpọlọ elédè, ó ṣeé ṣe láti fi ìmọ̀ yìí nípa àwọn ọ̀nà kan. Mo máa ṣàlàyé díẹ̀ lára wọn.

**ÌGBÉLÉWỌ̀N AKẸ́KỌ̀Ọ́**
Ṣàlàyé ìmọ̀-èdè tí elédè ní nínú èdè rẹ̀.

## 4.2 Ìdàrọ Gbólóhùn

Elédè máa ń fi ìmọ̀-èdè rẹ̀ hàn nipa bí ò ṣe máa ń gbé oríṣiríṣi gbólóhùn jáde. Gbogbo èèyàn tí ó bá ní ìmọ̀-èdè máa ń sọ ọ̀kẹ́ àìmoye gbólóhùn, tí ó sí máa ń sọ gbólóhùn tuntun jáde. Èyí ni a mọ̀ sí **ìdàrọ** gbólóhùn. Gbogbo elédè ni ó máa ń ṣàgbéjáde gbólóhùn nigba tí a bá ń ṣàfọ̀. A sí mọ̀ pé kìí ṣe pé a máa ń ṣe àkọ́sórí àwọn gbólóhùn tí a fẹ́ sọ kí a tó máa sọ wọ́n. Irú ohunkóhun tí elédè ba fẹ́ sọ̀rọ̀ lé lórí, tàbí ìgbàkúgbà tí a bá fẹ́ sọ̀rọ̀, elédè a máa ṣàgbéjáde àwọn gbólóhùn tí ó yẹ. Alábájọ tí ó fi jẹ́ pé elédè lè pàṣẹ, gbadura, bẹ̀bẹ̀, parọ́, ṣèbéèrè, gegun-ún, tàbí fi ohùn gbé ọ̀rọ̀ jáde gẹ́gẹ́ bí àkókò náà bá ṣẹ gbà á láàyè.

Commented [O.J23]: sì
Commented [O.J24]: gegùn-ún

Ìmọ̀ ti elédè ní nípa èdè rẹ̀ kò lópin. Ó lè sọ ohun tí kò gbọ́ rí, o lè mọ ìtumọ̀ gbólóhùn tí kò gbọ̀ rí, bẹ́ẹ̀ ni ó sì lè hun gbólóhùn tuntun lọ́nà àrà. Abínibí ni ọ̀nà èdè. Ìmọ̀ tàbí àbùdá èdè tí ẹlẹ́dàá fún ọmọnìyàn ní ó ya ọmọnìyàn sọ́tọ̀ sí ẹ̀dá yòókù. Bí èdè ti jẹ́ abínibí tó, kò sí ẹni ti ẹlẹ́dàá dá èdè kan pátò mọ́, gbogbo èdè la lè sọ, ṣùgbọ̀n èyí tí aládùúgbò wa bá gbọ́ ni a ń sọ nígbèyìn. Bí àpẹẹrẹ, ọmọ Yorùbá tí a bí ní ìlú Òyìnbó yóò gbọ̀ Gẹ̀ẹ́sì bí ọba ìlú Èèbó, ọmọ Haúsá tí a bí ní Ọ̀yọ́-ilé yóò lè táákà Yorùbá bí ọmọ Aláàfin.

**ÌGBÉLÉWỌ̀N AKẸ́KỌ̀Ọ́**
Ṣàlàyé bi Ìmọ̀ ti elédè ní nípa èdè rẹ̀ kò ṣe lópin.

## 5.0 ÌSỌNÍṢÓKÍ

Ẹ̀dá ọmọnìyàn kìí kàn sọ ọ̀rọ̀ tàbí gbólóhùn ti ó bá gbọ́ rí nìkan. Ó lè sọ ohun tí kò gbọ́ rí, o lè mọ ìtumọ̀ gbólóhùn tí kò gbọ̀ rí, bẹ́ẹ̀ ni ó sì lè hun gbólóhùn tuntun lọ́nà àrà. Ìmọ̀ tí elédè ní, tí ó fi ń ṣe gbogbo nǹkan yìí ni à ń pè ní Ìmọ-èdè.

Commented [O.J25]: kì í

## 6.0 IṢẸ́ ṢÌṢE

Kí ni ìmọ̀-èdè gan-an, àti pé báwo ni elédè ṣe máa ń fi ìmọ̀-èdè rẹ̀ hàn?

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ/ÀWỌN ÌWÉ FÙN KÍKÀ


Awóbùlúyì, O. 1978. *Essentials of Yorùbá Grammar*, Ìbàdàn: UPL.
Awobuluyi, O. 1988. *Èdè Ìperí Yorùbá*: *Apá kejí*, Lagos: NERDC
Awóbùlúyì, O. 2001a. “Arọ́pò–Orúkọ Kúkúrú Ẹni–Kẹ́ta Ẹyọ Aṣolùwà” *Yorùbá*, Vol. 2, No. 1 pp 1-8
Awóbùlúyì, O. 2001b. “Òte–Ìlò Àwọn Arọ́pò–Orúkọ Kúkúrú” Bébà tí a kà ní Àpérò Ẹgbẹ́ Onímọ̀ ÈdèYorùbá: Yunifásítì ìlú Eko.

Awobuluyi, O. 2008. *Ẹ̀kọ́ Íṣẹ̀dá-Ọ̀rọ̀ Yorùbá*, Akurẹ: Montem Paperbacks
Awobuluyi, O. 2013. *Ẹ̀kọ́ Gírámà Èdè Yorùbá*, Oshogbo: Montem Paperbacks
Bámgbóṣé, Ạ. 1967. *A Short Yorùbá Grammar*, Ìbàdàn: HEB.
Bámgbóṣé, Ạ. 1990. *Fonọ́lọ́jì àti Gírámà Yorùbá*. Ìbàdàn: UPL.
Comrie, Bernard. (1981). Language universals and linguistic typology: syntax and morphology (2nd ed). University of Chicago Press, Chicago
Dryer, M. S. (2013). Order of Subject, Object and Verb. In M. S. Dryer & M. Haspelmath (eds), The World Atlas of Language Structures Online.
Táíwò, O. 2003. Tense and Aspect in Ào. Nínú Ndimele O.M (olótùú) *Languages and Linguistics in Nigeria.* A Festscrist in Honour of Kay williamson.
Taiwo, O. 2007. Short Subject Pronoun in the Ào dialect of Yorùbá. *JOLAN: Journal of Linguistic Association of Nigeria (JOLAN)* No 10 o.i. 67 – 86
Taiwo, O. 2008a. *Basic Concepts in Grammar*: Ibadan, DLC, UI
Taiwo, O. 2008b. *Basic Grammar*: Ibadan, DLC, UI
Taiwo, O. 2009. *Elementary Grammar*: Ibadan, DLC, UI
Taiwo, O. 2010. *Transformational Grammar I*: Ibadan, DLC, UI
Taiwo, O. 2011. *Mofoloji: Àtúnṣe kejì*. Ibadan: Ibadan, Universal Akada Books Limited.

## ÌPÍN 2 RÍRÚ ÒFIN ÈDÈ

**1.0** Ìfáárà
**2.0** Èròǹgbà àti Àfojúsùn
**3.0** Ìbéèrè Ìṣáájú
**4.0** Àkóónú Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
  **4.1** Òfin Èdè
  **4.2** Dídá pọ́n-na mọ̀ ninú ìsọ tàbí ìpèdè
  **4.3** Dìdà Ìbátan ẹ̀dà òye-ọ̀rọ̀ mọ̀
  **4.4** Ìlò-èdè
**5.0** Ìsọníṣókí
**6.0** Iṣẹ́ Ṣìṣe
**7.0** Ìwé Ìtọ́kasí/Àwọn Ìwé Fùn Kíkà

### 1.0 ÌFÁÁRÀ

Elédè mọ̀ bí ìsọ kan nínú èdè rẹ̀ bá ṣeégbà tàbí kò ṣeégbà. Àmọ́, kò ṣeé ṣe fún èlédè láti sọ àwọn òfin tó dè é tí irú ìsọ bẹ́ẹ̀ ṣe jẹ́ aṣeégbà tàbí àìṣeégbà. Àwọn onímọ̀ ẹ̀dá-èdè ni wọ́n máa ń láti ṣàwárí àwọn òfin wọ̀nyí ni ìbámù pẹ̀lú àwọn ohun tí elédè fara mọ́. Èyí já sí pé bí a bá rú ọkankan nínú àwọn òfin èdè yìí nínú ìsọ, ó di dandan kí irú ìsọ bẹ́ẹ̀ jẹ́ àìṣeégbà. Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, a ó máa ṣàlàyé irúfẹ́ àwọn òfin yìí nínú èdè Yorùbá

Commented [O.J26]: ṣeé gbà

Commented [O.J27]: máa ń ní láti

### 2.0 ÈRÒǸGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN

Lẹ́yìn tí ó bá ti ka ìpín yìí tán, wà á lè mọ ohun ti à ń pè ní òfin èdè àti bí rirú òfin èdè ṣe ń yọrí sí ìsọ àìṣeégbà nínú èdè Yorùbá. Wà á tún le ṣàlàyé ohun tí à ń pè ní ìlò-èdè àti bí ó ṣe yàtọ̀ sí Ìmọ̀-èdè.

### 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢÁÁJÚ

Kí ni o mọ̀ nípa òfin èdè
Ṣàlàyé ìyàtọ̀ láàrin Ìlò-èdè àti Ìmọ̀-èdè

Commented [O.J28]: Kí ni o mọ̀ nípa òfin èdè? Ṣàlàyé ìyàtọ̀ láàrin Ìlò-èdè àti Ìmọ̀-èdè.

### 4.0 ÀKÓÓNÚ ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

### 4.1 Òfin Èdè

Kò ṣeé ṣe fún èlédè láti sọ àwọn òfin inú èdè rẹ̀, ìyẹn láti sọ ìdí tí ìsọ tàbí ìpèdè kan fi jẹ́ aṣeégbà tàbí àìṣeégbà, ojúṣe onímọ̀ ẹ̀dá-èdè ni láti ṣàkíyèsí àwọn òfin wọ̀nyí ni ìbámù pẹ̀lú àwọn ohun tí elédè fara mọ́ pé ó ṣeégbà àti èyí tí kò ṣeégbà. Onímọ̀ èdá-èdè yóò ṣàwárí àwọn bátànì aṣeégbà àti àìṣeégbà inú èdè kàn, láti inú ìwọ̀nyí ni yóò ti wá àwọn àbùdá tí ń bẹ lẹ́yìn àwọn bátànì wọ̀nyí. Àwọn bùdá ati bátánì wọ́nyì ni a óò ṣàjọ gẹ́gẹ́ bí ohun èlò ìṣàpèjúwe gírámá èdè ọ̀hún.

Àmọ́ ṣá, àwọn onímọ̀ gbà pé elédè ní ìmọ̀ àwọn òfin èdè rẹ̀ ní àmọ̀dájú. Ìdí ni pé bí elédè bá gbọ́ ìsọ kan nínú èdè rẹ́, ó lè sọ gbangba bóyá ìsọ náà jẹ́ aṣeégbà tàbí àìṣeégbà. Ìmọ̀ yìí ni ó fún elédè ní àǹfàní láti sọ bóyá ẹnìkan tí rú òfin èdè rẹ̀ tàbí kò rú u. Bí o bá yẹ gbólóhùn ìsàlẹ̀ yìí wò:

Commented [O.J29]: rẹ̀

Ó ga o. O ti rógo.

Elédè Yorùbá mọ̀ pé gbólóhùn méjèèjì òkè yìí ṣeé gbà, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ó lè má mọ ohun tàbí nǹkan tí ó ga, tàbí ògo tí ó rí.

Elédè máa ń mọ̀ lo **òye-inú** láti mọ àwọn ìsọ tí wọ́n jẹ́ àìṣeégbà, nitori pé àwọn ìsọ bẹ́ẹ̀ kò tẹ̀lé òfin síńtáàsì èdè rẹ̀. Bí àpẹẹrẹ, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé elédè Yorùbá lè má lè fún ìsọ ìsàlẹ̀ yìí ní ìtumọ̀ dáadáa, papa síbẹ̀, wọ́n loye rẹ̀.

ṣó ṣó ṣó fírù balẹ̀

Commented [O.J30]: máa ń mọ̀ lo **òye-inú** ?

Yátọ̀ sí ìlóye rẹ̀ tí èdè Yorùbá ní, wọ̀n tún mọ̀ pé bí á bá da bí a ṣe tò ó rú, bí ó ṣe wà ní ìsàlẹ̀ yìí, kò bújú mu rara.

*balẹ̀ só fìrù só sò

Àlàyé wa yìí fi hàn pé, bí èdè kò tilẹ̀ lè fi ìtumọ̀ kan pàtó fún àwọn ọ̀rọ̀ tí a tò jọ, bí á bá tún àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí tò, èdè máa mọ̀ bóyá ìrú àtúntò bẹ́ẹ̀ kò tọ̀nà tàbí ó ti gbé ìtumọ̀ mìíràn jáde.

**ÌGBÉLÉWỌ̀N AKẸ́KỌ̀Ọ̀**
Ṣàlàyé bí Òfin èdè ṣe yé ọ sí

### 4.2 Dídá pọ́n-na mọ̀ ninú ìsọ tàbí ìpèdè

Ìmọ̀-èdè tí èdè ní máa ń jẹ́ kí ó ṣeé ṣe fún un láti lè sọ bóyá ìsọ tàbí ìpèdè kan jẹ́ onípọ́n-na. Ìyẹn ni pé bóyá irú ìpèdè ọ̀hún ní jú ìtumọ̀ kan lọ. Bí àpẹẹrẹ, èdè Yorùbá mọ̀ pé ó ṣeẹ ṣe kí gbólóhùn ìsàlẹ̀ yìí ní ju ìtumọ̀ kan lọ.

Ayọ̀ jẹ ìrẹsì àti dòdò

Gbólóhùn òkè yìí jẹ́ onípọ́nna. Ó ní ìtumọ̀ méjì ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ tí a lè fún un. Ní ìtumọ̀ kan, **ìrẹsì** àti **dòdò** lè dúró gẹ́gẹ́ bí oúnjẹ kan ṣoṣo. Ìyẹn ni pé ìtumọ̀ ìsọ̀kan wà láàárín **ìrẹsì** àti **dòdò.**

Olùwà = Ayọ̀; ọ̀rọ̀-ìṣe = jẹ; àbọ̀ = ìrẹsì àti dòdò

Ní ìtumọ̀ kejì ẹ̀wẹ̀, ìṣọ̀kan lè máa sí láàárín **ìrẹsì** àti **dòdò** kó jẹ́ pé oúnjẹ ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni wọ́n. Ìyẹn ni pé ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni Ayọ̀ wọ́n.

Ayọ̀ jẹ ìrẹsì. Ayọ̀ jẹ dodo

Àwọn ọ̀rọ̀ tàbí ìsọ bí ***gbà, jò tì*** ní ju ìtumọ̀ kan lọ. Èdè Yorùbá sì mọ̀ bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ bí a ṣe rí wọn nínú àpẹẹrẹ wọ̀nyí.

Olú ***gbá*** etí Ayọ/bọ́ọ̀lù Òjó
Ọmọbínrin náà ń ***gbá*** ilẹ
Iná ń ***jò.***
Ọmọbínrin náà ń ***jó.***
Ìyá wa ***ti ti*** ilẹ̀kùn
Ìbùkún fi Ọwọ́ rẹ̀ ***ti*** ara ògiri.

Àwọn gbólóhùn wọ̀nyí tún jẹ́ àpẹẹrẹ gbólóhùn onípọ́n-na;

Olú bú Ọpẹ́ jáde.
Orí mi wú.
Wọ́n bá wọn lọ.
Dídó dídò dé.
A jọ sùn ní àná.
Wòlíi náà máa ń rí èyàn pẹ̀lú ojú inú.

**ÌGBÉLÉWỌ̀N AKẸ́KỌ̀Ọ̀**
Ṣàlàyé **pọ́n-na** tí ó wà nínú àwọn ìsọ̀ yìí
- Wálé àti Táyọ̀ ra ọkọ̀ ayọ́kẹ́lẹ́



**Commented [O.J31]:** Kò yéni ohun tí èyí túmọ̀ sí.

**Commented [O.J32]:** *gbà àbí gbà?*

- Ọkọ̀ ló pa wọ́n pọ̀

### 4.3 Dìdà Ìbátan ẹ̀dà òye-ọ̀rọ̀ mọ̀

Ìmọ̀-èdè tí elédè ní máa ń fún un ní àǹfàní láti mọ àwọn gbólóhùn tí wọ́n jẹ́ onítumọ̀ kan náà yàtọ̀ sí èyí tí ìtumọ̀ rẹ̀ yàtọ̀ sí wọn. Elédè Yorùbá mọ̀ pé gbólóhùn méjì àkọ́kọ́ tí ó wà ní ìsàlẹ̀ yìí, ìyẹn gbólóhùn (2a) àti gbólóhùn (2b), jẹ́ onítumọ̀ kan náà, ṣùgbọ́n ìtumọ̀ gbólóhùn kẹta, ìyẹn gbólóhùn (2d), yàtọ̀ sí ti méjì àkọ́kọ́.

2a. Ajá ńlá yìí pa ológbò yẹn.
b. Ológbò yẹn ni ajá ńlá yìí pa.
d. Ológbò yẹn pa ajá ńlá yìí.

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé iye ọ̀rọ̀ kan náà tí ó wà ní gbólóhùn (2a) náà ni ó wà ní gbólóhùn (2d), pàpà síbẹ̀síbẹ̀, elédè Yorùbá mọ̀ pé ìtumọ̀ gbólóhùn mejeeji kìí ṣe ọ̀kan náà, ìtumọ̀ wọ yàtọ̀. Ìmọ̀-èdè tí elédè Yorùbá ní ni ó fi lè mọ èyí.

**ÌGBÉLÉWỌ̀N AKẸ́KỌ̀Ọ́**

Fi àpẹẹrẹ sàlàyé Ìbátan ẹ̀dà òye-ọ̀rọ̀ ni èdè Yorùbá

### 4.4 Ìlò-èdè

Àwọn onímọ̀ gírámà gbà pé ìmọ̀-èdè tì elédè ní yàtọ̀ sí bí elédè se má ń lo ìmọ̀ náà nínú ọ̀rọ̀ sísọ. Ìdí ni pé nígbà tí a bá ń sọ̀rọ̀, oríṣiríṣi ìdíwọ̀ tàbí àṣìṣe òun àṣìwí máa ǹ wáyé. Àwọn nǹkan bí irún ìwọ̀nyí kò sí ní jẹ́ kí elédè ṣàgbékalẹ̀ ìmọ̀-èdè tí ó ní láìsí àbùlà kankan. Ìmọ̀-èdè tí ó ní oríṣiríṣi àbùlà báwọ̀nyí ní àwọn onímọ̀ pè ní ìlò-èdè, tíí ṣe mimu èdè lò gan-an nigba tí a bá ń ṣàfọ̀ yàtọ̀ sí ìmọ̀-èdè tí elédè ní tí ó sì wà ní ọpọlọ rẹ̀. Àwọn onímọ̀ sì wá gbà pé bí a bá fẹ́ ṣàyẹ̀wò bí elédè ṣe mọ èdè rẹ̀, kò bójú mu tó kí á ṣàyẹ̀wò bí elédè ṣe lo èdè, tí ṣe Ìlò-èdè, tí ó kún fún oríṣiríṣi àṣìṣe àtí àṣìwí, dípò bẹ́ẹ̀, ìmọ̀-èdè tí ó wà ní ọpọlọ elédè ló yẹ kí a yẹ̀ wò. Ṣe gbogbo èèyàn ni ó mọ̀ pé bí a bá fẹ́ sọ̀rọ̀, a lè má bẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀ sísọ wa dáadáa, kí á kọ́kọ́ ronú fáṣẹ́yìn ká tó sọ̀rọ̀, kí á ṣàṣìṣe pẹ̀lú àtúnṣe. Bákan náà, bí a ṣe ń ṣàgbékalẹ̀ àwọn gbólóhùn àti bí a ṣe ń loye wọn pẹ̀lú wá lára ìlò-èdè tí á ń sọ nípa rẹ̀.

**Àwọn ìṣokùnfà ìlò-èdè**

Ogunlọ́gọ̀ ni àwọn nǹkan tí ó ń kópa nínú lílo èdè gan-an ní pàtó. Àwọn nǹkan wọ̀nyí, tí mo pè nì ìṣokùnfà ìlò-èdè, sí ní ó máa ń jẹ́ kí ìyàtọ̀ púpọ̀ wà láàárín ìmọ̀-èdè àti ìlò-èdè tí a ń sọ nípa rẹ̀. Díẹ̀ lára àwọn ìṣokùnfà náà ni mo máa mẹ́nu bá bayii.

- Irù ìmọ̀-èdè tàbí ìmọ̀ àìkọ́ni tí elédè ní. Bí eleyii kò bá péye, ìlò-èdè yóò mẹ́hẹ, elédè kò sì ní lè ṣàfọ̀ tí ó muna doko.
- **Irú tàbí ẹ̀dá** àti **òdiwọ̀n** ọ̀nà ìgbéjáde àfọ̀ àti ọ̀nà gbígbọ́ àfọ̀ elédè.
- Irú àti òdiwọ̀n **iyè-inú, ìfọkànsí, ìfarabalẹ̀** àti àwọn **ipá iyè** elédè mìíràn
- Sàkání **àwùjọ/ajẹmáwùjọ** àti **ipò** elédè
- Sàkání **ajẹméka-èdè/ẹ̀ka-èdè** elédè
- **Ìṣọwọ́-sọ̀rọ̀** àti **èdè ẹni** elédè
- Kókó ìmọ̀ àti èrò tí elédè ní nípa ibi tí ó ń gbé
- Ipò ìlera, **ìmọ̀lára** àti àwọn ipò ìjọra mìíràn tí elédè wà ní àkókò àfọ̀, ìyẹn nígbà tí elédè bá ń sọ̀rọ̀.

Ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn ìṣokùnfà wọ̀nyí ní wọ́n ń kó ipa nínú ìlò-èdè.

Bí o bá tẹ̀lé àwọn àlàyé àti ìíròrò wa, ó yẹ kí ó yé ẹ bayii pé ìmọ̀-èdè àti ìlò-èdè toju-tòdi àwa kò sí rò pé ò ṣeé ṣe láti yà wọ́n, nitori pé bí ìgbin fà, ìkaraun ń tẹ̀lé e ni àwọn méjèèjì jẹ̀. Ṣùgbọ́n mo gbọ́dọ̀ jẹ́

Commented [O.J33]: máa
Commented [O.J34]: irú
Commented [O.J35]: ní ni àwọn
Commented [O.J36]: nígbà
Commented [O.J37]: fàsẹ́yìn
Commented [O.J38]: **èdè ẹni** elédè???
Commented [O.J39]: báyìí

kí ó di mímọ̀ pé ìmọ̀-èdè, tí a sọ pé ó jẹ́ òye tí inú, ni a máa ń lò fún ìṣàpèjúwe gírámà, kìí ṣe ìlò-èdè rara. Àwọn àpẹẹrẹ tí mo ti ń lò nínú ìwé yìí, àti àwọn tí o máa pàdé láti ímọ̀-èdè elédè Yorùbá, kìí ṣe ti ìlò-èdè rárá. Láti tún ṣàlàyé síwájú síi pé ìmọ̀-èdè àti ìlò-èdè kò ṣe é yà, mo fẹ́ kí o mọ̀ pé ìlò-èdè ni a máa ń lò láti mọ tàbí ṣàwárí bí elédè ṣe ní ìmọ̀-èdè rẹ̀ sí.

Commented [O.J40]: ti
Commented [O.J41]: kì í
Commented [O.J42]: kì í

## 5.0 ÌSỌNÍṢÓKÍ

Elédè ní ìmọ̀ nípa àwọn òfin èdè rẹ̀, èyí ni ó fún un ni àǹfàní láti lè sọ gbangba bóyá ìsọ náà jẹ́ aṣeégbà tàbí àìṣeégbà. Ó ṣeé ṣe kí èlédè má lè sọ ní pàtó àwọn òfin tó dè é tí irú ìsọ bẹ́ẹ̀. Ojúṣe àwọn onímọ̀ ẹ̀dá-èdè ni láti ṣàwárí àwọn òfin wọ̀nyí ni ìbámù pẹ̀lú àwọn ohun tí elédè fara mọ́. Ìlo-èdè ni bí elédè se máa ń lo ìmọ̀ náà nínú ọ̀rọ̀ sísọ tàbí afọ̀ ṣíṣe. Ogunlọ́gọ̀ ni àwọn nǹkan tí ó ń kópa nínú lílo èdè. Èyí ni ó máa ń jẹ́ kí ìyàtọ̀ púpọ̀ wà láàárín ìmọ̀-èdè àti ìlò-èdè.

## 6.0 IṢẸ́ ṢÌṢE

Àwọn nǹkan wo ló máa ń fi ìyàtọ̀ han láàárín ìmọ̀-èdè àti ìlò-èdè?

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ/ÀWỌN ÌWÉ FÚN KÍKÀ


Awóbùlúyì, O. 1978. *Essentials of Yorùbá Grammar*, Ìbàdàn: UPL.
Awobuluyi, O. 1988. *Èdè Ìperí Yorùbá*: *Apá kejí*, Lagos: NERDC
Awóbùlúyì, O. 2001a. "Arọ́pò–Orúkọ Kúkúrú Ẹni–Kẹ́ta Ẹyọ Aṣolùwà" *Yorùbá*, Vol. 2, No. 1 pp 1-8
Awóbùlúyì, O. 2001b. "Òte–Ìlò Àwọn Arọ́pò–Orúkọ Kúkúrú" Bébà tí a kà ní Àpérò Ẹgbẹ́ Onímọ̀ ÈdèYorùbá: Yunifásítì ìlú Eko.
Awobuluyi, O. 2008. *Ẹ̀kọ́ Íṣẹ̀dá-Ọ̀rọ̀ Yorùbá*, Akurẹ: Montem Paperbacks
Awobuluyi, O. 2013. *Ẹ̀kọ́ Gírámà Èdè Yorùbá*, Oshogbo: Montem Paperbacks
Bámgbóṣé, Ạ. 1967. *A Short Yorùbá Grammar*, Ìbàdàn: HEB.
Bámgbóṣé, Ạ. 1990. *Fonọ́lọ́jì àti Gírámà Yorùbá*. Ìbàdàn: UPL.
Táíwò, O. 2003. Tense and Aspect in Àọ. Nínú Ndimele O.M (olótùú) *Languages and Linguistics in Nigeria*. A Festscrist in Honour of Kay williamson.
Taiwo, O. 2007. Short Subject Pronoun in the Àọ dialect of Yorùbá. *JOLAN: Journal of Linguistic Association of Nigeria (JOLAN)* No 10 o.i. 67 – 86
Taiwo, O. 2008a. *Basic Concepts in Grammar*: Ibadan, DLC, UI
Taiwo, O. 2008b. *Basic Grammar*: Ibadan, DLC, UI
Taiwo, O. 2009. *Elementary Grammar*: Ibadan, DLC, UI
Taiwo, O. 2010. *Transformational Grammar I*: Ibadan, DLC, UI
Taiwo, O. 2011. *Mofoloji: Àtúnṣe kejì*. Ibadan: Ibadan, Universal Akada Books Limited.

# ÌPÍN 3: ÀWÒRÁN ATỌ́KA-IGI

**1.0** Ìfáárà
**2.0** Èròǹgbà àti Àfojúsùn
**3.0** Ìbéèrè Ìṣáájú
**4.0** Àkóónú Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
  **4.1** Gírámà Èdè
  **4.2** Àwòrán Atọ̀ka-igi
**5.0** Ìsọníṣókí
**6.0** Iṣẹ́ Ṣíṣe
**7.0** Ìwé Ìtọ́kasí/Àwọn Ìwé Fùn Kíkà

## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Gírámà èdè ní ṣè pẹ̀lú ọmọ-inú gírámà bíi Àká-ọ̀rọ́, fonọ́lọ́jì, sínńtáàsì àti sẹ̀mánńtíìkì. Èyí tí a óò yànnàná nínú àwọn ìdánílẹ́kọ̀ọ́ inú yìí ni sínńtáàsì. A á ṣiṣẹ́ lórí àwọn ìhún aṣeégbà inú èdè Yorùbá. Mà á sì ṣàlàyé bí a ṣe ń fi fọnrán-ìhun gbólóhùn hàn ni àwòrán atọ́ka-igi.

Commented [O.J43]: ní í ṣè

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN

Lẹ́yìn tí o bá ti ka ìpín yìí tán, wà á lè mọ ìhún ìsọ̀rí sínńtáàsì kọ̀ọ̀kan ninú èdè Yorùbá. Wà á tún lè ṣàlàyé ẹ̀wọ́n nínú àwòrán atọ́ka-igi.

## 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢÁÁJÚ

Kí ni Ìsọ̀rí-sínńtáàsì?
Ṣàlàyé ẹ̀wọ́n nínú àwòrán atọ́ka-igi.

## 4.0 ÀKÓÓNÚ ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

### 4.1 Gírámà Èdè

Gírámà èdè ní ṣè pẹ̀lú àwọn èròjà tí èdè ní àti ìṣàpèjúwe wọn. Àwọn èròjà náà ni a lè pín sí ẹ̀yà tàbí ọmọ-inú gírámà wọ́nyì: Àká-ọ̀rọ́, fonọ́lọ́jì, sínńtáàsì àti sẹ̀mánńtíìkì.

Commented [O.J44]: ní í ṣè

1.




- **Àká-Ọ̀rọ̀** ni kíkó àwọn ọ̀rọ̀ inú èdè jọ láti fí ìtumọ̀ wọn, pípè wọn àti ìhun wọn hàn. Bákan náà, àká-ọ̀rọ́ dá lórí i ìbátan ọ̀rọ̀ kan àti òmíràn nínú èdè àti àwọn ọ̀nà tí a fi lè lò ó ni ṣíṣẹ̀dá gbólóhùn.
- **Fonọ́lọ́jì** dá lórí ìṣàpèjúwe àwọn ìró-ìfọ̀ inú èdè àti bí àwọn ìró-ìfọ̀ wọ̀nyí ṣe ń papọ̀ di ọ̀rọ̀.
- **Sínńtáàsì** ni ìṣàpàjúwe oríṣirísi àwọn ọ̀nà tí a fi máa ń so ọ̀rọ̀ papọ̀ láti di gbólóhùn.
- **Sẹ̀mánńtíìkì** ni ìṣàpèjùwe ọ̀rọ̀ àti bí ìtumọ̀ ìhun-ọ̀rọ̀ inú èdè ṣe jẹ́ ìtumọ̀ ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn ọ̀rọ̀ inú ìhun-ọ̀rọ̀ ọhún.

Commented [O.J45]: lórí ìbátan

Èyí tí a óò tẹpẹlẹ mọ́ nínú àwọn ìdánílẹ́kọ̀ọ́ inú ìwé yìí ni sínńtáàsì. Àwọn ohun tí a óò ṣiṣẹ́ lé lórí ni àwọn ìhún aṣeégbà inú èdè Yorùbá. A óò sì wo ìsọ̀rí sínńtáàsì kọ̀ọ̀kan àti ìhún wọn ninú èdè Yorùbá. Ìsọ̀rí-sínńtáàsì ni ọ̀rọ̀ tàbí àkójọ ọ̀rọ̀ ìnú èdè kan tí wọ́n lè rọ́pò ara wọn nínú ẹ̀hun èdè láì mú gbólóhùn

àìṣeégbà jáde. Bí ìsọ̀rí sínńtáàsì bá jẹ́ ẹyọ̀ ọ̀rọ̀, èyí yóò jẹ́ ìsòrí-ọ̀rọ̀, bí ó bá jẹ́ akójọpọ̀ ọ̀rọ̀, yóò di àpolà-ọ̀rọ̀. Bí àpẹẹrẹ

3a. [Adé] jẹ iṣu [Òjó] 4a. Ọmọ [náà] lu ìyá [yẹn]

b. [Òjó] jẹ iṣu [Adé] b. Ọmọ [yẹn] lu ìyá [náà]

5a. Olú ***ra*** bàtà pupa b. Olú ***gba*** bàtà pupa

Ní àpẹẹrẹ tí ó wà ní (3), *Adé* (3a) rọ́pò *Òjó* ni (3b), ní àpẹẹrẹ (4), *náà* (4a) rọ́pọ̀ *yẹn* ni (4b) Bákàn náà, ni *gbá* ni (5b) rọ́pọ̀ *rá* ni (5a). Ìrọ́pọ̀ wọ̀nyí kò sọ àwọn gbólóhún náà di àìṣeégbà, wọ́n bá òfin gírámà mu. Èyí fi hàn wá pè ìsọ̀rí-ọ̀rọ́ kan ni *Adé* àti *Òjó* jẹ́ tíí ṣè ọrọ̀-orúkọ (OR); ìsọ̀rí-ọ̀rọ̀ kan ni *náà* àti *yẹn* jẹ́ tíí ṣe ẹ̀yàn aṣàfihàn (AF), *rà* àti *gbà* ni (5a) àti (5b) náà jẹ́ ìsòrí-ọ̀rọ̀ kan náà tíí ṣe ọ̀rọ̀-ìṣe (IṢ). Ní àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí,

6a. [Ọmọ náà] lu [ìyá yẹn]

b. [Ìyá yẹn] lu [Ọmọ náà]

Ó ṣeé ṣe pé kí *Ọmọ náà* ní (6a) rọ́pò *ìyá yẹn* ní (6b), kí àbájáde irú ìrọ́pò bẹ́ẹ̀ sì tún bá òfin gírámà mu. Èyí túmọ̀ sí pé àpólà-ọ̀rọ̀ kan ni *ọmọ náà* àti *ìyá yẹn* jé, tíí ṣe Àpọ́là-Orúkọ (APOR).

**ÌGBÉLÉWỌ̀N AKẸ́KỌ̀Ọ́**

Ṣàlàyé ọ̀kọ̀ọ̀kan ẹ̀yà tí a lè pín èròjà gírámà èdè sí.

### 4.2 Àwòrán Atọ̀ka-igi

Nínú ìmọ̀ ẹ̀dá-èdè, ọ̀kan lára àwọn ète tí a sábà máa ń lò fún fífi fọ́nrán-ìhun gbólóhùn hàn ni àwòrán atọ́ka-igi. A ń pè é ní àwòràn atọ́ka-igi nítorí pé ó ní àwọn ẹ̀ká tí ó jọ àwọn ẹ̀ka igi. Ìyẹn ni pé ó pẹ̀ka gẹ́gẹ́ bí ti igi. Nínú àwòrán atọ̀ka-igi bẹ́ẹ̀, ìpèdè tàbí ẹ̀hun kan lè pẹ̀ka wá sí ìsàlẹ̀ láti fi orísirísi fọ́nrán-ìhun tí ó wà nínú ìpèdè tàbí ẹ̀hun bẹ́ẹ̀ hàn. Àwòrán atọ̀ka-igi jẹ́ ọ̀nà mìíràn láti fi ìhun gbólóhùn hàn.

A máa ń ṣàmúlò àwọn èdè ìperí fún ìṣàpèjúwe nínú àwòrán atọ́ka-igi. Mo máa ṣàlayé wọn ní ọ̀kọ̀ọ̀kan.

**Ẹ̀wọ́n**

Ó ṣeé ṣe kí àwòrán atọ́ka-igi pín sí ẹ̀ká tàbí kí a sọ pẹ̀ka. Ibí tí ẹ̀ka ti jáde wá yìí lára àwòrán atọ́ka-igi ni à ń pè ni ẹ̀wọ́n.

Commented [O.J46]: kí a sọ pẹ̀ka?????

1




A máa ń sàmì sí ẹ̀wọ́n kọ̀ọ̀kan nípa lílo àrokò èyí tí ó ń fi ìsọ̀rí hàn làti dúró fún fọ́nrán-ìhun kọ̀ọ̀kan.

Bí àpẹẹrẹ.

2a




b



**APOR**, **AROK**, **APOR, OR, AF** ni àwọn àrokò tí a lò láti fi sàmì sí ẹ̀wọ́n òkè yìí. Wọ́n sì fi yé wa irú fọ́nrán-ìhun tí ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn ń ṣe. A lè fi ọ̀rọ̀ tàbí wúnrẹ̀n onítumọ̀ àdámọ́ sámì sí ẹ̀wọ́n. Jẹ́ kí á wo àpẹẹrẹ yìí fún àlàyé.

3. Mo jẹ iṣu náà

A lè ya àwòrán atọ́ka-igi fún APOR méjì tí ó wà ní àpẹẹrẹ òkè yìí báyìí.




**Ẹ̀wọ́n Apẹ̀ka**
Nínú àwòrán atọ́ka-igi, bí ìlà tàbí ẹ̀ka méjì bá jáde láti ara ẹyọ ẹ̀wọ́n kan ṣoṣo, èyí ni a mọ̀ sí pé ẹ̀wọ́n bẹ́ẹ̀ pẹ̀ká tàbí pípẹ̀ka. Nínú àwòrán atọ́ka- igi àpẹẹrẹ (2b) àti (4b), ẹ̀wọ́n APOR pẹ̀ka nítorí pé ẹ̀ka méjì ló jáde láti ara wọn

**Ẹ̀wọ́n Aláìpẹ̀ka**
Bí ó bá jẹ́ pé ilà tàbí ẹ̀ka kan ṣoṣo ní ó jáde láti ara ẹ̀wọ́n kan nínú àwòrán atọ́ka-igi, á jẹ́ pé ẹ̀wọ́n ọ̀hún kò pẹ̀ka tàbí kò sí pípẹ̀ka. A ní láti mọ̀ pé nínú àwòrán atọ̀ka-igi kan, kò pọn dandan pé kí gbogbo ẹ̀wọ́n pẹ̀ka. Nínú àwọn àwòrán atọ́ka-igi tí ó wà ní àpẹẹrẹ (2a), ẹ̀wọ́n APOR jẹ́ ẹ̀wọ́n aláìpẹ̀ka, ní àpẹẹrẹ (4a), ẹ̀wọ́n APOR àti ẹ̀wọ́n OR náà jẹ́ aláìpẹ̀ka nítorí pé ẹ̀ka kan ṣoṣo ló jáde láti ara ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn.

**Ẹ̀wọ́n Agbẹ̀yìn**
Nínú àwòràn atọ́ka-igi, àwọn ẹwọ̀n tí ó wà ní ìsàlẹ̀ ni a mọ̀ sí ẹ̀wọ́n agbẹ̀yìn. Nínú àwọn àwòrán atọ́ka-igi tí ó wà ní àpẹẹrẹ (2) àti (4), ẹ̀wọ́n tí ó wà lábẹ́ ẹ̀wọ́n AROK ní (2a) àti (4a) jẹ́ ẹ̀wọ́n agbẹ̀yìn. Ní àpẹẹrẹ (2b) àti (4b), ẹ̀wọ́n tí ó wà lábẹ́ ẹ̀wọ́n OR àti AF ni ẹ̀wọ́n agbẹ̀yìn**.** Ohun tí a sì máa ń fi sàmì sí irú àwọn ẹ̀wọ́n ágbẹ̀yìn bẹ́ẹ̀ ni ọ̀rọ̀ tàbí wúnrẹ̀n onítumọ̀ àdámọ́ tí ó bá yẹ. Ní ọ̀nà mìíràn, a lè sọ pé ẹ̀wọ́n tí kò sí àrokò lábẹ rẹ̀ àfi ọ̀rọ̀ tàbí wúnrẹ̀n onítumọ̀ àdámọ́ ni à pè ní ẹ̀wọ́n agbẹ̀yìn. Àwọn ọ̀rọ̀ tàbí wúnrẹ̀n onítumọ̀ àdámọ́ tí a sì fi sàmì sí irú ẹ̀wọ́n agbẹ̀yìn bẹ́ẹ̀ ni à ń pè ní ***ìhun àgbẹ̀yìn***. Nínú àwòràn atọ́ka-igi àpẹẹrẹ (4), àwọn ẹ̀wọ́n ti a fi *mo, iṣu* àti *náà* sàmì sí ni ẹ̀wọ́n agbẹ̀yìn. Àwọn wúnrẹ̀n *mo, iṣu* àti *náà* ni ìhun àgbẹ̀yìn.

**Commented [O.J47]:** agbẹ̀yìn

**Commented [O.J48]:** ***ìhun àgbẹ̀yìn*** tàbí ***ìhun agbẹ̀yìn?***

**Ẹ̀wọ́n Aláìgbẹ̀yìn**
Nínú àwòrán atọ́ka-igi, ẹ̀wón tí o bá ní ẹ̀wọ́n mìíràn lábẹ́ rẹ̀ ni à ń pè ní ẹ̀wọ́n aláìgbẹ̀yìn. I.n.p ẹ̀wọ́n tí ó kù nínú àwòràn atọ̀ka-igi lẹ́yìn tí a bá ti yọ ẹ̀wọ́n àgbẹ̀yìn kúrò tán. Àrokò tí ó jẹ́ àmí afisọ̀rí-hàn ni a máa fi ń sàmì sí ẹ̀wọ́n aláìgbẹ̀yìn. Bí àpẹẹrẹ, nínú àwòrán atọ́ka-igi àpẹẹrẹ (4), àwọn ẹ̀wọ́n APOR, AROK, ní (4a) àti ẹ̀wọ́n APOR, OR àti AF ni (4b) jẹ́ ẹ́wọ́n aláìgbẹ̀yìn.

## 5.0 ÌSỌNÍṢÓKÍ
Gírámà èdè ní ṣè pẹ̀lú àwọn èròjà èdè, èyí tí a lè pín sí ọmọ-inú gírámà wọ́nyì: Àká-ọ̀rọ́, fonólọ́jì, sínńtáàsì àti sẹ̀máńtíìkì. Sínńtáàsì (èyí tí ó kàn wá gbọ̀ngbọ̀n ní ìpín yìí) ni ìṣàpàjúwe oríṣirísi àwọn ọ̀nà tí a fi máa ń so ọ̀rọ̀ papọ̀ láti di gbólóhùn. Àwòrán atọ́ka-igi ni ọ̀kan lára ọ̀nà tí a máa ń lò láti fi fọ́nrán-ìhun gbólóhùn hàn. Ẹ̀wọ́n ni ibí tí ẹ̀ka ti jáde lára àwòrán atọ́ka-igi.

**6.0 IṢẸ́ ṢÌṢE**

Kí ni ẹ̀wọ̀n nínú àwòrán atọ́ka-igi?

**7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ/ÀWỌN ÌWÉ FÙN KÍKÀ**

Awóbùlúyì, O. 1978. *Essentials of Yorùbá Grammar,* Ìbàdàn: UPL.
Awobuluyi, O. 1988. *Èdè Ìperí Yorùbá*: *Apá kejí*, Lagos: NERDC
Awóbùlúyì, O. 2001a. "Arọ́pò–Orúkọ Kúkúrú Ẹni–Kẹ́ta Ẹyọ Aṣolùwà" *Yorùbá*, Vol. 2, No. 1 pp 1-8
Awóbùlúyì, O. 2001b. "Òte–Ìlò Àwọn Arọ́pò–Orúkọ Kúkúrú" Bébà tí a kà ní Àpérò Ẹgbẹ́ Onímọ̀ ÈdèYorùbá: Yunifásítì ìlú Eko.
Awobuluyi, O. 2008. *Ẹ̀kọ́ Íṣẹ̀dá-Ọ̀rọ̀ Yorùbá*, Akurẹ: Montem Paperbacks
Awobuluyi, O. 2013. *Ẹ̀kọ́ Gírámà Èdè Yorùbá*, Oshogbo: Montem Paperbacks
Bámgbóṣé, Ạ. 1967. *A Short Yorùbá Grammar*, Ìbàdàn: HEB.
Bámgbóṣé, Ạ. 1990. *Fonọ́lọ́jì àti Gírámà Yorùbá*. Ìbàdàn: UPL.
Táíwò, O. 2003. Tense and Aspect in Ào. Nínú Ndimele O.M (olótùú) *Languages and Linguistics in Nigeria.* A Festscrist in Honour of Kay williamson.
Taiwo, O. 2007. Short Subject Pronoun in the Ào dialect of Yorùbá. *JOLAN: Journal of Linguistic Association of Nigeria (JOLAN)* No 10 o.i. 67 – 86
Taiwo, O. 2008a. *Basic Concepts in Grammar*: Ibadan, DLC, UI
Taiwo, O. 2008b. *Basic Grammar*: Ibadan, DLC, UI
Taiwo, O. 2009. *Elementary Grammar*: Ibadan, DLC, UI
Taiwo, O. 2010. *Transformational Grammar I*: Ibadan, DLC, UI
Taiwo, O. 2011. *Mofoloji: Àtúnṣe kejì.* Ibadan: Ibadan, Universal Akada Books Limited.

## ÌPÍN 4: ÌBÁTAN LÁÀÁRÍN Ẹ̀WỌ́N


**1.0** Ìfáárà
**2.0** Èròǹgbà àti Àfojúsùn
**3.0** Ìbéèrè Ìṣáájú
**4.0** Àkóónú Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
  **4.1** Ìhà Ìgàba
  **4.2** Ìwúlò ìhà ìgàba tàárà
  **4.3** Ìhà ìkọ́múpò
**5.0** Ìsọníṣókí
**6.0** Iṣẹ́ Ṣíṣe
**7.0** Ìwé Ìtọ́kasí/Àwọn Ìwé Fùn Kíkà


### 1.0 ÌFÁÁRÀ
Nínú àwòrán atọ̀ka-igi tàbí atọ́ka ìhun-gbólóhùn kan náà, ìhà ńlá méjì ni àwọn ẹ̀wọ́n lè kọ sí ara wọn. Àwọn ìhà méjì náà ni ìhà ìgàba àti ìhà ìkọ́múpò. Ní ìpín yìí, mà á ṣàlàyé ìhà ìgàba àti oríṣiríṣi ìhà mìíràn tí àwọn ẹ̀wọ́n lè kọ sí ara wọn nínú àwòrán atọ̀ka-igi. Mà á tún ṣàlàyé ohun ti a mọ̀ sí ìhà ìkọ́múpò.

### 2.0 ÈRÒŇGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN
Lẹ́yìn tí ó bá ti ka ìpín yìí, wà á lè ṣàlàyé ìhà ìgàba, ìhà ìkọ́múpò àti oríṣirisị ìhà mìíràn tí àwọn ẹ̀wọ́n lè kọ sí ara wọn nínú àwòrán atọ̀ka-igi.

### 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢÁÁJÚ
Ṣàlàyé oríṣirisị ìhà tí àwọn ẹ̀wọ́n lè kọ sí ara wọn nínú àwòrán atọ̀ka-igi.

### 4.0 ÀKÓÓNÚ ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́
### 4.1 Ìhà Ìgàba
Nínú àwòrán atọ́ka-igi tàbí atọ́ka-ìhun gbólóhùn, ohun tí ó máa ń fi ìhà ìgàba hàn ni ìlà tàbí ẹ̀ka tí ó so àwọn ẹ̀wọ́n pọ̀. Bí ẹ̀wọ́n kan bá wà lókè nínú àwòrán atọ́ka-igi, tí ẹ̀wọ́n mìíràn sì wà ní ìsàlẹ̀ ẹ̀wọ́n tí ó wà lókè, bí ọ̀nà tàárà tàbí ẹ̀ka bá wà láti ẹ̀wọ́n tí ó wà lókè náà si ẹ̀wọ́n tí ó wà ní ìsàlẹ̀ gẹ́gẹ́ bí àwọn ìlà tàbí ẹ̀ka inú àwòràn atọ́ka-igi ṣe fi hàn, ẹ̀wọ́n tí ó wà lókè gàba lórí ẹ̀wọ́n tí ó wà ní ìsàlẹ̀. Bí àpẹẹrẹ

Commented [O.J49]: àwòrán




Ní àpẹẹrẹ (5), ẹ̀wọ́n A gàba lé ẹ̀wọ́n B ní ìbámu pẹ̀lú àlàyé wa. Ní àpẹẹrẹ (4a) tí a tún dà kọ lókè, ẹ̀wọ́n APOR gába lórí ẹ̀wọ́n AROK àti ẹ̀wọ́n tí a fi *Mo* ṣàmì sí, ẹ̀wọ́n AROK náà gàba lórí ẹ̀wọ́n tí a fi *Mo* sàmì sí. Ní àpẹẹrẹ (4b) bákan náà, ẹ̀wọ́n APOR gàba lórí ẹ̀wọ́n OR, ẹ̀wọ́n AF àti ẹ̀wọ́n tí a fi *iṣu* àti èyí tí a fi *náà* sàmí sí. Ẹ̀wọ́n OR gàba lórí ẹ̀wọ́n tí a fi *iṣu* sàmí sí, ẹ̀wọ́n AF náà sì gàba lórí ẹ̀wọ́n tí a fi *náà* sàmí sí. Ṣùgbọ́n ẹ̀wọ́n OR kò gàba lórí ẹ̀wọ́n tí a fi *náá* sàmì sí, ẹ̀wọ́n AF náà kò gàba lórí ẹ̀wọ́n tí a fi *iṣu* sàmì sí.

Lábẹ́ ìhà ìgàba, a lè ya oríṣi ìhà ìgàba wọ̀nyí sọ́tọ̀: ìhà ìgàba tààrà àti ìhà ìgàba àkótán

**Ìhà Ìgàba Tààrà**

Nínú àwòrán atọ̀ka-igi tàbí atọ́ka-ìhun gbólóhùn, a máa ń sọ pé ẹ̀wọ́n A gàbá tààrà lé ẹ̀wọ́n B bí ìlà tàbí ẹ̀ka bá so ẹ̀wọ́n méjèèjì pọ̀ tí ẹ̀wọ́n A wà lókè tí ẹ̀wọ́n B sì wà ní ìsàlẹ̀ láìsí pé ẹ̀wọ́n mìíràn wà láàárín wọn. Bí àpẹẹrẹ, a lè fi ìhà ìgàba tààrà hàn nínú àwòrán atọ́ka-igi ìsàlẹ̀ yìí.

6a b




Ẹ̀wọ́n A gàba tààrà lé ẹ̀wọ́n B ní (6a), bákán náà ẹ̀wọ́n B gàba tààrà lé ẹ̀wọ́n D. Ṣùgbọ́n ẹ̀wọ́n A kò gàba tààrà lé ẹ̀wọ́n D nítorí pé ẹ̀wọ́n B wà láàárín ẹ̀wọ́n A àti ẹ̀wọ́n D. Ó yẹ kí ó rántí pé ẹ̀wọ́n A gàba lé ẹ̀wọ́n D, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé kò gàba tààrà lé e lórí. Ní àpẹẹrẹ (6b), ẹ̀wọ́n W gàba tààrà lé ẹ̀wọ́n H àti ẹ̀wọ́n Y, ẹ̀wọ́n H gàba tààrà lé ẹ̀wọ́n M, bákan náà, ẹ̀wọ́n Y gàba tààrà ẹ̀wọ́n L. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ẹ̀wọ́n W gàba lé ẹ̀wọ́n H, ẹ̀wọ́n Y, ẹ̀wọ́n M àti ẹ̀wọ́n L, kò gàba tààrà lé ẹ̀wọ́n M, nítorí pé ẹ̀wọ́n H wà láàárín rẹ̀ àti ẹ̀wọ́n M; bákan náà, ẹ̀wọ́n Y wà láàárín ẹ̀wọ́n W àti ẹ̀wọ́n L.

Lábẹ́ ìhà ìgàba tààrà, oríṣiriṣi ìhà mìíràn ni àwọn ẹ̀wọ́n tún lè kọ sí ara wọn. A sábà máa ń ṣàpèjúwe àwọn ìhà tí a ń wí yìí nípa lílo àwọn ọ̀rọ̀-ìpèrí tí ó dúró fún ẹ̀bí gẹ́gẹ́ bí Ọmọbìnrin, Arábìnrin, Ìyá abbl. Àpẹẹrẹ àwọn ìhà bẹ́ẹ̀ ni ìwọ̀nyí.

**Ẹ̀wọ́n Ọmọbìnrin**

Ẹ̀wọ́n Y ni ọmọbìnrin ẹ̀wọ́n W bí ẹ̀wọ́n Y bá jẹ́ ẹ̀wọ́n tí ẹ̀wọ́n W gàba tààrà lé lórí báyìí:




Ẹ̀wọ́n Y = Ọmọbìnrin ẹ̀wọ́n W

**Ẹ̀wọ́n ọmọbìnrin (apá) òsì**

Ẹ̀wọ́n Y ni ọmọbìnrin (apá) òsì ẹ̀wọ́n W bí ẹ̀wọ́n W bá gàba tààrà lé ẹ̀wọ́n Y lóri tí kò sì sí ẹ̀wọ́n mìíràn tí ẹ̀wọ́n W gàba lé lórí ní (apá) òsì ẹ̀wọ́n Y báyìí:




Ẹ̀wọ́n Y = Ọmọbìnrin (apá) òsì ẹ̀wọ́n W

**Ẹ̀wọ̀n Ọmọbìnrin (apá) ọ̀tún**

Ẹ̀wọ́n H ni ọmọbìnrin (apá) ọ̀tún ẹ̀wọ́n W bí ẹ̀wọ́n W bá gàba tààrà lé ẹ̀wọ́n H lórí, tí kò sì sí ẹ̀wọ́n mìíràn tí ẹ̀wọ́n W gàba lé lórí ní (apá) ọ̀tún ẹ̀wọ́n H báyìí:




Ẹ̀wọ́n H = Ọmọbìnrin (apá) ọ̀tún ẹ̀wọ́n W

**Commented [O.J50]:** Ẹ̀wọ́n

**Ẹ̀wọ̀n Arábìnrin**
Ẹ̀wọ́n Y àti ẹ̀wọ́n H jẹ́ arábìnrin bí ó bá jẹ́ pé ẹ̀wọ́n W kan náà nì ó gàba tààrà lè ẹ̀wọ́n Y àti ẹ̀wọ́n H lórí bayìí:




tàbí




(Ẹ̀wọ́n Y àti ẹ̀wọ́n H = ẹ̀wọ́n arábìnrin)

**Ẹ̀wọ̀n Arábìnrin (apá) òsì**
Ẹ̀wọ́n Y ni arábìnrin (apá) òsì ẹ̀wọ́n H bí ó bá jẹ́ pé ẹ̀wọ́n W kan náà ni ó gàba tààrà lè ẹ̀wọ́n Y àti ẹ̀wọ́n H lórí, tí ẹ̀wọ́n Y jẹ yọ ní (apá) òsì ẹ̀wọ́n H, tí kò sì sí ẹ̀wọ́n mìíràn ní ààrín ẹ̀wọ́n Y àti ẹ̀wọ́n H báyìí:




(Ẹ̀wọ́n Y = arábìnrin (apá) òsì ẹ̀wọ́n H)

**Ẹ̀wọ́n arábìnrin (apá) ọ̀tún**
Ẹ̀wọ́n H ni arábìnrin (apá) ọ̀tún ẹ̀wọ́n Y bí ó bá jẹ́ pé ẹ̀wọ́n W kan náà ni ó gàba tààrà lé ẹ̀wọ́n H àti ẹ̀wọ́n Y lórí tí ẹ̀wọ́n H sì jẹ yọ ní (apá) ọ̀tún ẹ̀wọ́n Y, tí kò sì sí ẹ̀wọ́n mìíràn lááárin ẹ̀wọ́n H àti ẹ̀wọ́n Y báyìí:




(Ẹ̀wọ́n H = arábìnrin (apá) òtún ẹ̀wọ́n Y)

**Ẹ̀wọ́n ìyá**
Ẹ̀wọ́n W ni ìyá ẹ̀wọ́n Y bí ó bá jẹ̀ pé ẹ̀wọ́n W gàba tààrà lé ẹ̀wọ́n Y lórí báyìí:




(Ẹ̀wọ́n W = ìyá ẹ̀wọ́n Y).

**ÌGBÉLÉWỌ̀N AKẸ́KỌ̀Ọ́**
Ṣàlàyé oríṣiríṣi ẹ̀wọ̀n nínú àwòrán atọ́ka-igi tí ó mọ̀

## 4.2 ÌWÚLÒ ÌHÀ ÌGÀBA TÀÀRÀ

Nínú gírámà onídàrọ, òye ìhà ìgàba tààrà wúlò púpọ̀ fún fífi lílo fọnrán hán gẹ́gẹ́ bí olùwà gbólóhùn, kókó gbólóhùn, àbọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe, abbl nínú gbólóhùn. Jẹ́ kí a yẹ atọ́ka ìhun gbólóhùn tàbí àwòrán atọ̀ka-igi fún gbólóhùn àpẹẹrẹ yìí wò.

7a. Èmi náà ti jẹ iṣu ní ilé.

b.




Nínú atọ́ka ìhun gbólóhùn, APOR tí APAPR bá gàba tàárà lè lórí ni olùwà gbólóhùn. Nítorí náà nínú atóka-ìhun gbólóhun àpẹẹrẹ (7b) APOR, (ìyẹn: Èmi nàà) ni olùwà gbólóhùn. Kókó gbólóhùn ni APIṢ tí APR$^I$ tíi ṣe orí fún gbólóhùn gàba táárá lé lóri. Nínú atóka-ìhun gbólóhùn àpẹẹrẹ tí a yà (7b), APIṢ, (iyẹn: jẹ isu ní ilé) ni kókó gbólóhùn. Bẹ́è sì ni APOR tí IṢ$^I$ gàba tàárà lé lóri ni àbọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣè nínú gbólóhùn. Nítorí náà, nínú àwòrán atọ́ka-igi tí a yà fún àpẹẹrẹ (7b) APOR$_2$ (ìyẹ́n: iṣu) ni àbọ̀ ọ̀rọ̀ -ìṣe.

### Ìhà Ìgàba Àkótán

Nínú àwòrán atọ́ka-igi tàbí atọ̀ka-ìhun gbólóhùn kan, ẹ̀wọ̀n kan gàba àkòtán lé fọ́nrán tàbí tẹ̀lẹ́ǹtẹ̀lẹ́ (ìyẹn àsopọ̀) fọ̀nrán mìíràn, bí ó bá jẹ́ pé ẹ̀wọ̀n tí a ń wí yìí gàba lé ẹ̀wọ̀n ọ̀hún nìkan ṣoṣo, tí kò sì gàba lé fọ̀nrán mîìràn jú ẹ̀wọ́n ọ̀hún lọ. Bí àpẹẹrẹ, ní àwòrán atọ́ka-igi ìsàlẹ̀ yìí, ẹ̀wọ́n W gàba àkótán lé ẹ̀wọ̀n Y àti àwọn ẹ̀wọ́n ti ẹ̀wọ̀n Y gàba lè lórí, ṣúgbọ̀n ẹ̀wọ̀n W kò gàbá lé ẹ̀wọ́n mìírán àfi ẹ̀wọ̀n Y nìkan.

Commented [O.J51]: lórí, iyẹn H àti L




### ÌGBÉLÉWỌ̀N AKẸ́KỌ̀Ọ̀

Báwo ni ìhà ìgàba tàárà ṣe wúlò

Commented [O.J52]: wúlò?

**4.3 ÌHÀ ÌKỌ́MÚPÒ**
Ìhà ìkọmúpò ń tọ́ka sí bí àwọn ẹ̀wọ́n ṣe tẹ̀lé ara wọn bí a bá wò wọ́n láti òsì lọ sí ọ̀tún lórí ìlà tí ó sì jẹ́ pé ẹ̀wọ́n ìyá kan náà ni àwọn ẹ̀wọ́n méjèèjì ní. Nígbà tí a bá sọ pé ẹ̀wọ́n kan ni ó kọ́ mú ipò tàbí pé ẹ̀wọ́n kan ni ó ṣáájú ọ̀míràn, ohun tí eléyìí túmọ̀ sí ni pé ẹ̀wọ́n tí a ń wí yìí jẹ yọ ní apá òsì ẹ̀wọ́n mìírán. Bí àpẹẹrẹ nínú àwòrán atọ́ka-igi òkè yìí, ẹ̀wọ́n Y jẹ́ ìyá ẹ̀wọ́n H àti ẹ̀wọ́n L nítorí pé ẹ̀wọ́n yìí gába le ẹ̀wọ́n méjèèjì lórí, ẹ̀wọ́n H ni ó kọ́ mú ipò kí ó tó kan ẹ̀wọ́n L, fún ìdì èyí, a máa ń sọ pé ẹ̀wọ́n H ṣáájú ẹ̀wọ́n L.

**ÌGBÉLÉWỌ̀N AKẸ́KỌ̀Ọ́**
Kí ni ìhà ìkọ́múpò

Commented [O.J53]: ìkọ́múpò?

**5.0 ÌSỌNÍṢÓKÍ**
Oríṣiriṣi ìhà ni àwọn ẹ̀wọ́n lè kọ sí ara wọn nínú àwòrán atọ̀ka-igi. Lára rẹ̀ ni ìhà ìgàba tí ó tọ́ka sí ìlà tàbí ẹ̀ka tí ó so àwọn ẹ̀wọ́n pọ̀, tí ẹ̀wọ́n mìíràn sì wà ní ìsàlẹ̀ rẹ̀. Lábẹ́ ìhà ìgàba, a lè ya oríṣi ìhà ìgàba wọ̀nyí sọ́tọ̀: ìhà ìgàba tàárà àti ìhà ìgàba àkótán. Ìhà ìkọmúpò ń tọ́ka sí bí àwọn ẹ̀wọ́n ṣe tẹ̀lé ara wọn bí a bá wò wọ́n láti òsì lọ sí ọ̀tún lórí ìlà tí ó sì jẹ́ pé ẹ̀wọ́n ìyá kan náà ni àwọn ẹ̀wọ́n méjèèjì ní.

**6.0 IṢẸ́ ṢÍṢE**
Fi ìyàtọ̀ hàn láàárin ìhà ìgàba àti ìhà ìkọ́múpò.

**7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ/ÀWỌN ÌWÉ FÙN KÍKÀ**
Awóbùlúyì, O. 1978. *Essentials of Yorùbá Grammar,* Ìbàdàn: UPL.
Awobuluyi, O. 1988. *Èdè Ìperí Yorùbá*: *Apá kejí,* Lagos: NERDC
Awóbùlúyì, O. 2001a. "Arọ́pò–Orúkọ Kúkúrú Ẹni–Kẹ́ta Ẹyọ Aṣolùwà" *Yorùbá,* Vol. 2, No. 1 pp 1-8
Awóbùlúyì, O. 2001b. "Òte–Ìlò Àwọn Arọ́pò–Orúkọ Kúkúrú" Bébà tí a kà ní Àpérò Ẹgbẹ́ Onímọ̀ ÈdèYorùbá: Yunifásítì ìlú Eko.
Awobuluyi, O. 2008. *Ẹ̀kọ́ Íṣẹ̀dá-Ọ̀rọ̀ Yorùbá,* Akurẹ: Montem Paperbacks
Awobuluyi, O. 2013. *Ẹ̀kọ́ Gírámà Èdè Yorùbá,* Oshogbo: Montem Paperbacks
Bámgbóṣé, Ạ. 1967. *A Short Yorùbá Grammar,* Ìbàdàn: HEB.
Bámgbóṣé, Ạ. 1990. *Fonọ́lọ́jì àti Gírámà Yorùbá.* Ìbàdàn: UPL.
Táíwò, O. 2003. Tense and Aspect in Ào. Nínú Ndimele O.M (olótùú) *Languages and Linguistics in Nigeria.* A Festscrist in Honour of Kay williamson.
Taiwo, O. 2007. Short Subject Pronoun in the Ào dialect of Yorùbá. *JOLAN: Journal of Linguistic Association of Nigeria (JOLAN)* No 10 o.i. 67 – 86
Taiwo, O. 2008a. *Basic Concepts in Grammar*: Ibadan, DLC, UI
Taiwo, O. 2008b. *Basic Grammar*: Ibadan, DLC, UI
Taiwo, O. 2009. *Elementary Grammar*: Ibadan, DLC, UI
Taiwo, O. 2010. *Transformational Grammar I*: Ibadan, DLC, UI
Taiwo, O. 2011. *Mofoloji: Àtúnṣe kejì.* Ibadan: Ibadan, Universal Akada Books Limited.

## MÓDÙ 2 ÀWÒRÁN ATỌ́KA-IGI ÀTI ÌHUN ÀPÓLÀ ORÚKỌ (APOR)

Èròǹgbà módù yìí ni láti ṣàlàyé bi a ṣe ń lo àwòrán atọ́ka-igi láti fi fọ́nrán ìhun hàn. Ní módù yìí, a ó wo ìhun àpólà orúkọ, mà á sì fi àwòrán atọ́ka-igi ṣàlàyé Àmúpè?, Àfikún àti Asọdọ̀tọ̀ inú ìhun àpólà orúkọ han. Ohun tí a máa ń lo àwòrán atọ́ka-igi fún ni láti fi fọ́nrán ìhun hàn, yálà ti àpólà tàbí gbólóhùn. Àwọn èròjà tí a lè rí nínú fọ́nrán ìhun ni Orí, Àmúpè, Àfikún àti Asọdọ̀tọ̀. Orí ni ó ṣe pàtàkì jùlọ nínú fọ́nrán ìhun, kànńpa sì ni pẹ̀lu. Òun gan-an ni a fi ń sọ orúkọ fọ́nrán ìhun. Àwọn èròjà yòókù tí ó wà nínú fọ́nrán ìhun jẹ ẹ̀yán/ẹ̀pọ́n. Ìyẹn ni pé Àmúpè, Àfikún àti Asọdọ̀tọ̀ jẹ́ ẹ̀yán/ẹ̀pọ́n fún Orí nínú fọ́nrán ìhun. Àmúpé ni ọ̀rọ̀ tí ó jẹ yọ pẹ̀lú ọ̀rọ̀ mìíràn láti mú kí ìtumọ̀ ọ̀rọ̀ náà pé. Àfikún ni ọ̀rọ̀-ìperí tí a máa ń lò fún fọ́nrán-ìhun tàbí ọ̀rọ̀ tí ó máa ń ṣe àfikún ìtumọ̀ òrí nínú ìhun. Asọdọ̀tọ̀ jẹ́ ọ̀rọ̀-ìperí tí a máa ń lò láti sọ nípa nǹkan kan ní ẹ̀kún rẹ́rẹ́ tàbí ní àìrúnilójú ṣùgbọ́n tí nǹkan ọ̀hún yóò fi yé èyàn yékéyéké.

Gbogbo àwọn èròjà inú fọ́nrán ìhun yìí ló ni bí a ṣe máa fi wọn hàn yàtọ̀ sí ara wọn nínú àwòrán atọ́ka-igi. Àpólà orúkọ ni a ó tẹnpẹlẹ mọ nínú módù yìí, ti mà á ṣàlàyé lẹsẹẹsẹ bi àwọn èròjà fọ́nrán ìhun yìí ṣe farahàn ní oríṣiríṣi Àpólà orúkọ nínú èdè Yorùbá.

Ní mòdú yìí, wà á kọ́ nípa Àmúpé, Àfikún àti Asọdọ̀tọ̀, wà á si rí i bí a ṣe ń fi wọn hàn ní àwòrán atọ́ka-igi. Lẹ́yìn náà, wà á kọ́ oríkì àpólà orúkọ, wà á sì mọ bí a ti ń fi àwòrán atọ́ka-igi ṣàlàyé Àmúpè, Àfikún àti Asọdọ̀tọ̀ nínú Àpólà Orúkọ (APOR). Àwọn àkòrí wọ̀nyí ni o máa kà ní módù yìí:

Ìpín 1: Fífi ẹ̀yán/ẹ̀pọ́n hàn nínú àwòrán atọ́ka-igi
Ìpín 2: Àmúpé, Àfikún àti Asọdọ̀tọ̀
Ìpín 3: Oríkì Àpólà Orúkọ
Ìpín 4: Àmúpè, Àfikún àti Asọdọ̀tọ̀ nínú Àpólà Orúkọ (APOR)

Commented [O.J54]: Àmúpè ni àbí Amúpé?

## ÌPÍN 1 FÍFI Ẹ̀YÁN/Ẹ̀PỌ́N HÀN NÍNÚ ÀWÒRÁN ATỌ́KA-IGI

**1.0** Ìfáárà
**2.0** Èròǹgbà àti Àfojúsùn
**3.0** Ìbéèrè Ìṣáájú
**4.0** Àkóónú Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
  **4.1** Ẹ̀yán/Ẹ̀pọ́n hàn nínú àwòrán atọ́ka-igi
  **4.2** Orí nínú àpólà
**5.0** Ìsọníṣókí
**6.0** Iṣẹ́ Ṣíṣe
**7.0** Ìwé Ìtọ́kasí/Àwọn Ìwé Fùn Kíkà

### 1.0 ÌFÁÁRÀ

A lè pín fọ́nrán-ìhun inú ẹ̀hun àpólà sí méjì gbòòrò, àwọn ni: Orí àti Ẹ̀yán/Ẹ̀pọ́n. Orí nínú ẹ̀hun àpólà kò ṣoro dámọ̀. Ìdí ni pé orí àpólà kan ni a fi ń pe àpólà bẹ́ẹ̀. Yàtọ̀ sí orí, ẹ̀yán/ẹ̀pọ́n ni àwọn fọ́nrán-ìhun yòókù nínú àpólà. Ní ìpín yìí, mà á ṣàlàyé orí àti ẹ̀yán/ẹ̀pọ́n nípa lílo àwòrán atọ́ka-igi.

### 2.0 ÈRÒǸGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN

Lẹ́yìn tí ó bá ti ka ìpín yìí wà á lè da orí mọ̀ yàtọ̀ sí ẹ̀yán/ẹ̀pọ́n nínú àpólà.

### 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢÁÁJÚ

Fi àpẹẹrẹ ṣàlàyé orí àti ẹ̀yán/ẹ̀pọ́n nínú àpólà.

### 4.0 ÀKÓÓNÚ ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

### 4.1 Ẹ̀YÁN/Ẹ̀PỌ́N HÀN NÍNÚ ÀWÒRÁN ATỌ́KA-IGI

Bí a bá fẹ́ fi ìrísí ẹ̀hun kan tàbi àpólà kan hàn, orí irú ẹ̀hun tàbí àpólà bẹ́ẹ̀ ni a kọ́kọ́ máa dá mọ̀. Láti dá orí mọ̀ kò nira púpọ̀. Ìdí ni pé orí àpólà kan ni a fi ń pe àpólà bẹ́ẹ̀. Bí àpẹẹrẹ, Ọ̀rọ̀-Orúkọ ni orí nínú Àpólà Orúkọ, Ọ̀rọ̀-Ìṣe ni orí nínú Àpólà Ìṣe, Ọ̀rọ-Aṣẹ̀pọ́n ni orí nínú Àpólà Aṣẹ̀pọ́n, abbl. Yàtọ̀ sí orí tí a yà sọ́tọ̀, àwọn fọ́nrán-ìhun mìíràn tí ó kù nínú àpólà ni a ń pè ní ẹ̀yán tàbí ẹ̀pọ́n. Ìhà tí àwọn ẹ̀yán/ẹ̀pọ́n nínú àpólà kọ sí orí yàtọ̀ sí ara wọn. Oríṣi ẹ̀yán/ẹ̀pọ́n mẹ́ta ni ó lè wà nínú ìhun àpólà kan. Àwọn ẹ̀yán/ẹ̀pọ́n kan lè jẹ́ ***àmúpé (complement)*** fún orí, àwọn kan lè jẹ́ ***àfikún (adjunct)***, oríṣi ẹ̀yán kẹta tí ó máa ń jẹ yọ nínú àpólà ni ***asọdọ̀tọ̀ (specifier).***

**Commented [O.J55]:** *àfikún* àbí *àrótì (adjunct)?*

Nínú àwòrán atọ́ka-igi, oríṣi ***ìyọrí (projection)*** mẹ́ta ni a máa ń yà sọ́tọ̀, àwọn ni ***ìyọrí akérépìn (minimal projection), ìyọrí abàárín (intermidiate projection)*** àti ***ìyọrí agajù (maximal projection).***

Orí nínú àpólà ni ó máa ń jẹ́ ìyọrí akérépìn, yóò ní ẹ̀yán/ẹ̀pọ́n àmúpé gẹ́gẹ́ bí arábìnrin rẹ̀. A óò kan àwọn méjèèjì, ìyẹn orí àti àmúpé, pọ̀ ***(kàn pọ̀ – merge), ìkànpọ̀ (merger)*** àwọn méjèèjì yóò di ìyọrí abàárín, ìyọrín abàárín yìí yòó ní àfikún gẹ́gẹ́ bí **arábìnrin** tirẹ̀. Bí a bá kan ìyọrí abàárín àti àfikún pọ̀, ìkànpọ̀ àwọn méjèèjì yóó di ìyọrín abàárín mìíràn, ìyọrín abàárín kejì yìí yóò gba asọdọ̀tọ́ gẹ́gẹ́ bí arábìnrin rẹ̀, àwọn méjèèjì, ìyẹn ìyọrín abàárín kejì àti asọdọ̀tọ̀ yóò papọ̀ di ìyọrí agajù.

**Commented [O.J56]:** akérépin

Bí a bá lo àrokò W fún àwọn ìyọrí tí a ń sọ nìpa rẹ̀, **W** tàbí $\mathbf{W^{O}}$ ni orí tí a ***dà pọ̀ (combine)*** mọ́ àmúpé, ìdàpọ̀ tàbí ìkànpọ̀ àwọn méjèèjì di $\mathbf{W^{I}}$, ìyẹn ìyọrí abàárín, gẹ́gẹ́ bí a ṣe ṣàlàyé ṣáájú, $W^{I}$ ni a mọ̀ sí ***ìyọrí onípele kan (single bar projection)***, ìyọrín abàárín yìí, ìyẹn $W^{I}$ àti àfikún yóò papọ̀ dí $W^{I}$ mìíràn tí ṣe ìyọrín abàárín kejì, gẹ́gẹ́ bí a ṣe ṣàlàyé ṣáájú, $W^{I}$ kejì yìí àti asọdọ̀tọ̀ tí ṣe arábìnrin rẹ̀ yóò papọ̀ di $W^{II}$, ìyẹn ìyọrí agajù, tí a ǹ pè ní ***ìyọrí onípele méjì (double bar projection).*** Àwòrán atọ́ka-igi ìsàlẹ̀ yìí ní ó fi àlàyé tí mo ṣe yìí hàn.

**Commented [O.J57]:** ní ó máa fi

1




**ÌGBÉLÉWỌ̀N AKẸ́KỌ̀Ọ́**
Kọ àpẹẹrẹ àwọn ẹ̀hun àpólà tí ó wù ọ́, kí o sì gbìyànjú kí o fàlà sí ori nínú ẹhun kọ̀ọ̀kan.

### 4.2 Orí nínú Àpólà

Àṣà fífún ìsọ tàbí ìpèdè kan ní àpèlé orí nínú ẹ̀hun jẹ́ èyí tí ó wọ́ pọ̀ nínú síńtáàsì. Orí nínú àpólà ni abala tí ó fi ìṣesí àpólà náà hàn. Ìdí nìyí tí ó fi jẹ́ pé orúkọ orí náà ni a fi máa ń pe ẹ̀hun náà. Èyí gan-an ló fà á tí a fi máa ń fún àkójọ ọ̀rọ̀ ní orúkọ bíi àpólà orúkọ, àpólà ìṣe abbl. Àwọn tí a fún ní orúkọ wọ̀nyí jẹ́ àwọn tí ó jẹ́ pé ìsọ̀rí-ọ̀rọ̀ tí a fi pè wọ́n ní ó jẹ́ orí nínú irú àkójọ ọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀. Bí àpẹẹrẹ, nínú àwọn ìsọ ìsàlẹ̀ wọ̀nyí,

2a. Ọmọ pupa náà
b. jẹ ìṣu

a óò sọ pé ìsọ àkọ́kọ́ (2a **ọmọ pupa náà**) jẹ́ àpólà-orúkọ, nígbà tí ìsọ kéjì (ìyẹn 2b **jẹ ìṣu**) jẹ́ àpólà ìṣe.

Ohun tí ó fa sábàbí orúkọ tí a fún ìsọ wọ̀nyí ní ṣe pẹ̀lú pé, bí wọ́n tilẹ̀ jẹ́ àkójọ ọ̀rọ̀, wọn lè ṣiṣẹ́ gẹ́gẹ́ bí ẹyọ ọ̀rọ̀. Fún àpẹẹrẹ, **ọmọ pupa náà** (2a) lè jẹ́ olùwà tàbí àbọ̀ gbólóhùn gẹ́gẹ́ bí ó ṣe jẹ yọ nínú àwọn gbólóhùn ìsàlẹ̀ yìí.

3a. **Ọmọ pupa náà** fẹ́ràn ẹ̀wà àti iṣu
b. Wálé rí **ọmọ pupa náà** ní ànà

**Ọmọ pupa náà** ni olùwà gbólóhùn àkọ́kọ́ (3a) òun sì ni ó jẹ́ àbọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe **rí** ní gbólóhùn kéjì (3b). Ọ̀rọ̀-orúkọ ni ó máa jẹ yọ gẹ́gẹ́ bí olùwà àti àbọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe nínú gbólóhùn ní àyè ìbi tí **ọmọ pupa náà** tí jẹ yọ gẹ́gẹ́ bí gbólóhùn ìsàlẹ̀ yìí ṣe fi hàn.

4a. **Olú** fẹ́ràn ẹ̀wà àti iṣu
b. Wálé rí **Olú** ní àná.

Yàtọ̀ sí pé àkójọ ọ̀rọ̀ **ọmọ pupa náà** ń ṣíṣẹ́ (tàbí jẹ yọ) ní àyè ibi tí ọ̀rọ̀-orúkọ tí máa ń ṣíṣẹ́ (tàbí jẹ yọ) tí ó sì fà á tí a fi ń pè é ní àpólà orúkọ, ìdí mìíràn tí a fi ń pè é ní àpólà orúkọ ní pé **ọmọ** tí ó jẹ́ àkọ́kọ́ nínú àkójọ ọ̀rọ̀ náà ní àwọn ọ̀rọ̀ méjì tí ó kù, ìyẹn **pupa** àti **náà** ń sọ nípa rẹ̀. Èyí jásí pé **ọmọ** ní ó jẹ́ **orí** nígbà tí **pupa** àti **náà** jẹ́ **ẹ̀yán**. Gẹ́gẹ́ bí a sì ti mọ̀ pé ọ̀rọ̀-orúkọ ni **ọmọ** tí a pè ní orí nínú ìsọ **ọmọ pupa náà**, ìdí nìyí tí a fí pé **ọmọ pupa náà** ní àpólà orúkọ.

Ohun tí àlàyé wa wọ̀nyí ń tọ́ka tàbí túmọ̀ sí ni pé orí àpólà kan gbọ́dọ̀ fara hàn tàbí kí a sọ pé orí àpólà kan gbọ́dọ̀ wà nínú àpólà bẹ́ẹ̀. Ohun tí a ń sọ ní pàtó ni pé ẹ̀hun kọ̀kọ̀ọ̀kan gbọ́dọ̀ ní orí, orí yìí sì ni àwọn fọ́nrán-ìhun yòókù gbára lé. Àtẹ ìsàlẹ̀ yìí ṣàfihàn W, $W^{I}$ àti $W^{II}$.

**5. Atẹ orí àti àwọn ìyọrí tàbí ìsọ̀rí mìíràn**

| ìyọrí/isọ̀rí akérépìn | ìyọrí/isọ̀rí abàárín | ìyọrí/isọ̀rí agajù |
|---|---|---|
| W | W[I] | W[II] tàbí APW |
| OR | OR[I] | OR[II] tàbí APOR |
| IṢ | IṢ[I] | IṢ[II] tàbí APIṢ |
| EP | EP[I] | EP[II] tàbí APEP |
| APR | APR[I] | APR[II] tàbí APAPR |
| AM | AM[I] | AM[II] tàbí APAM |

*APR ni àrokò tí a máa ń lò fún orí nínú ẹ̀hun tíí ṣe gbólóhùn, tí a sì máa ń lo àrokò AM fún orí nínú ẹ̀hun tíí ṣe awẹ́ gbólóhùn afarahẹ. A óò ṣàlàyé wọn láìpẹ́.*

Gẹ́gẹ́ bí mo ṣe fi hàn ní àtẹ òkè yìí, orí àpólà ni a so gbogbo àpólà náà mọ́. Ìdí níyì tí ó fi pọn dandan pé kí àpólà kan ní orí, àmọ́ ṣá, àpólàkápòláà kò gbọ́dọ̀ ni ju orí kan ṣoṣo lọ. Bákan náà, orí kan kò lè ní ju àpólà kan ṣoṣo.

**ÌGBÉLÉWỌ̀N AKẸ́KỌ̀Ọ̀**

Kọ ọ̀rọ̀ arọ́pò orúkọ márùn-un, kí o sì fàlà sí orí tí ó wà níbẹ̀

Commented [O.J58]: Ẹ yẹ ìgbéléwọ̀n yìí wò

## 5.0 ÌSỌNÍṢÓKÍ

Orí àti Ẹ̀yán/Ẹ̀pọ́n ni fọ́nrán-ìhun tí ó máa ń jẹyọ nínú ẹ̀hun àpólà. Orí àpólà kan ni a fi ń pe àpólà bẹ́ẹ̀. Yàtọ̀ sí orí, ẹ̀yán/ẹ̀pọ́n ni àwọn fọ́nrán-ìhun yòókù nínú àpólà.

## 6.0 IṢẸ́ ṢÍṢE

Kọ àpẹẹrẹ àpólà orúkọ márùn-ún àti Àpólà Ìṣe márùn-ún, kí o sì fàlà sí ori nínú ẹhun kọ̀ọ̀kan

Commented [O.J59]: Kò dà bí ẹni pé iṣẹ́ ìpín yìí mẹ́nuba àpólà ìṣe

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ/ÀWỌN ÌWÉ FÙN KÍKÀ


Awóbùlúyì, O. 1978. *Essentials of Yorùbá Grammar*, Ìbàdàn: UPL.

Awobuluyi, O. 1988. *Èdè Ìperí Yorùbá*: *Apá kejí*, Lagos: NERDC

Awóbùlúyì, O. 2001a. "Arọ́pò–Orúkọ Kúkúrú Ẹni–Kẹ́ta Ẹyọ Aṣolùwà" *Yorùbá*, Vol. 2, No. 1 pp 1-8

Awóbùlúyì, O. 2001b. "Òte–Ìlò Àwọn Arọ́pò–Orúkọ Kúkúrú" Bébà tí a kà ní Àpérò Ẹgbẹ́ Onímọ̀ ÈdèYorùbá: Yunifásítì ìlú Eko.

Awobuluyi, O. 2008. *Ẹ̀kọ́ Íṣẹ̀dá-Ọ̀rọ̀ Yorùbá*, Akurẹ: Montem Paperbacks

Awobuluyi, O. 2013. *Ẹ̀kọ́ Gírámà Èdè Yorùbá*, Oshogbo: Montem Paperbacks

Bámgbóṣé, Ạ. 1967. *A Short Yorùbá Grammar*, Ìbàdàn: HEB.

Bámgbóṣé, Ạ. 1990. *Fonọ́lọ́jì àti Gírámà Yorùbá*. Ìbàdàn: UPL.

Táíwò, O. 2003. Tense and Aspect in Ào. Nínú Ndimele O.M (olótùú) *Languages and Linguistics in Nigeria*. A Festscrist in Honour of Kay williamson.

Taiwo, O. 2007. Short Subject Pronoun in the Ào dialect of Yorùbá. *JOLAN: Journal of Linguistic Association of Nigeria (JOLAN)* No 10 o.i. 67 – 86

Taiwo, O. 2008a. *Basic Concepts in Grammar*: Ibadan, DLC, UI

Taiwo, O. 2008b. *Basic Grammar*: Ibadan, DLC, UI

## ÌPÍN 2: ÀMÚPÉ, ÀFIKÚN ÀTI ASỌDỌ̀TỌ̀

**1.0** Ìfáárà
**2.0** Èròǹgbà àti Àfojúsùn
**3.0** Ìbéèrè Ìṣáájú
**4.0** Àkóónú Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
  **4.1** Àmúpé
  **4.2** Àfikún
  **4.3** Asọdọ̀tọ̀
**5.0** Ìsọníṣókí
**6.0** Iṣẹ́ Ṣíṣe
**7.0** Ìwé Ìtọ́kasí/Àwọn Ìwé Fùn Kíkà

### 1.0 ÌFÁÁRÀ

Ẹyán/Ẹ̀pọ́n tí ó wà nínú àpólà lé jẹ́ àmúpé, àfikún tàbí asọdọ̀tọ̀. Ó ṣe é ṣe kí àwọn mẹ́tẹ̀ẹ̀ta jẹ yọ nínú àpólà tàbí kí méjì nínú wọn jẹ yọ. Nígbà mìíràn, ó lè jẹ́ ọ̀kan péré ni ó máa wà nínú ìhun àpólà kan. Ní ìpín yìí, mà á ṣàlàyé ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn ẹ̀yà Ẹyán/Ẹ̀pọ́n yìí.

### 2.0 ÈRÒǸGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN

Lẹ́yìn tí ó bá ti ka ìpín yìí tán, wà á lè fọ́nrán ìhun àmúpé, àfikún tàbí asọdọ̀tọ̀ yàtọ̀ sí ara wọn.

### 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢÁÁJÚ

Ṣe ìyàtọ̀ láààrin fọ́nrán ìhun àmúpé àti fọ́nrán ìhun àfikún

Commented [O.J60]: Ẹ sọ èyí di gbólóhùn ìbéèrè.

### 4.0 ÀKÓÓNÚ ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

### 4.1 Àmúpé

Àmúpé jẹ́ ọ̀rọ̀-ìperí tí a ń lò fún fọ́nrán tí a máa ń fi kún fọ́nrán mìíràn láti mú ìtumọ̀ tàbí ìhun tí a mọ̀ mọ́ fọ́nrán náà gún régí tàbí pé. Ìyẹn ni pé àmúpé ni ọ̀rọ̀ tí ó jẹ yọ pẹ̀lú ọ̀rọ̀ mìíràn láti mú kí ìtumọ̀ ọ̀rọ̀ náà pé. Kìí ṣe kànńpá ni pé àmúpé gbọ́dọ̀ jẹ yọ nínú ìhun àpólà, ṣùgbọ́n bí ó bá jẹ yọ, òun ni ó máa jẹ́ arábìnrin orí nínú àpólà. Ìdí tí èyí fi rí bẹ̀ẹ̀ ni pé àmúpè máa ń mú kí ìtumọ̀ fọ́nràn-ìhun tí ó jẹ́ orí pé nínú àpólà, kìí ṣe pé ó máa ń fi kùn ìtumọ̀ orí rárá. Ẹ jẹ́ kí a yẹ àwọn ìsọ tàbí ẹ̀hun wọ̀nyí wò kí àlàyé lè fẹsẹ̀ múlẹ̀ dáadáa.

6a. Olùkọ̀ ***síńtáàsì*** gíga náà
 b. Kọ́ ***ilé***
 d. Sí ***àdúgbò wa***

Commented [O.J61]: Ṣé kò dára kí a pe (6d) ní APAT tó ń ṣe iṣẹ́ ẹ̀pọ́n tí a bá fi wé (6a) àti (6b)?

Àpólà Orúkọ (APOR) ni ó wà ní (6a), àpẹẹrẹ (6b) jẹ́ Àpólà Ìṣe (APIṢ) nígbà tí àpẹẹrẹ (6d) jẹ́ Àpólà Aṣẹ̀pọ́n (APEP). Ọ̀rọ̀-Orúkọ (OR) ***olùkọ́*** ni orí nínú APOR (6a), Ọ̀rọ̀-Ìṣe (IṢ) ***kọ́*** ni orí nínú APIṢ (6b), Ọ̀rọ̀-Aṣẹ̀pọ́n (EP) ***sí*** sì ni orí nínú APEP (6d).

Àmúpè tí ó wà ní APOR ní (6a) lára àwọn ẹ̀yán ni ***síńtáàsì.*** Ìdí ni pé a mọ̀ pé ***olùkọ́*** (OR) orí nínú APOR (6a) gbọ́dọ̀ jẹ́ ẹni tí ó ń kọ́ ẹ̀kọ́ kan, ***síńtáàsì*** sì ni ẹ̀kọ́ ọ̀hún. Àwọn yòókù, ***gíga*** àti ***nàá*** kìí ṣe ẹ̀kọ́, fún ìdí èyí, wọn kìí ṣe àmúpé. Ẹyán ***síńtáàsì*** jẹ́ àmúpé nítorí pé ó jẹ́ kí a mọ̀ ẹ̀kọ́ tí ***olùkọ́*** ń kọ́, ó sì mú ìtumọ̀ ***olùkọ́*** pé. Ní àpẹẹrẹ (6b), ***ilé*** ni àmúpé fún ***kọ́,*** IṢ, tí ó jẹ́ orí nínú APIṢ. Ìdí ni pé ìtumọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe ***kọ́*** jẹ́ kí a mọ̀ pé ó gbọ́dọ̀ ní nǹkan tí a ń kọ́. Ní (6b), ***ilé*** ni nǹkan náà, ***ilé*** ni ó mú ìtumọ̀ ***kọ́*** pé. Ìdí nìyí tí a fi mọ̀ pé ***ilé*** ni àmúpè fún IṢ ***kọ́*** ní (6b). Àbùdá kan pàtàkì tí Ọ̀rọ̀-Aṣẹ̀pọ́n (EP) irú èyí ní

ni pé OR tàbí APOR gbọ́dọ̀ jẹ yọ tẹ̀lé e nínú APEP láti mú ìtumọ̀ rẹ̀ pé. Gẹ́gẹ́ a sì ṣe ṣàlàyé ṣáájú, EP ***sí*** orí ní àpẹẹrẹ APEP (6d), ***àdúgbò wa*** tí ó jẹ́ APOR sì ni àmúpé rẹ̀.
Bí o bá tẹ̀lé àlàyé àti ìtúpalẹ̀ tí mo ṣe wọ̀nyí, ó yẹ kí o ṣàkíyèsí pé bí ọ̀rọ̀ kan bá ṣe tan mọ́ orí nínú àpólà ni yóò fi hàn bóyá àmúpé ní ọ̀rọ̀ náà jẹ́ sí orí tàbí bẹ́ẹ̀ kọ́. Ìtumọ̀ tí irú ọ̀rọ̀ ọ̀hún bá fi hàn ni yóò jẹ́ kí á mọ̀ bóyá ó mù ìtumọ̀ orí pé tàbí bẹ́ẹ̀ kọ́.

Àkíyèsí mìíràn ni pé, bí a ṣe sọ pé àmúpé máa ń mú ìtumọ̀ orí pé yìí, kìí ṣe kànńpá ni pé orí gbọ́dọ̀ ní àmúpé nínú àpólà kan. Ní igbà mìíràn, àmúpé lè máa jẹ yọ nínú àpólà. Ni àpẹẹrẹ (6a) tí ó wà lókè, ò ṣe é ṣe kí ***sínńtáàsì*** tí ó jẹ́ àmúpè fún ***olùkọ́*** máa jẹ yọ gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ (6e) ṣe fi hàn ní ìsàlẹ̀ yìí, pàpà síbẹ̀síbẹ̀, kí àpólà náà ṣeé gbà.

6e. ***Olùkọ̀*** gíga náà

**ÌGBÉLÉWỌ̀N AKẸ́KỌ̀Ọ̀**
Ṣàlàyé àmúpé nínú fọ́nrán ìhun

## 4.2 Àfikún

Àfikún ni ọ̀rọ̀-ìperí tí a máa ń lò fún fọ́nrán-ìhun tàbí ọ̀rọ̀ tí ó máa ń ṣe àfikún ìtumọ̀ òrí nínú ìhun àpólà. Gẹ́gẹ́ bí mo ṣe ṣàlàyé ṣáájú, àfikún kìí mú kí ìtumọ̀ orí pé, ìlò tirẹ̀ nínú ẹ̀hun kan ni láti jẹ̀ kí a lóye ítumọ̀ tí a fún orí sí i. Kí àlàyé wa ba lè múná dóko, ẹ jẹ́ kí a yẹ àwọn àpẹẹrẹ wọ̀nyí wò.

Commented [O.J62]: kàn

7a. Olùkọ̀ sínńtáàsì ***gíga dúdú*** náà
b. Olùkọ̀ sínńtáàsì ***dúdú gíga*** náà

8a. Sùn ***ní àná ní oko wa***
b. Sùn ***ní oko wa ní àná***

Ní (7), ***gíga dúdú/dúdú gága*** ni àwọn àfikún tí ó wà nínú APOR, ní (8), ***ní àná ní oko/ní oko ní àná*** ni àfikún. Àwọn àfikùn ní (7) ṣàlàyé síwájú síi irú ẹni tí ***Olúkọ́ sínńtáàsì*** jẹ́, àwọn àfikún méjèèjì wọ̀nyí ń ṣe àfikùn sí ìtumọ̀ ***olùkọ́ sínńtáàsì.*** Ní (8), ***ní àná ní oko/ní oko ní àná*** náà ń ṣe àfikún ìgbà tí sísùn wáyé àti ibi tí ó ti wáyè.

Àkíyèsí kan pàtakì nípa àfikún ni pé ó ṣe é ṣe láti pààrọ̀ wọn sí ara wọn tí irú ìpààrọ̀ kò ní fa ìsọ àìṣeégbà, ṣùgbọ́n ìtumọ̀ wọn nìkan ni ó máa yàtọ̀. Ìdí nìyí tí ìpààrọ̀ wọn ní àpẹẹrẹ (7) àti (8) fi wáyé tí ìsọ wọ̀nyí sì jẹ́ aṣeégbà. A tún gbọ́dọ̀ kíyè sí i pé ẹ̀hun kan máa ń fàyè gba àfikún méjì tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ. Ohun tí mo ń sọ ni pé, ó ṣe é ṣe láti to àfikún pọ̀ nínú ìhun àpólà kan. Ní (7) àti (8) lókè, àfikún méjì méjì ni ó wà àpẹẹrẹ kọ̀ọ̀kan. Ní (9) ní ìsàlẹ̀ yìí, àfikún tí ó wà nínú àpólà orúkọ ju méjì lọ.

9. Ọkọ̀ ***akérò ńlá mẹ́jọ tí mo rà***

Ní àpẹẹrẹ (9), àfikún mẹ́rin ni ó wà nínú APOR yìí, àwọn náà ni ***akérò*** (OR), ***ńlá*** (AJ), ***mẹ́jọ*** (AK), àti ***tí mo rà*** (APAM). Bí ó ṣe jẹ́ pé àfikún mẹ́rin ni ó wà nínú APOR (9), kò sí ọ̀rọ̀-àsopọ̀ tí a fi so wọ́n pọ̀, a kàn tò wọ́n léra ni. Èyí jẹ́ ìyàtọ̀ kan pàtàkì tí ó wà láàárín àfikún àti àmúpé nítorí pé bí àmúpé méjì tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ bá jẹ yọ nínú àpólà, a gbọ́dọ̀ fi ọ̀rọ̀-àsopọ̀ so wọ́n pọ̀ tàbí kí a lo kọ́mà láti fi so wọ́n pọ̀ gẹ́gẹ́ bí a ṣe ṣe ní ìsàlẹ̀ yìí.

10a. Olùkọ̀ ***sínńtáàsì*** àti ***mofọ́lọ́jì*** gíga náà
b. Akẹ́kọ̀ọ́ Yorùbá, Sáyẹ́ńsì àti Ẹ̀dá-Èdè

**ÌGBÉLÉWỌ̀N AKẸ́KỌ̀Ọ́**
Ṣàlàyé àfikún nínú fọ́nrán ìhun

### 4.3 Asọdọ̀tọ̀

Asọdọ̀tọ̀ jẹ́ ọ̀rọ̀-ìperí tí a máa ń lò láti sọ nípa nǹkan kan ní ẹ̀kún rẹ́rẹ́ tàbí ní àìrúnilójú ṣùgbọ́n tí nǹkan ọ̀hún yóò fi yé èyàn yékéyéké. Fún àpẹẹrẹ, nínú APOR tí ó wà ní ìsàlẹ̀ yìí,

11a. Ọmọ b. Ọmọ ***náà*** d. Ọmọ ***yìí*** e. Ọmọ ***yẹn***

àpẹẹrẹ (11a) kò sọ ***ọmọ*** tí a ní lọ́kàn ní pàtó, ṣùgbọ́n (11b), (11d) àti (11e) sọ irú ***ọmọ*** tí a ní lọ́kàn. Àwọn wúnrẹ̀n tí ó jẹ́ kí a mọ èyí ni ***náà, yìí*** àti ***yẹn,*** àwọn sì ni ó jẹ́ kí a mọ̀ pé ***ọmọ*** tí ò wà nínú àpẹẹrẹ wọ̀nyí yàtọ̀ sí ara wọn, àwọn wúnrẹ̀n náà ni asọdọ̀tọ̀.

**ÌGBÉLÉWỌ̀N AKẸ́KỌ̀Ọ́**
Ṣàlàyé Asọdọ̀tọ̀ nínú fọ́nrán ìhun

## 5.0 ÌSỌNÍṢÓKÍ

Ní ìpín yìí, mo ṣàlàye oríṣi ẹ̀yà Ẹ̀yán/Ẹ̀pọ́n tí ó lè jẹyọ nínú àpólà. Àwọn ni: Àmúpé, Àfikún àti Asọdọ̀tọ̀. Ó ṣe é ṣe kí àwọn mẹ́tẹ̀ẹ̀ta jẹ yọ papọ̀ nínú àpólà tàbí kí méjì nínú wọn jẹ yọ. Ó sì ṣe é ṣe kí ọ̀kan nínú mẹ́tẹ̀ẹ̀ta jẹyọ nínú àpólà. Àmúpé jẹ́ ọ̀rọ̀-ìperí tí a ń lò fún fọ́nrán tí a máa ń fi kún fọ́nrán mìíràn láti mú ìtumọ̀ tàbí ìhun tí a mọ̀ mọ́ fọ́nrán náà gún régí tàbí pé. Àfikún ni ọ̀rọ̀-ìperí tí a máa ń lò fún fọ́nrán-ìhun tàbí ọ̀rọ̀ tí ó máa ń ṣe àfikún ìtumọ̀ òrí nínú ìhun àpólà. Asọdọ̀tọ̀ jẹ́ ọ̀rọ̀-ìperí tí a máa ń lò láti sọ nípa nǹkan kan ní ẹ̀kún rẹ́rẹ́ tàbí ní àìrúnilójú ṣùgbọ́n tí nǹkan ọ̀hún yóò fi yé èyàn yékéyéké.

## 6.0 IṢẸ́ ṢÍṢE

Ṣe ìyàtọ̀ láàárin ẹ̀yà Ẹ̀yán/Ẹ̀pọ́n Àmúpé, Àfikún àti Asọdọ̀tọ̀

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ/ÀWỌN ÌWÉ FÚN KÍKÀ


Awóbùlúyì, O. 1978. *Essentials of Yorùbá Grammar*, Ìbàdàn: UPL.
Awobuluyi, O. 1988. *Èdè Ìperí Yorùbá*: *Apá kejí*, Lagos: NERDC
Awóbùlúyì, O. 2001a. "Arọ́pò–Orúkọ Kúkúrú Ẹni–Kẹ́ta Ẹyọ Aṣolùwà" *Yorùbá*, Vol. 2, No. 1 pp 1-8
Awóbùlúyì, O. 2001b. "Òte–Ìlò Àwọn Arọ́pò–Orúkọ Kúkúrú" Bébà tí a kà ní Àpérò Ẹgbẹ́ Onímọ̀ ÈdèYorùbá: Yunifásítì ìlú Eko.
Awobuluyi, O. 2008. *Ẹ̀kọ́ Íṣẹ̀dá-Ọ̀rọ̀ Yorùbá*, Akurẹ: Montem Paperbacks
Awobuluyi, O. 2013. *Ẹ̀kọ́ Gírámà Èdè Yorùbá*, Oshogbo: Montem Paperbacks
Bámgbóṣé, Ạ. 1967. *A Short Yorùbá Grammar*, Ìbàdàn: HEB.
Bámgbóṣé, Ạ. 1990. *Fonọ́lọ́jì àti Gírámà Yorùbá*. Ìbàdàn: UPL.
Táíwò, O. 2003. Tense and Aspect in Ào. Nínú Ndimele O.M (olótùú) *Languages and Linguistics in Nigeria*. A Festscrist in Honour of Kay williamson.
Taiwo, O. 2007. Short Subject Pronoun in the Ào dialect of Yorùbá. *JOLAN: Journal of Linguistic Association of Nigeria (JOLAN)* No 10 o.i. 67 – 86
Taiwo, O. 2008a. *Basic Concepts in Grammar*: Ibadan, DLC, UI
Taiwo, O. 2008b. *Basic Grammar*: Ibadan, DLC, UI

**ÌPÍN 3: ÌHUN ÀPÓLÀ ORÚKỌ**


**1.0** Ìfáárà
**2.0** Èròǹgbà àti Àfojúsùn
**3.0** Ìbéèrè Ìṣáájú
**4.0** Àkóónú Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
**4.1** Oríkì àpólà orúkọ
**4.2** Ìhun Àpólà Orúkọ (APOR)
**4.3** Ìrísí APOR ní ibi tí OR ti jẹ́ orí
**5.0** Ìsọníṣókí
**6.0** Iṣẹ́ Ṣìṣe
**7.0** Ìwé Ìtọ́kasí/Àwọn Ìwé Fùn Kíkà


## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Ọ̀kan gbòógì lára àpólà tí ó máa ń jẹyọ nínú ẹ̀hun gbólóhùn ni àpólà orúkọ. Ní ìpín yìí, mà á ṣàlàyé ohun ti apólà jẹ́; ìhun àpólà orúkọ; ati ìrísí àpólà orúkọ.

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN

Lẹ́yìn tí ó bá ti ka ìpín yìí, wà á lè ki oríkì àpólà orúkọ, wà á sì lè dá ìhun àpólà orúkọ mọ̀ nínú gbólóhùn.

## 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢÁÁJÚ

Fún àpólà orúkọ ní oríkì.

## 4.0 ÀKÓÓNÚ ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

### 4.1 Oríkì àpólà orúkọ

Àpólà orúkọ (APOR) ni èyọ ọ̀rọ̀ tàbí àsopọ̀ ọ̀rọ̀ tí a lè lò gẹ́gẹ́ bi olùwà gbólóhùn tàbí àbọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe tàbí àmúpé ọ̀rọ̀-atọ́kùn nínú gbólóhùn aṣeégbà. Bí àpẹẹrẹ:

1a. Ọkùnrin yẹn pa ajá náà.
b. Adé bú Ojó.
d. Èmi rí wọn ní ilé Ayọ̀.
e. Áwọn náà gbọ́ orin wa.
ẹ. Mo rí ẹ ní àná.

Commented [O.J63]: Òjó

Nínú àwọn gbólóhùn tí ó wà lókèè yìí, àwọn àpólà orúkọ àti bí a ṣe lò wọn ni a fà yọ ní ìsàlẹ̀ yìí.

2. **Àpólà Orúkọ àti Ipò Rẹ̀**

| **Ipò** | **Àpólà Orúkọ** |
|---|---|
| Olùwà | Ọkùnrin yẹn (1a), Adé (1b), Èmi (1d), Áwọn náà (1e), Mo (1ẹ) |
| Àbọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe | ajá náà (1a), Ojó (1b), wọn (1d), orin wa, (1e), ẹ (1ẹ) |
| Àmúpé ọ̀rọ̀-Aṣẹ̀pọ́n | ilé Ayọ̀ (1d), àná, (1ẹ) |

**ÌGBÉLÉWỌ̀N AKẸ́KỌ̀Ọ́**
Ki oríkì Àpólà Orúkọ

**4.2 Ìhun Àpólà Orúkọ (APOR)**

Abala méjì gbòòrò ni a lè pín ìhun APOR sí. Àwọn náà ni orí àti ẹ̀yán. Nínú àwọn méjèèjì, kanńpá ni orí jẹ́, dandan tí ó gbọdọ̀ jẹ yọ nínú ìhun APOR, kò sí APOR tí kìí ní orí. Sùgbọ́n ẹ̀yán kìí ṣe dandan, ìwọ̀fún ni. Ìyẹn ni pé ẹ̀yán lè jẹ yọ nínú APOR, ó sì lè máà jẹ yọ. Àwọn ìsọ̀rí gírámà tí a sábà máa ń lò gẹ́gẹ́ bí orí nínú APOR ni ọ̀rọ̀-orúkọ (OR) tàbí arọ́pò-orúkọ (AR). Àlàyé tí a ṣe lórí ìhun àpólà orúkọ yìí ni ó wà ní àtẹ ìsàlẹ̀ yìí.

3. **Ìhun Àpólà Orúkọ**




Gẹ́gẹ́ bí ó ṣe wà ní àtẹ òkè yìí, ọ̀rọ̀-orúkọ (OR), arọ́pò-orúkọ gígùn (AROG) àti arọ́pò-orúkọ kúkúrú (AROK) ni ó lè jẹ́ orí nínú ìhun àpólà orúkọ. Nínú àwọn mẹ́ẹ̀ẹ̀ta wọ̀nyí, arọ́pò-orúkọ kúkúrú (AROK) kìí gba ẹ̀yán nínú àpólà orúkọ, ńṣe ni ó máa ń dá wà. Ọ̀rọ̀-orúkọ (OR) àti arọ́pò-orúkọ gígùn (AROG) máa ń gba ẹ̀yán, wọn sì lè máà gba ẹ̀yán gẹ̀gẹ̀ bí orí nínú ìhun àpólà orúkọ (APOR).

**ÌGBÉLÉWỌ̀N AKẸ́KỌ̀Ọ́**
Ṣàlàyé àwọn ìsọ̀rí ọ̀rọ̀ tí o le jẹ́ orí nínú àpólà orúkọ

**4.3 Ìrísí APOR ní ibi tí OR ti jẹ́ orí**

Onírúurú ìsọrí gírámà ni a lè lò gẹ́gẹ́ bí ẹ̀yán nínú Àpólà Orúkọ (APOR). Nínú ìhun Àpólà Orúkọ ní ibi tí Ọ̀rọ̀ orúkọ (OR) ti jẹ́ orí, irú Ọ̀rọ̀-orúkọ (OR) bẹ́ẹ̀ lè gba ẹ̀yán lóríṣiríṣi. Irú àwọn ẹ̀yán tí ó lè gbà ni: ẹ́yán ajórúkọ; èyí lè jẹ́ Ọ̀rọ̀-orúkọ (OR) tàbí Arọ́pò-orúkọ kúkúrú (AROK), ẹ́yán aṣàpèjúwe (AJ), ẹ́yán aṣòǹkà (AK), ẹ́yán awẹ-gbólóhùn aṣàpèjúwe tí a ń pè ní àpólà aṣàmúpé (APAM) àti ẹ́yán aṣàfihàn (AF).

Ọ̀rọ̀-orúkọ (OR) tí ó jẹ́ orí nínú APOR lè gba ọ̀kan nínú àwọn ẹ̀yán tí ó wà lókè yìí tàbí kí ó gbà ju ọ̀kan lọ. Ṣùgbọ́n kò dà bí ẹni pé ó lè gba gbogbo àwọn ẹ̀yán mẹ́fẹ̀ẹ̀fà lẹ́ẹ̀kan ṣoṣo tán. Àmọ́ ṣa, kìí ṣe dandan ni fún Ọ̀rọ̀-òrúkọ (OR) láti gba ẹ̀yán, wọ̀fún ni ẹ̀yán jẹ, kìí ṣe kànńpá.

**Tẹ̀léǹtẹ̀lé Ẹ̀yán**

Bí àwọn ẹ̀yán ṣe máa ń tẹ̀lé ara wọn nínú àpólà orúkọ níbi tí Ọ̀rọ̀-Orúkọ (OR) ti jẹ́ orí ni ó wà ní ìsàlẹ̀ yìí.

4. **Tẹ̀léǹtẹ̀lé Ẹ̀yán**

| **Orí** | **Ẹ̀yán** | | | | | |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | **1** | **2** | **3** | **4** | **5** | **6** |
| **Ọ̀rọ̀-orúkọ** | **Ajórúkọ** | **Aṣàpèjúwe** | **Aṣòǹkà** | **Awẹ́ Gbólóhùn** | **Aṣàfihàn** | **Àtọ́ka Aṣàfihàn** |
| ọkọ̀ | Akérò | Ńlá | méjọ | tí mo rà | Yìí | gan-an |
| iṣu | rẹ̀ | | | tí ẹran jẹ | Náà | pàápàá |
| iṣẹ́ | awakọ̀ | | | tí mo kọ́ | | nìkan |
| ọkọ̀ | ayọ́kẹ́lẹ́ | Dúdú | | tí Délé rà | | gan-an |
| àwọn | Ìyàwó | Pupa | mẹ́tẹ̀ẹ̀ta | tí lèmọ́mù fẹ́ | | wọ̀nyẹn |

Ní ibi tí OR bá dá wà gẹ́gẹ́ bí orí tí kò gba ẹ̀yán kankan nínú APOR, gẹ́gẹ́ bí ó ṣe wà nínú gbólóhùn ìsàlẹ̀ yìí

5a. Olú lọ.

APOR, ***Olú*** ni olùwà gbólóhùn òkè yìí. Ìrísí APOR náì ni ó wà ní ìsàlẹ̀ yìí

Commented [O.J64]: náà

5b
APOR
|
OR[1]
|
Olú

## ÌGBÉLÉWỌ̀N AKẸ́KỌ̀Ọ́

Ṣàlàyé bi àwọn ẹ̀yán ṣe tẹ̀lé ara sí nínú àpólà orúkọ

## 5.0 ÌSỌNÍṢÓKÍ

Ní ìpín yìí, mo ṣàlàye ìhun àpólà orúkọ (APOR). Àpólà orúkọ (APOR) ni èyọ ọ̀rọ̀ tàbí àsopọ̀ ọ̀rọ̀ tí a lè lò gẹ́gẹ́ bi olùwà gbólóhùn tàbí àbọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe tàbí àmúpé ọ̀rọ̀-atọ́kùn nínú gbólóhùn aṣeégbà. Ìhun APOR ni a lè pín sí Orí àti Ẹ̀yán. Ọ̀rọ̀-orúkọ (OR) tàbí arọ́pò-orúkọ (AR) ni ìsọ̀rí gírámà tí a sáábà máa ń lò gẹ́gẹ́ bí orí nínú APOR. Àmọ̀ onírúurú ìsọrí gírámà ni a lè lò gẹ́gẹ́ bí ẹ̀yán nínú Àpólà Orúkọ (APOR).

Commented [O.J65]: àtọ̀pọ̀

Commented [O.J66]: Àpólà-orúkọ

## 6.0 IṢẸ́ ṢÍṢE

Fi àpẹẹrẹ ṣàlàyé ìhun Àpólà Orúkọ ní ibi tí Ọ̀rọ̀ orúkọ ti jẹ́ orí

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ/ÀWỌN ÌWÉ FÙN KÍKÀ

Awóbùlúyì, O. 1978. *Essentials of Yorùbá Grammar*, Ìbàdàn: UPL.
Awobuluyi, O. 1988. *Èdè Ìperí Yorùbá*: *Apá kejí*, Lagos: NERDC
Awóbùlúyì, O. 2001a. "Arọ́pò–Orúkọ Kúkúrú Ẹni–Kẹ́ta Ẹyọ Aṣọlùwà" *Yorùbá*, Vol. 2, No. 1 pp 1-8
Awóbùlúyì, O. 2001b. "Òte–Ìlò Àwọn Arọ́pò–Orúkọ Kúkúrú" Bébà tí a kà ní Àpérò Ẹgbẹ́ Onímọ̀ ÈdèYorùbá: Yunifásítì ìlú Eko.
Awobuluyi, O. 2008. *Ẹ̀kọ́ Íṣẹ̀dá-Ọ̀rọ̀ Yorùbá*, Akurẹ: Montem Paperbacks
Awobuluyi, O. 2013. *Ẹ̀kọ́ Gírámà Èdè Yorùbá*, Oshogbo: Montem Paperbacks
Bámgbóṣé, Ạ. 1967. *A Short Yorùbá Grammar*, Ìbàdàn: HEB.
Bámgbóṣé, Ạ. 1990. *Fonọ́lọ́jì àti Gírámà Yorùbá*. Ìbàdàn: UPL.
Oyetade, S.O. 1995. *Yorùbá Grammar I*. Ibadan, Centre for External Studies, UI.

Táíwò, O. 2003. Tense and Aspect in Ào. Nínú Ndimele O.M (olótùú) *Languages and Linguistics in Nigeria.* A Festscrist in Honour of Kay williamson.
Taiwo, O. 2007. Short Subject Pronoun in the Ào dialect of Yorùbá. *JOLAN: Journal of Linguistic Association of Nigeria (JOLAN)* No 10 o.i. 67 – 86
Taiwo, O. 2008a. *Basic Concepts in Grammar*: Ibadan, DLC, UI
Taiwo, O. 2008b. *Basic Grammar*: Ibadan, DLC, UI

## ÌPÍN 4: ÀMÚPÈ, ÀFIKÚN ÀTI ASỌDỌ̀TỌ̀ NÍNÚ ÀPÓLÀ ORÚKỌ (APOR)


**1.0** Ìfáárà
**2.0** Èròǹgbà àti Àfojúsùn
**3.0** Ìbéèrè Ìṣáájú
**4.0** Àkóónú Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
- **4.1** Àmúpè, Àfikún àti Asọdọ̀tọ̀ nínú àpólà orúkọ (APOR)
- **4.2** Ìrísí APOR ní ibi tí Arọ́pò-Orúkọ Gígùn (AROG) ti jé orí
- **4.3** Ìrísí APOR ní ibi ti AROK ti jẹ́ orí

**5.0** Ìsọníṣókí
**6.0** Iṣé Ṣìṣe
**7.0** Ìwé Ìtọ́kasí/Àwọn Ìwé Fún Kíkà


Commented [O.J67]: Ṣíṣe

### 1.0 ÌFÁÁRÀ
Ní ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tó kọjá, a kọ́ Àmúpè, Àfikún àti Asọdọ̀tọ̀. Ní ìpín yìí, mà á ṣàlàyé bí Àmúpè, Àfikún àti Asọdọ̀tọ̀ jẹyọ nínú àpólà orúkọ (APOR). Mà á tún ṣàlàyé ìrísí APOR ní ibi tí Arọ́pò-Orúkọ Gígùn (AROG) ti jé orí àti Ìrísí APOR ní ibi ti AROK ti jẹ́ orí.

### 2.0 ÈRÒŃGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN
Lẹ́yìn tí ó bá ti ka ìpín yìí, wà á lè fi àworán atọ́ka-igi ṣàlàyé bí Àmúpè, Àfikún àti Asọdọ̀tọ̀ jẹyọ nínú àpólà orúkọ. Wà á tún mọ ìrísí àpólà orúkọ ní ibi tí Arọ́pò-Orúkọ Gígùn (AROG) ti jé orí àti ibi ti AROK ti jẹ́ orí.

Commented [O.J68]: jẹ́

### 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢÁÁJÚ
Ṣàlàyé Àmúpè, Àfikún àti Asọdọ̀tọ̀ nínú àpólà orúkọ

Commented [O.J69]: Ẹ yí èyí sí ojúlówó ìbéèrè

### 4.0 ÀKÓÓNÚ ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́
#### 4.1 Àmúpè, Àfikún àti Asọdọ̀tọ̀ nínú àpólà orúkọ (APOR)
Gẹ́gẹ́ bí mo ṣe ṣàlàyé ṣáájú, ojúṣe àmúpé ni láti mú kí ìtumọ̀ Ọ̀rọ̀-Orúkọ (OR) tí ó jẹ́ orí nínú APOR pé. Mo sì ti ṣàlàyé pé OR, tí ó jẹ́ ìpele akérépin ni arábìnrin àmúpé. Ọ̀rọ̀-Orúkọ (OR) orí àti àmúpé ni ó máa ń dà pọ̀ di $OR^{I}$ tí a ń pè ní ìpele abàárín. Àfikún ni arábìnrin fún ìpele abàárín, $OR^{I}$, ìpele abàárín $OR^{I}$ yóò dà pọ̀ mọ́ àfikún láti di ìpele abàárín mìíràn. Ìpele abàárín kejì yìí máa ń gba asọdọ̀tọ̀ gẹ́gẹ́ bi arábìnrin, àwọn méjèèjì yóò wá pa pọ̀ di ìpele agajù tí ṣe APOR tàbí $OR^{II}$. Àwọn àpẹẹrẹ díẹ̀ tí ó wà ní ìsàlẹ̀ yìí fi àlàyé wọ̀nyí hàn kedere.

6a. Akẹ́kọ̀ọ́ Yorùbá tẹ́ẹ́rẹ́ pupa tí mo rí gan-an
b. Mo lá [$_{APOR}$ àlá pé Délé á kọ́ ilé]

APOR (6a) àti *àlá pé Délé kọ́ ilé* ní (6b) ni ó jẹ wá lógún. ***Akẹ́kọ̀ọ́*** ni OR orí ní (6a), ***Yorùbá*** jẹ́ àmúpé fún orí nítorí pé ***Yorùbá*** ni ẹ̀kọ́ tí ***akẹ́kọ̀ọ́*** ń kọ́. Ṣùgbọ́n ***tẹ́ẹ́rẹ́, pupa*** àti ***tí mo rí*** jẹ́ àfikún. Ìdí ni pé àwọn mẹ́tẹ̀ẹ̀ta ń ṣe àfikún ìtumọ́ ***akẹ́kọ̀ọ́*** làsán ni, kìí ṣe pé wọn mú kí ìtumọ̀ rẹ̀ pé. Asọdọ̀tọ̀ tí ó wà nínú APOR (6a) ni ***gan-an.*** Ní (6b), ***àlá*** ni orí APOR náà, ***pé Délé á kọ́ ilé*** sì ni àmúpé. Àlàyé wọ̀nyí ni mo fi hàn nínú àwòrán atọ́ka-igi ìsàlẹ̀ wọ̀nyí.

7a


APOR
ORI
AF
ORI
APAM
ORI
AJ
AMI
ORI
AJ
AM
APAPR
OR
APOR
APOR
APRI
ORI
ORI
APR
APIṢ
OR
AROK
IṢI
IṢ
Akẹ́kọ̀ọ́ Yorùbá tẹ́ẹ́rẹ́ pupa tí mo ø rí gan-an

7b


APOR
ORI
OR
APAM
AMI
APAPR
AM
APOR
APRI
ORI
APR
APIṢ
OR
KO
IṢI
IṢ
APOR
ORI
OR
Àlá pé Délé á kọ́ ilé

**ÌGBÉLÉWỌ̀N AKẸ́KỌ̀Ọ̀**
Kọ àpẹẹrẹ àpólà orúkọ tí ó ní àpapọ̀ Àmúpè, Àfikún àti Asọdọ̀tọ̀.

### 4.2 Ìrísí APOR ní ibi tí Arọ́pò-Orúkọ Gígùn (AROG) ti jé orí

Nínú ìhun Àpólà Orúkọ ni ibi tí Arọ́pò-orúkọ gígún tí jẹ́ orí, irú arọ́pò-orúkọ gígùn bẹ́ẹ̀ lè gba ẹ̀yán gẹ́gẹ́ bí ti Ọ̀rọ̀-orúkọ. Àmọ́ sá, kì í ṣe gbogbo ẹ̀yán tí Ọ̀rọ̀-orúkọ tí ó jẹ́ orí gbà ni Arọ́pò-orúkọ gígún lè gbà. Arọ́pọ̀-orúkọ gígùn kò lè gba ẹ̀yán ajórúkọ, bákan náà ní ó dàbí ẹni pé kò lẹ̀ gba ẹ̀yán aṣàpèjúwe pẹ̀lú. Ìyàtọ̀ mìíràn ni pé ó dàbí ẹni pé ipó olùwà nìkan ni Arọ́pò-orúkọ gígùn ti lè jẹ yọ. Bí ó bá rí bẹ́ẹ̀, á jẹ́ pé àwọn ẹ̀yán tí Arọ́pò-orúkọ gúngún lè gbà ni ìwọ̀nyí. ẹ́yán aṣọ̀ǹkà (AK), ẹ́yán aṣàpọ́nlé (AP), ẹ́yán aṣàfihàn (AF) àti ẹ́yán awẹ́-gbólóhùn aṣàpèjúwe tí a ń pè ní àpólà aṣàmúpé (APAM)

Arọ́pò-orúkọ gígún (AROG) tí ó jẹ́ orí nínú Àpólà Orúkọ (APOR) lé gba ọ̀kan nínú àwọn ẹ̀yán tí ó wà lókè yìí tàbí kí ó gbà ju ọ̀kan lọ. Àmọ́ ṣá, Arọ́pò-orúkọ gígún (AROG) tí ó jẹ́ orí nínú Àpólà Orúkọ lè máà gba ẹ̀yán kọ̀ọ̀kan. Jẹ́ kí á yẹ àwọn àpẹẹrẹ wọ̀nyí wò.

8a. **Àwa** gbọ́ orin wọn.
b. **Òun náà** ti dé.
d. **Àwọn tí mo rí** ti jáde.
e. **Ẹ̀yin méjì yìí** gbọ́ ohun tí a sọ.

Nínú àwọn gbólóhùn àpẹẹrẹ tí ó wà ní (8), àwọn Àpólà Orúkọ ní ibi tí Arọ́pò-orúkọ gígún (AROG) ti jẹ́ orí ni ni a kọ ní àkọhàn, ìrísí ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn ni ó wà ní (9).

9a



b.


d.




e.




**ÌGBÉLÉWỌ̀N AKẸ́KỌ̀Ọ́**
Kọ àpẹẹrẹ àpólà orúkọ tí ó ní Arọ́pò-Orúkọ Gígùn (AROG) gẹ́gẹ́ bí orí.

### 4.3 Ìrísí APOR ní ibi ti AROK ti jẹ́ orí

Arọ́pò-orúkọ kúkúrú (AROK) lè jẹ orí nínú ìhun Àpólà Orúkọ. Ní ibi tí ó bá ti jẹ́ orí bẹ́ẹ̀, irú Àpólà Orúkọ bẹ́ẹ̀ kò sí ní ẹ̀yán, kìkìdá Arọ́pò-orúkọ kúkúrú (AROK) nìkan ni yóò wà nínú ìhun irú Àpólà Orúkọ bẹ́ẹ̀. Ìdí ni pé Arọ́pò-orúkọ kúkúrú (AROK) kìí gba ẹ̀yán tí ó bá jẹ́ orí nínú Àpólà Orúkọ. Bí àpẹẹrẹ:

10a. Mo rí wọn ní àná.
b. Ẹ kó o jọ fún wa.
d. Ayé fẹ́ gbọ́ yín.

Àwọn APOR tí ó jẹ́ kìkìdá AROG (Arọ́pò-orúkọ kúkúrú) nínú àwọn gbólóhùn àpẹẹrẹ (10) ni ìwọ̀nyí. ***Mo, wọn, ẹ, o, wa, yín***. Ìrísí kan náà ni àwọn Àpólà Orukọ wọ̀nyí ní. Ìrísí ọ̀hún ni mo yà sí ìsàlẹ̀ yìí ní àpẹẹrẹ (11).

11 APOR
|
OR[I]
|
AROK
|
Mo/wọn/Ẹ/o/wa/yín

**ÌGBÉLÉWỌ̀N AKẸ́KỌ̀Ọ́**
Kọ àpẹẹrẹ àpólà orúkọ tí ó ní Arọ́pò-orúkọ kúkúrú (AROK) gẹ́gẹ́ bí orí.

## 5.0 ÌSỌNÍṢÓKÍ

Ní ìpín yìí, mo ṣàlàye bí a ṣe lè fi Àmúpè, Àfikún àti Asọdọ̀tọ̀ nínú ìhun àpólà orúkọ nípa lílo àwòrán atọ́ka igi. Mo ṣàlàyé pé ọ̀rọ̀ orúkọ tí ó jẹ́ orí ó wà ní ìpele akérépin, tí òun àti àmúpé ni ó máa ń dà pọ̀ di OR[I] ní ìpele abàárín. Àfikún ni arábìnrin fún ìpele abàárín, OR[I], ìpele abàárín OR[I] yóò dà pọ̀ mọ́ àfikún láti di ìpele abàárín mìíràn. Ìpele abàárín kejì yìí máa ń gba asọdọ̀tọ̀ gẹ́gẹ́ bi arábìnrin, àwọn méjèèjì yóò wá pa pọ̀ di ìpele agajù tí ṣe APOR tàbí OR[II].

Mo tún ṣàlàyé pé ní ìgbà ti Arọ́pò-orúkọ gígún bá jẹ́ orí nínú ìhun Àpólà Orúkọ, irú arọ́pò-orúkọ gígùn bẹ́ẹ̀ lè gba ẹ̀yán gẹ́gẹ́ bí ti Ọ̀rọ̀-orúkọ. Àmọ́ ní ibi tí Arọ́pò-orúkọ kúkúrú (AROK) bá ti jẹ́ orí, irú Àpólà Orúkọ bẹ́ẹ̀ kìí sí ẹ̀yán, kìkìdá Arọ́pò-orúkọ kúkúrú (AROK) nìkan ni yóò wà nínú ìhun irú Àpólà Orúkọ bẹ́ẹ̀.

**Commented [O.J70]:** nínú irú

## 6.0 IṢẸ́ ṢÍṢE

Lo àwòrán atọ́ka igi láti fi ìhun àwọn àpólà orúkọ yìí hàn.

- Olùkọ́ Yorùbá gíga náà
- Ajá dúdú yìí

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ/ÀWỌN ÌWÉ FÙN KÍKÀ


Awóbùlúyì, O. 1978. *Essentials of Yorùbá Grammar,* Ìbàdàn: UPL.
Awobuluyi, O. 1988. *Èdè Ìperí Yorùbá*: *Apá kejí*, Lagos: NERDC
Awóbùlúyì, O. 2001a. "Arọ́pò–Orúkọ Kúkúrú Ẹni–Kẹ́ta Ẹyọ Aṣolùwà" *Yorùbá,* Vol. 2, No. 1 pp 1-8
Awóbùlúyì, O. 2001b. "Òte–Ìlò Àwọn Arọ́pò–Orúkọ Kúkúrú" Bébà tí a kà ní Àpérò Ẹgbẹ́ Onímọ̀ ÈdèYorùbá: Yunifásítì ìlú Eko.
Awobuluyi, O. 2008. *Ẹ̀kọ́ Íṣẹ̀dá-Ọ̀rọ̀ Yorùbá*, Akurẹ: Montem Paperbacks
Awobuluyi, O. 2013. *Ẹ̀kọ́ Gírámà Èdè Yorùbá*, Oshogbo: Montem Paperbacks
Bámgbóṣé, Ạ. 1967. *A Short Yorùbá Grammar*, Ìbàdàn: HEB.
Bámgbóṣé, Ạ. 1990. *Fonọ́lọ́jì àti Gírámà Yorùbá.* Ìbàdàn: UPL.
Oyetade, S.O. 1995. *Yorùbá Grammar I.* Ibadan, Centre for External Studies, UI.
Táíwò, O. 2003. Tense and Aspect in Ào. Nínú Ndimele O.M (olótùú) *Languages and Linguistics in Nigeria.* A Festscrist in Honour of Kay williamson.
Taiwo, O. 2007. Short Subject Pronoun in the Ào dialect of Yorùbá. *JOLAN: Journal of Linguistic Association of Nigeria (JOLAN)* No 10 o.i. 67 – 86
Taiwo, O. 2008a. *Basic Concepts in Grammar*: Ibadan, DLC, UI
Taiwo, O. 2008b. *Basic Grammar*: Ibadan, DLC, UI

## MÓDÙ 3: Ẹ̀PỌ́N AṢÀFIKÚN NÍNÚ ÌHUN ÀPÓLÀ ÌṢE (APIṢ)

Èròǹgbà módù yìí ni láti ṣàlàyé ìhun àpólà ìṣe. Ohun tí a ó sì máa tẹnpẹlẹ ní abala yìí ni ẹ̀pọ́n aṣàfikún inú àpólà ìṣe. Pàtàkì ni àpólà ìṣe jẹ́ nínú gbólóhùn aṣeégbà. Ọ̀nà méjì gbòòrò ni a lè pín ìhun àpólà ìṣe sí. Àwọn ni orí àti ẹ̀pọ́n. Kò yẹ kí ó ṣàjòjì sí ọ mọ́ pé ọ̀rọ̀-ìṣe ni orí nínú àpólà ìṣe. Kàǹpá sì ni ọ̀rọ̀-ìṣe nínú àpólà ìṣe. Èyí túmọ̀ sí pé ọ̀rọ̀ ìṣe nìkan lè dá wà nínú àpólà ìṣe. Ìgbà mìíràn, ó sì tún lè gba àwọn àpólà mìíràn mọ́ra nínú àpóla ìṣe láti pọn on lé. Àwọn àpóla mìíràn tí ó máa ń jẹ́yọ nínú àpólà ìṣe láti pọn ọ̀rọ̀-ìṣe lé ni àpólà àmúpé, tí ọ̀rọ̀ àmúpé ti jẹ́ orí, àti àpólà aṣàfikún, ti ọ̀rọ̀ aṣàfikún ti jẹ́ orí. Ẹ̀pọ́n ni ọ̀rọ̀ tàbí àkójọ ọ̀rọ̀ tí a lò nínú ìhun àpólà ìṣe láti fi kún ìtumọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí tàbí láti mú kí ìtumọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe pé.

Ẹ̀pọ́n aṣàfikún jẹ́ ọ̀rọ̀ tàbí àkójọ ọ̀rọ̀ tí ó ń ṣàlàyé nípa ìtumọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe tí ó ń pọ́n nínú àpólà ìṣe. Oríṣi ẹ̀pọ́n aṣàfikún tó wà nínú ìhun àpólà ìṣe ni ẹ̀pọ́n aṣàfikún aṣáájú ọ̀rọ̀-íṣe àti ẹ̀pọ́n aṣàfikún atẹ̀lé ọ̀rọ̀-íṣe. Ní ọ̀nà mìíràn ẹ̀wẹ̀, ẹ̀pọ́n aṣàfikún tún lè jé alábọ̀ àti aláìlàbọ̀.

Ní mòdú yìí, mà á kọ́ ọ nípa ìhun àpólà ìṣe, pàápàá jùlọ ẹ̀pọ́n aṣàfikún nínú ìhun àpólà ìṣe. Wà á lè mọ oríṣirí ẹ̀pọ́n aṣàfikún tí ó wà nínú ìhun àpólà ìṣe oríkì rẹ̀ Àwọn àkòrí wọ̀nyí ni o máa kà ní módù yìí:

- Ìpín 1: Ìhun Àpólà Ìṣe
- Ìpín 2: Àpólà Aṣẹ̀pọ́n (APEP) Aláìlàbọ̀ gẹ́gẹ́ bí Ẹ̀pọ́n Aṣàfikún Aṣáájú Ọ̀rọ̀-Íṣe
- Ìpín 3: Àpólà Aṣẹ̀pọ́n (APEP) gẹ́gẹ́ bí Ẹ̀pọ́n Aṣàfikún Aṣáájú Ọ̀rọ̀-Ìṣe
- Ìpín 4: Ẹ̀pọ́n Aṣàfikún Atẹ̀lé Ọ̀rọ̀-Íṣe

## ÌPÍN 1: ÌHUN ÀPÓLÀ ÌṢE

**1.0** Ìfáàrà
**2.0** Èròǹgbà àti Àfojúsùn
**3.0** Ìbéèrè Ìṣáájú
**4.0** Àkóónú Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
  **4.1** Ìhun àpólà ìṣe
  **4.2** Ẹ̀pọ́n nínú Ìhun Àpólà Ìṣe
  **4.3** Ẹ̀pọ́n Aṣàfikún nínú Ìhun Àpólà Ìṣe
**5.0** Ìsọníṣókí
**6.0** Iṣẹ́ Ṣìṣe
**7.0** Ìwé Ìtọ́kasí/Àwọn Ìwé Fùn Kíkà

### 1.0 ÌFÁÁRÀ

Pàtàkì ni àpólà ìṣe jẹ́ nínú gbólóhùn aṣeégbà. Kànńpá ni ọ̀rọ̀-ìṣe jẹ́ nínú àpóla ìṣe. Yàtọ̀ sí ọ̀rọ̀-ìṣe orí nínú àpólà ìṣe yìí, ẹ̀pọ́n náà tún lè jẹyọ pọ̀ pẹ̀lú ọ̀rọ̀ ìṣe. Ní ìpín yìí, mà á máa ṣàlàyé Ìhun àpólà ìṣe lẹṣẹẹsẹ, ní ibi tí ọ̀rọ̀-ìṣe nìkan ti jẹyọ àti ibi tí ọ̀rọ̀-ìṣe ti jẹyọ pẹ̀lú ẹ̀pọ́n.

### 2.0 ÈRÒǸGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN

Lẹ́yìn tí ó bá ti ka ìpín yìí, wà á lè mọ oríkì àpólà ìṣe, wà á sì tún mọ oríṣirísi àwọn ẹ̀pọ́n tí wọ́n le jẹyọ nínú àpólà ìṣe.

### 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢÁÁJÚ

Irú àwọn ẹ̀pọ́n wo ni wọ́n máa ń jẹyọ pẹ̀lú ọ̀rọ̀-ìṣe nínú àpólà ìṣe.

### 4.0 ÀKÓÓNÚ ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

### 4.1 Ìhun àpólà ìṣe

Táíwò (2018b) ki àpólà ìṣe gẹ́gẹ́ bí ***ẹyọ ọ̀rọ̀ tàbí àsópọ̀ ọ̀rọ̀ tí ọ̀rọ̀-ìṣe jẹ́ orí rẹ̀ tí a sì a lè lò gẹ́gẹ́ bí kókó gbólóhùn nínú gbólóhùn aṣeégbà***. Oríkì yìí fi hàn pé ọ̀rọ̀-ìṣe kan ni o máa ń wà ní àpólà ìṣe. Bí a bá rí àpólà ìṣe tí ó ní ju ọ̀rọ̀-ìṣe kan lọ, irú àpólà ìṣe bẹ́ẹ̀ kìí ṣe àpólà ìṣe ẹyọ kan rárá, ó ti ju àpólà ìṣe kan. Èyí fi hàn pé iye ọ̀rọ̀-ìṣe tí ó bá wà nínú ìhun àpólà ìṣe ni a fi máa mọ iye àpólà ìṣe ti a ń sọ nípa rẹ̀.

Ọ̀nà méjì gbòòrò ni a lè pín ìhun àpólà ìṣe sí. Àwọn ni orí àti **ẹ̀pọ́n**. Ọ̀rọ̀-ìṣe ni orí nínú ìhun àpólà ìṣe, oríṣirísi ìsọ̀rí-ọ̀rọ̀ ni ó sì lè jẹ́ ẹ̀pọ́n. Ọ̀rọ̀-Ìṣe (IṢ) lè dá wà láì gba ẹ̀pọ́n nínú APIṢ gẹ́gẹ́ bí ó ṣe wà ní (1a) àti ìrísí rẹ̀ ní (1b).

1a. Ọmọ náà ti **[APIṢ kú]**.

b




Ní (1a), IṢ ***kú*** nìkan ni ó wà nínú ìhun APIṢ, gẹ́gẹ́ bí mo ṣe fi hàn ní àwòrán atọ́ka-igi (1b), IṢ, ***kú,*** ni ìpele akérépin, kò ní arábìnrin tí ó yẹ kí ó jẹ́ àmúpé, nítorí pé ọ̀rọ̀-ìṣe aláìgbabọ̀ ni. Òun nìkan náà ni ó di ìpele abàárín, ìpele abàárín yìí náà kò ní asọdọ̀tọ̀, òun nìkan ni ó tún di ìpele agajù pẹ̀lú.

**ÌGBÉLÉWỌ̀N AKẸ́KỌ̀Ọ́**
Ki oríki apólà ìṣe

### 4.2 Ẹ̀pọ́n nínú Ìhun Àpólà Ìṣe

**Oríkì Ẹ̀pọ́n**

A lè ki ẹ̀pọ́n gẹ́gẹ́ bí *ọ̀rọ̀ tàbí àkójọ ọ̀rọ̀ tí a lò nínú ìhun àpólà ìṣe láti fi kún ìtumọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí tàbí láti mú kí ìtumọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí pé.* Oríkì yìí fi hàn pé a máa ń lo àwọn ẹ̀pọ́n kan láti mú kí ìtumọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí pé, láìsí irú àwọn ẹ̀pọ́n bẹ́ẹ̀ nínú ìhun àpólà ìṣe, ìtumọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí kò ní pé, irú gbólóhùn tàbí ìsọ bẹ́ẹ̀ kò ní ṣe é gbà tàbí kí ìtumọ̀ rẹ̀ yàtọ̀ sí ohun tí a ní lọ́kàn. A sì máa ń lo àwọn ẹ̀pọ́n kan láti ṣe àfikún sí ìtumọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí nínú ìhun àpólà ìṣe. Bí a lo irú àwọn ẹ̀pọ́n yìí tàbí a kò lò wọ́n nínú ìhun àpólà ìṣe kò lé yí ìtumọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí padà, bẹ́ẹ̀ sì ni kò lè sọ gbólóhùn náà di àìṣeégbà.
Ìhun àpólà ìṣe ni mo fi hàn ní àtẹ ìsàlẹ̀ yìí.




**ÌGBÉLÉWỌ̀N AKẸ́KỌ̀Ọ́**
Ki oríki ẹ̀pọ́n

### 4.3 Ẹ̀pọ́n Aṣàfikún nínú Ìhun Àpólà Ìṣe

Ẹ̀pọ́n aṣàfikún jẹ́ ọ̀rọ̀ tàbí àkójọ ọ̀rọ̀ tí ó ń ṣàlàyé nípa ìtumọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe tí ó ń pọ́n nínú àpólà ìṣe. Irú àlàyé yìí ni láti sọ ìwọ̀nba ìtumọ̀ tí a gbọ́dọ̀ fún ọ̀rọ̀-ìṣe tí àfikún ń pọ́n. Oríṣi ẹ̀pọ́n aṣàfikún méjì ni óo wà nínú ìhun àpólà ìṣe. Àwọn ni **ẹ̀pọ́n aṣàfikún aṣáájú ọ̀rọ̀-íṣe** àti **ẹ̀pọ́n aṣàfikún atẹ̀lé ọ̀rọ̀-íṣe.**

**ÌGBÉLÉWỌ̀N AKẸ́KỌ̀Ọ́**
Ṣàlàyé ẹ̀pọ́n aṣàfikún nínú ìhun àpólà ìṣe

## 5.0 ÌSỌNÍṢÓKÍ

Pàtàkì ni àpólà ìṣe jẹ́ nínú gbólóhùn aṣeégbà. Kànńpá ni ọ̀rọ̀-ìṣe jẹ́ nínú àpóla ìṣe. Ẹ̀pọ́n náà tún le jẹyọ pẹ̀lú ọ̀rọ̀-ìṣe nínú àpóla ìṣe, èyí sì le jé ẹ̀pọ́n aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe tàbí ẹ̀pọ́n atẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe. Ọ̀rọ̀-ìṣe kan ni ó máa ń jẹyọ nínú àpólà ìṣe. Nínú gbólóhùn ọlọ́pọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe, àpólà ìṣe ti ó wà níbẹ̀ ju ẹyọkan lọ. Iye ọ̀rọ̀-ìṣe tí ó bá wà nínú ẹ̀hun gbólóhùn ni yó sọ iye àpólà ìṣe ti ó wà níbẹ̀.

## 6.0 IṢẸ́ ṢÍṢE

Ọ̀nà méjì gbòòrò wo ni a le pín ẹ̀pọ́n inú ìhun àpólà ìṣe sí?



Commented [O.J71]: ọ̀rọ̀-àpọ́nlé

**7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ/ÀWỌN ÌWÉ FÙN KÍKÀ**

Awóbùlúyì, O. 1978. *Essentials of Yorùbá Grammar,* Ìbàdàn: UPL.

Awobuluyi, O. 1988. *Èdè Ìperí Yorùbá*: *Apá kejí*, Lagos: NERDC

Awóbùlúyì, O. 2001a. "Arọ́pò–Orúkọ Kúkúrú Ẹni–Kẹ́ta Ẹyọ Aṣolùwà" *Yorùbá,* Vol. 2, No. 1 pp 1-8

Awóbùlúyì, O. 2001b. "Òte–Ìlò Àwọn Arọ́pò–Orúkọ Kúkúrú" Bébà tí a kà ní Àpérò Ẹgbẹ́ Onímọ̀ ÈdèYorùbá: Yunifásítì ìlú Eko.

Awobuluyi, O. 2008. *Ẹ̀kọ́ Íṣẹ̀dá-Ọ̀rọ̀ Yorùbá*, Akurẹ: Montem Paperbacks

Awobuluyi, O. 2013. *Ẹ̀kọ́ Gírámà Èdè Yorùbá*, Oshogbo: Montem Paperbacks

Bámgbóṣé, Ạ. 1967. *A Short Yorùbá Grammar*, Ìbàdàn: HEB.

Bámgbóṣé, Ạ. 1990. *Fonọ́lọ́jì àti Gírámà Yorùbá.* Ìbàdàn: UPL.

Oyetade, S.O. 1995. *Yorùbá Grammar I.* Ibadan, Centre for External Studies, UI.

Táíwò, O. 2003. Tense and Aspect in Ào. Nínú Ndimele O.M (olótùú) *Languages and Linguistics in Nigeria.* A Festscrist in Honour of Kay williamson.

Taiwo, O. 2007. Short Subject Pronoun in the Ào dialect of Yorùbá. *JOLAN: Journal of Linguistic Association of Nigeria (JOLAN)* No 10 o.i. 67 – 86

Taiwo, O. 2008a. *Basic Concepts in Grammar*: Ibadan, DLC, UI

Taiwo, O. 2008b. *Basic Grammar*: Ibadan, DLC, UI

**ÌPÍN 2: ÀPÓLÀ AṢẸ̀PỌ́N (APEP) ALÁÌLÀBỌ̀ GẸ́GẸ́ BÍ Ẹ̀PỌ́N AṢÀFIKÚN AṢÁÁJÚ Ọ̀RỌ̀-ÍṢE**

Commented [O.J72]: àpólà ọ̀rọ̀-àpọ́nlé


**1.0** Ìfáárà
**2.0** Èròǹgbà àti Àfojúsùn
**3.0** Ìbéèrè Ìṣáájú
**4.0** Àkóónú Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
**4.1** Àpólà aṣẹ̀pọ́n (APEP) aláìlàbọ̀ aṣáájú ọ̀rọ̀-íṣe
**5.0** Ìsọníṣókí
**6.0** Iṣẹ́ Ṣíṣe
**7.0** Ìwé Ìtọ́kasí/Àwọn Ìwé Fún Kíkà


Commented [O.J73]: Ṣé aláìní àbọ̀ ni àbí aláìlo àbọ̀?

**1.0 ÌFÁÁRÀ**

Yàtọ̀ sí ẹ̀pọ́n àṣàmúpé, ẹ̀pọ́n aṣàfikún náà tún lè jẹyọ nínú àpólà ìṣe. Àmọ́, bí ó ṣe jẹ́ pé ẹ̀pọ́n àṣàmúpé máa ń jẹyọ tẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe, ẹ̀pọ́n aṣàfikún le jẹyọ ṣaájú tàbí tẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe nínú àpólà ìṣe. Ní ìpín yìí, mà á máa ṣàlàyé àpólà aṣẹ̀pọ́n (APEP) aláìlàbọ̀ gẹ́gẹ́ bí ẹ̀pọ́n aṣàfikún aṣáájú ọ̀rọ̀-íṣe.

Commented [O.J74]: aṣamúpé

**2.0 ÈRÒŃGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN**

Lẹ́yìn tí ó bá ti ka ìpín yìí tán, wà á lè dá àpólà aṣẹ̀pọ́n (APEP) aláìlàbọ̀ aṣáájú ọ̀rọ̀-íṣe mọ, wà á sì le fi hàn nínú àwòrán atọ́ka igi.

Commented [O.J75]: mọ̀

**3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢÁÁJÚ**

Kọ àpẹẹrẹ àpólà ìṣe tí ó ni ìhun àpólà aṣẹ̀pọ́n (APEP) aláìlàbọ̀ aṣáájú ọ̀rọ̀-íṣe, kí o sì fi hàn nínú àwòrán atọ́ka igi.

**4.0 ÀKÓÓNÚ ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́**

**4.1 ÀPÓLÀ AṢẸ̀PỌ́N (APEP) ALÁÌLÀBỌ̀ AṢÁÁJÚ Ọ̀RỌ̀-ÍṢE**

Ẹ̀pọ́n aṣàfikún aṣáájú ọrọ̀-ìṣe ni àwọn aṣàfikún tí ó máa ń jẹ yọ ṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí nínú àpólà ìṣe. Ó ṣe é ṣe kí ẹ̀pọ́n aṣàfikún ju ẹyọ kan lọ. Àpẹẹrẹ bí àwọn ẹ̀pọ́n aṣàfikún aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe ṣe jẹ yọ ṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe nínú àpólà ìṣe ní wọ́n wà ní ìsàlẹ̀ yìí. Àpólà Aṣẹ̀pọ́n (APEP) aláìlàbọ̀ sì ni àwọn ẹ̀pọ́n aṣàfikún náà.

2a O [***jẹ́*** ra iṣu yẹn]
b Ọmọ náà [***ṣe*** sọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀].
d Mo [***lè*** jẹ iṣu di ọ̀la].

3a Wọ́n [***pàpà tún*** pariwo sí i].
b O [***gbọ́dọ̀ tètè*** parí iṣẹ́ yẹn].
d Mo [***kàn dédé*** gbọ́ ariwo wọn]

4a Wọ́n [***mà lè tètè*** wáà].
b Kò [***tiẹ̀ lè nìkan*** gbé ẹrù yẹn].
d Ẹ [***ṣáà kàn dédé*** dákẹ́].

Àpólà ìṣe (APIṢ) ni wọ́n wà ní àkámọ́ onígun [ ] ní àwọn àpẹẹrẹ òkè wọ̀nyí.

Nínú APIṢ wọ̀nyí, APEP tí wọ́n jẹ́ ẹ̀pọ́n aṣàfikún aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí ni mo kọ ní àkọhàn-adẹ̀gbẹ́. Ní àpẹẹrẹ (2), ẹyọ kan ni ẹ̀pọ́n aṣàfikún aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe, ní àpẹẹrẹ (3), wọ́n jẹ́ méjì, wọ́n sì jẹ́ mẹ́ta ní àpẹẹrẹ (4) Ìrísí ọ̀kọ̀ọ̀kan ní àpẹẹrẹ (2) sí (4) ni mo fi hàn ní àwọn àwòrán atọ́ka-igi ìsàlẹ̀ wọ̀nyí.

5a




b.




d.




Àwọn wúnrẹ̀n kan wà tí a lè pè ní ọ̀rọ̀-ìṣe bí wọ́n bá dá wà, ìyẹn láìjẹ́ pé a lò wọ́n nínú ẹ̀hun, ṣùgbọ́n a máa ń lo irú àwọn wúnrẹ̀n bẹ́ẹ̀ láti pọ́n ọ̀rọ̀-ìṣe nínú ìhun àpólà ìṣe. Àpẹẹrẹ wọn ni ó wà nínú gbólóhùn ìsàlẹ̀ wọ̀nyí, àwọn ni mo sì kọ ní àkọhàn-adẹ̀gbẹ́.

5a. Ọmọ náà [***sáré*** dàgbà]
b. Ọbẹ̀ náà [***dùn*** tó]
d. Ó [***yára*** gun igi]

Commented [O.J76]: Ṣé kì í ṣe dùn gan-an ni ọ̀rọ̀-ìṣe nibi ti **tó** sì jẹ́ ẹ̀pọ́n fun?

Ìrísí kan náà ni àwọn APIṢ tí wọ́n wà nínú àkámọ́ onígun **[ ]** ní àpẹẹrẹ (5a àti b) ní òkè wọ̀nyí ní. Ìrísí náà ni mo fi hàn ní àwòrán atọ́ka-igi (6a). Mo sì fi ìrísí APIṢ tí ó wà nínú àkámọ́ onígun **[ ]** ní (5d) hàn ni àwòrán atọ́ka-igi (6b) ní ìsàlẹ̀ yìí.

6a



b.



**ÌGBÉLÉWỌ̀N AKẸ́KỌ̀Ọ́**
Ṣàlàyé àpólà aṣẹ̀pọ́n (APEP) aláìlàbọ̀ aṣáájú ọ̀rọ̀-íṣe.

## 5.0 ÌSỌNÍṢÓKÍ
Àpólà Aṣẹ̀pọ́n (APEP) aláìlàbọ̀ ti o lè jẹ yọ ṣaájú ọ̀rọ̀-ìṣe ṣe é ṣe kí ó ju ẹyọ kan lọ. Iṣẹ́ tí wọ́n sì ń ṣe ni pé, ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn ń fi kún ìtumọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe ni. A tún máa ń lo àwọn wúnrẹ̀n kan tí a lè pè ní ọ̀rọ̀-ìṣe bí wọ́n bá dá wà, láti pọ́n ọ̀rọ̀-ìṣe nínú ìhun àpólà ìṣe. Ní irúfẹ́ gbólóhùn tí a bá ti lo irú àwọn wúnrẹn báwọ̀nyìí láti pọ́n ọ̀rọ̀-ìse mìíràn lé, o jású pé àpólà aṣẹ̀pọ́n ni irúfẹ́ wúnrẹ̀n bẹ́ẹ̀.

## 6.0 IṢẸ́ ṢÍṢE
Kọ àpẹẹrẹ àpólà ìṣe márùn-ún tí ó ni ìhun àpólà aṣẹ̀pọ́n (APEP) aláìlàbọ̀ aṣáájú ọ̀rọ̀-íṣe, kí o sì fi hàn nínú àwòrán atọ́ka igi.

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ/ÀWỌN ÌWÉ FÙN KÍKÀ
Awóbùlúyì, O. 1978. *Essentials of Yorùbá Grammar*, Ìbàdàn: UPL.
Awobuluyi, O. 1988. *Èdè Ìperí Yorùbá*: *Apá kejí*, Lagos: NERDC

Awóbùlúyì, O. 2001a. “Arọ́pò–Orúkọ Kúkúrú Ẹni–Kẹ́ta Ẹyọ Aṣolùwà” *Yorùbá,* Vol. 2, No. 1 pp 1-8
Awóbùlúyì, O. 2001b. “Òte–Ìlò Àwọn Arọ́pò–Orúkọ Kúkúrú” Bébà tí a kà ní Àpérò Ẹgbẹ́ Onímọ̀ ÈdèYorùbá: Yunifásítì ìlú Eko.
Awobuluyi, O. 2008. *Ẹ̀kọ́ Íṣẹ̀dá-Ọ̀rọ̀ Yorùbá,* Akurẹ: Montem Paperbacks
Awobuluyi, O. 2013. *Ẹ̀kọ́ Gírámà Èdè Yorùbá,* Oshogbo: Montem Paperbacks
Bámgbóṣé, Ạ. 1967. *A Short Yorùbá Grammar,* Ìbàdàn: HEB.
Bámgbóṣé, Ạ. 1990. *Fonọ́lọ́jì àti Gírámà Yorùbá*. Ìbàdàn: UPL.
Oyetade, S.O. 1995. *Yorùbá Grammar I*. Ibadan, Centre for External Studies, UI.
Táíwò, O. 2003. Tense and Aspect in Ào. Nínú Ndimele O.M (olótùú) *Languages and Linguistics in Nigeria.* A Festscrist in Honour of Kay williamson.
Taiwo, O. 2007. Short Subject Pronoun in the Ào dialect of Yorùbá. *JOLAN: Journal of Linguistic Association of Nigeria (JOLAN)* No 10 o.i. 67 – 86
Taiwo, O. 2008a. *Basic Concepts in Grammar*: Ibadan, DLC, UI
Taiwo, O. 2008b. *Basic Grammar*: Ibadan, DLC, UI

## ÌPÍN 3: ÀPÓLÀ AṢẸ̀PỌ́N (APEP) GẸ́GẸ́ BÍ Ẹ̀PỌ́N AṢÀFIKÚN AṢÁÁJÚ Ọ̀RỌ̀-ÌṢE


**1.0** Ìfáárà
**2.0** Èròǹgbà àti Àfojúsùn
**3.0** Ìbéèrè Ìṣáájú
**4.0** Àkóónú Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
**4.1** Àpólà aṣẹ̀pọ́n (APEP) alàbọ̀ gẹ́gẹ́ bí ẹ̀pọ́n aṣàfikún aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe
**4.2** Àpapọ̀ àpólà aṣẹ̀pọ́n (APEP) aláìlàbọ̀ àti alàbọ̀ gẹ́gẹ́ bí ẹ̀pọ́n aṣàfikún aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe
**5.0** Ìsọníṣókí
**6.0** Iṣẹ́ Ṣíṣe
**7.0** Ìwé Ìtọ́kasí/Àwọn Ìwé Fùn Kíkà


### 1.0 ÌFÁÁRÀ

Ní ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tó kọjá, mo ṣàlàyé àpólà aṣẹ̀pọ́n (APEP) aláìlàbọ̀ gẹ́gẹ́ bí ẹ̀pọ́n aṣàfikún aṣáájú ọ̀rọ̀-íṣe, ní ibi tí ẹ̀yọ ọ̀rọ̀ kan ti dúró gẹ́gẹ́ bíi àpolà. Ní ìgbà míràn, àpólà aṣẹ̀pọ́n (APEP) lè jẹ́ àpapọ̀ orí àti àbọ̀ rẹ̀. Èyí ni a pè ni àpólà aṣẹ̀pọ́n (APEP) alàbọ̀. Ní ìpín yìí, mà á máa ṣàlàyé àpólà aṣẹ̀pọ́n (APEP) alábọ̀ gẹ́gẹ́ bí ẹ̀pọ́n aṣàfikún aṣáájú ọ̀rọ̀-íṣe. Mà á tún ṣàlàyé ìrísí àpólà ìṣe tí ó ní àpapọ̀ àpólà aṣẹ̀pọ́n (APEP) aláìlàbọ̀ àti alàbọ̀ gẹ́gẹ́ bí ẹ̀pọ́n aṣàfikún aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe.

Commented [O.J77]: alábọ̀ tàbí agbàbọ̀ ńkọ́?

### 2.0 ÈRÒǸGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN

Lẹ́yìn tí ó bá ti ka ìpín yìí tán, wà á lè dá àpólà aṣẹ̀pọ́n (APEP) alàbọ̀ aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe mọ, wà á sì le fi hàn nínú àwòrán atọ́ka igi.

### 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢÁÁJÚ

Kọ àpẹẹrẹ àpólà ìṣe tí ó ni ìhun àpólà aṣẹ̀pọ́n (APEP) alábọ̀ aṣáájú ọ̀rọ̀-íṣe, kí o sì fi hàn nínú àwòrán atọ́ka igi.

### 4.0 ÀKÓÓNÚ ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

#### 4.1 Àpólà Aṣẹ̀pọ́n (APEP) Alàbọ̀ gẹ́gẹ́ bí Ẹ̀pọ́n Aṣàfikún Aṣáájú Ọ̀rọ̀-Ìṣe

Àwọn Àpólà Aṣẹ̀pọ́n (APEP) alábọ̀ tí a máa ń lò bí àfikún aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe nínú ìhun àpólà ìṣe ni mo kọ ní àkọhàn-adẹ̀gbẹ́ ní ìsàlẹ̀ yìí.

7a. Mo [***ti Ìbàdàn*** lọ sí Ìjàyè].
b. Ó [***fi ẹnu*** wa ọkọ̀].
d. Olú [***bá ọmọ náà*** ra aṣọ yìí ní ọjà].

Nínú àwọn APIṢ tí wọ́n wà nínú àkámọ́ onígun **[ ]** lókè, APEP tí wọ́n jẹ́ ẹ̀pọ́n aṣàfikún aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí ni mo kọ ní àkọhàn-adẹ̀gbẹ́. Ìrísí ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn ni mo fi hàn ní àwọn àwòrán atọ́ka-igi ìsàlẹ̀ wọ̀nyí.

8a




b.




d.




**ÌGBÉLÉWỌ̀N AKẸ́KỌ̀Ọ́**

Kọ àpẹẹrẹ àpólà aṣẹ̀pọ́n (APEP) alàbọ̀ gẹ́gẹ́ bí ẹ̀pọ́n aṣàfikún aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe.

## 4.2 Àpapọ̀ Àpólà Aṣẹ̀pọ́n (APEP) Aláìlàbọ̀ àti Alàbọ̀ gẹ́gẹ́ bí Ẹ̀pọ́n Aṣàfikún Aṣáájú Ọ̀rọ̀-Ìṣe

Ó ṣe é ṣe kí àpólà aṣẹ̀pọ́n aláìlàbọ̀ àti alábọ̀ jẹ̀ ẹ̀pọ́n aṣàfikún aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe nínú ìhun àpólà ìṣe. Bí ìjẹyọpọ̀ báyìí bá wáyé, ó dàbí ẹni pé àpólà aṣẹ̀pọ́n aláìlàbọ̀ ni ó kọ́kọ́ máa jẹ yọ nínú ìhun àpólà ìṣe gẹ́gẹ́ bí ẹ̀pọ́n aṣàfikún aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe kí àpólà aṣẹ̀pọ́n alàbọ̀ tó tẹ̀lé e. Àpẹẹrẹ ìjẹyọpọ̀ àwọn ẹ̀pọ́n aṣàfikún aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe méjèèjì nínú ìhun àpólà ìṣe ni mo fi hàn nínú àwọn gbólóhùn ìsàlẹ̀ wọ̀nyí.

9a. Olú [APIṢ[$_{\text{APEP}}$ ***kúkú***] [$_{\text{APEP}}$ ***lè***] ***[***$_{\text{APEP}}$ ***bá ọmọ náà]*** ra aṣọ ní ọjà].
b. Ó [APIṢ [$_{\text{APEP}}$ ***kàn***] [$_{\text{APEP}}$ ***dèdè] [***$_{\text{APEP}}$ ***fi ẹnu]*** wa ọkọ̀].

Ìrísí APIṢ tí ó wà ní (9a) ni mo fi hàn ní (10) ní ìsàlẹ̀ yìí gẹ́gẹ́ bí àwọn ẹ̀pọ́n méjèèjì ṣe jẹ yọ tẹ̀lé ara wọn.

10




## ÌGBÉLÉWỌ̀N AKẸ́KỌ̀Ọ́

Gbìyànjú kí o fi ìhun àpólà ìṣe ìsàlẹ̀ yìí hàn ni àwòrán atọ́ka igi.

Kàn kúkú fi ẹnu wa ọkọ

## 5.0 ÌSỌNÍṢÓKÍ

Àpólà aṣẹ̀pọ́n (APEP) lè jẹ́ àpapọ̀ orí àti àbọ̀ rẹ̀. Èyí ni a pè ni àpólà aṣẹ̀pọ́n (APEP) alàbọ̀. Ní ìpín yìí, mo ṣàlàyé àpólà aṣẹ̀pọ́n (APEP) alábọ̀ gẹ́gẹ́ bí ẹ̀pọ́n aṣàfikún aṣáájú ọ̀rọ̀-íṣe. Mo tún ṣàlàyé ìrísí àpólà ìṣe tí ó ní àpapọ̀ àpólà aṣẹ̀pọ́n (APEP) aláìlàbọ̀ àti alàbọ̀ gẹ́gẹ́ bí ẹ̀pọ́n aṣàfikún aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe.

## 6.0 IṢẸ́ ṢÌṢE

Kọ àpẹẹrẹ àpólà ìṣe márùn-ún tí ó ni ìhun àpólà aṣẹ̀pọ́n (APEP) alábọ̀ aṣáájú ọ̀rọ̀-íṣe, kí o sì fi hàn nínú àwòrán atọ́ka igi.

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ/ÀWỌN ÌWÉ FÙN KÍKÀ

Awóbùlúyì, O. 1978. *Essentials of Yorùbá Grammar*, Ìbàdàn: UPL.
Awobuluyi, O. 1988. *Èdè Ìperí Yorùbá*: *Apá kejí*, Lagos: NERDC
Awóbùlúyì, O. 2001a. “Arọ́pò–Orúkọ Kúkúrú Ẹni–Kẹ́ta Ẹyọ Aṣolùwà” *Yorùbá*, Vol. 2, No. 1 pp 1-8

Awóbùlúyì, O. 2001b. “Òte–Ìlò Àwọn Arọ́pò–Orúkọ Kúkúrú” Bébà tí a kà ní Àpérò Ẹgbẹ́ Onímọ̀ ÈdèYorùbá: Yunifásítì ìlú Eko.
Awobuluyi, O. 2008. *Ẹ̀kọ́ Íṣẹ̀dá-Ọ̀rọ̀ Yorùbá*, Akurẹ: Montem Paperbacks
Awobuluyi, O. 2013. *Ẹ̀kọ́ Gírámà Èdè Yorùbá*, Oshogbo: Montem Paperbacks
Bámgbóṣé, Ạ. 1967. *A Short Yorùbá Grammar,* Ìbàdàn: HEB.
Bámgbóṣé, Ạ. 1990. *Fonọ́lọ́jì àti Gírámà Yorùbá*. Ìbàdàn: UPL.
Oyetade, S.O. 1995. *Yorùbá Grammar I*. Ibadan, Centre for External Studies, UI.
Táíwò, O. 2003. Tense and Aspect in Ào. Nínú Ndimele O.M (olótùú) *Languages and Linguistics in Nigeria.* A Festscrist in Honour of Kay williamson.
Taiwo, O. 2007. Short Subject Pronoun in the Ào dialect of Yorùbá. *JOLAN: Journal of Linguistic Association of Nigeria (JOLAN)* No 10 o.i. 67 – 86
Taiwo, O. 2008a. *Basic Concepts in Grammar*: Ibadan, DLC, UI
Taiwo, O. 2008b. *Basic Grammar*: Ibadan, DLC, UI

## ÌPÍN 4: ẸPỌ́N AṢÀFIKÚN ATẸ̀LÉ Ọ̀RỌ̀-ÍṢE

**1.0** Ìfáárà
**2.0** Èròǹgbà àti Àfojúsùn
**3.0** Ìbéèrè Ìṣáájú
**4.0** Àkóónú Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
**4.1** Àpólà Aṣẹ̀pọ́n (APEP) gẹ́gẹ́ bí ẹpọ́n aṣàfikún atẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe
**5.0** Ìsọníṣókí
**6.0** Iṣẹ́ Ṣíṣe
**7.0** Ìwé Ìtọ́kasí/Àwọn Ìwé Fùn Kíkà

### 1.0 ÌFÁÁRÀ
Ní ìdánilẹ́kọ̀ọ́ méjì tó kọjá, mo ṣàlàyé àpólà aṣẹ̀pọ́n (APEP) gẹ́gẹ́ bí ẹpọ́n aṣàfikún aṣáájú ọ̀rọ̀-íṣe. Gẹ́gẹ́ bí mo sì ti fi hàn ṣaájú nínú ìhun àpólà ìṣe pé aṣàfikún lè jẹyọ ṣaáju ọ̀rọ̀ ìṣe, ó sì tún lè jẹyọ tẹ̀lé ọ̀rọ̀ ìṣe, ní ìpín yìí, mà á ṣàlàyé ẹ̀pọ́n aṣàfikún atẹ̀lé ọ̀rọ̀-íṣe.

### 2.0 ÈRÒŃGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN
Lẹ́yìn tí ó bá ti ka ìpín yìí tán, wà á lè dá ẹ̀pọ́n aṣàfikún atẹ̀lé ọ̀rọ̀-íṣe mọ, wà á sì le fi hàn nínú àwòrán atọ́ka igi.

### 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢÁÁJÚ
Kọ àpẹẹrẹ àpólà ìṣe tí ó ni ìhun àpólà aṣẹ̀pọ́n (APEP) atẹ̀lé ọ̀rọ̀-íṣe, kí o sì fi hàn nínú àwòrán atọ́ka igi.

### 4.0 ÀKÓÓNÚ ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́
### 4.1 Àpólà Aṣẹ̀pọ́n (APEP) gẹ́gẹ́ bí ẹ̀pọ́n aṣàfikún atẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe
Àpólà Aṣẹ̀pọ́n (APEP) náà ni a máa ń lò gẹgẹ́ bí ẹ̀pọ́n aṣàfikún atẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí.

11a. Adé sùn ***lọ.***
b. Adé sùn ***fọnfọn.***
d. Ìṣẹ̀lẹ̀ náà burú ***jâì***
e. Mi ò gbọ́ ọ̀rọ̀ burúkú yẹn ***rí***

12a



b




Àwọn ẹ̀pọ́n aṣàfikún atẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí inú àwọn àpẹẹrẹ wọ̀nyí ni ***lọ, fọnfọn, jáì*** àti ***rí.***

Àwọn àpólà aṣẹ̀pọ́n alábọ̀ tí wọ́n jẹ́ ẹ̀pọ́n aṣàfikún atẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí ni mi fi hàn nínú àwọn àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ wọ̀nyí.

13a. Ọ̀gà wa ti lọ ***sí ilé.***
b. Wọ́n kọrin ***pẹ̀lú túlàsì.***
d. Obìnrin náà ta aṣọ ***fún mi.***
e. Olú kó bàtà náà ***sínú àpò méjì.***

**Commented [O.J78]:** Ǹjẹ́ kò ní í dára kí a rán àwọn akẹ́kọ̀ọ́ létí wí pé àpólà-atọ́kùn ni àwọn àpẹẹrẹ tí a sàlámì dúdú wọ̀nyẹn kí wọn tó ṣiṣẹ́ àpọ́nlé?

Ní àwọn àpẹẹrẹ òkè wọ̀nyí, àwọn àpólà aṣẹ̀pọ́n ***sí ilé, pẹ̀lú túlàsì, fún mi*** àti ***sínú àpò méjì*** ni wọ́n ń ṣiṣẹ́ gẹ́gẹ́ bí ẹ̀pọ́n aṣàfikún atẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí nínú àwọn gbólóhùn tí wọ́n ti jẹ yọ.

14a



b.




Ó dàbí ẹni pé àpólà aṣẹ̀pọ́n aláìlàbọ̀ àti alábọ̀ aṣàfikún atẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí lè tẹ̀lé ara wọn nínú ìhun àpólà ìṣe. Àmọ̀ kò dàbí ẹni pé ìjẹyọpọ̀ yìí wọ́pọ̀ rárá. Àwọn àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí ni ibi ti ìjẹyọpọ̀ àwọn méjèèjì ti wáyé.

15a. Adé sùn ***fọnfọn sínú ọkọ̀ ayọ́kẹ́lẹ́***
b. Oúnjẹ tí a rà lánàá ti tán ***kíákíá ní àárọ̀ yìí***




**ÌGBÉLÉWỌ̀N AKẸ́KỌ̀Ọ́**
Gbìyànjú kí o fi ìhun àpólà ìṣe ìsàlẹ̀ yìí hàn ni àwòrán atọ́ka igi.
kọrin ***pẹ̀lú túlàsì***

## 5.0 ÌSỌNÍṢÓKÍ

Ní ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, mo ṣàlàyé ẹ̀pọ́n aṣàfikún atẹ̀lé ọ̀rọ̀-íṣe. Àpólà Aṣẹ̀pọ́n (APEP) náà ni a máa ń lò gẹ́gẹ́ bí ẹ̀pọ́n aṣàfikún atẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe. Bíi ti ẹ̀pọ́n aṣàfikún aṣaájú ọ̀rọ̀-ìṣe, ẹ̀pọ́n aṣàfikún atẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe yìí náà lè jẹ́ alábọ̀ tàbi aláìlábọ̀.

## 6.0 IṢẸ́ ṢÍṢE

Kọ àpẹẹrẹ àpólà ìṣe márùn-ún tí ó ní ìhun ẹ̀pọ́n aṣàfikún atẹ̀lé ọ̀rọ̀-íṣe, kí o sì fi hàn nínú àwòrán atọ́ka igi.

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ/ÀWỌN ÌWÉ FÙN KÍKÀ

Awóbùlúyì, O. 1978. *Essentials of Yorùbá Grammar*, Ìbàdàn: UPL.
Awobuluyi, O. 1988. *Èdè Ìperí Yorùbá*: *Apá kejí*, Lagos: NERDC

Awóbùlúyì, O. 2001a. “Arọ́pò–Orúkọ Kúkúrú Ẹni–Kẹ́ta Ẹyọ Aṣolùwà” *Yorùbá,* Vol. 2, No. 1 pp 1-8
Awóbùlúyì, O. 2001b. “Òte–Ìlò Àwọn Arọ́pò–Orúkọ Kúkúrú” Bébà tí a kà ní Àpérò Ẹgbẹ́ Onímọ̀ ÈdèYorùbá: Yunifásítì ìlú Eko.
Awobuluyi, O. 2008. *Ẹ̀kọ́ Íṣẹ̀dá-Ọ̀rọ̀ Yorùbá*, Akurẹ: Montem Paperbacks
Awobuluyi, O. 2013. *Ẹ̀kọ́ Gírámà Èdè Yorùbá*, Oshogbo: Montem Paperbacks
Bámgbóṣé, Ạ. 1967. *A Short Yorùbá Grammar,* Ìbàdàn: HEB.
Bámgbóṣé, Ạ. 1990. *Fonọ́lọ́jì àti Gírámà Yorùbá*. Ìbàdàn: UPL.
Oyetade, S.O. 1995. *Yorùbá Grammar I*. Ibadan, Centre for External Studies, UI.
Táíwò, O. 2003. Tense and Aspect in Ào. Nínú Ndimele O.M (olótùú) *Languages and Linguistics in Nigeria.* A Festscrist in Honour of Kay williamson.
Taiwo, O. 2007. Short Subject Pronoun in the Ào dialect of Yorùbá. *JOLAN: Journal of Linguistic Association of Nigeria (JOLAN)* No 10 o.i. 67 – 86
Taiwo, O. 2008a. *Basic Concepts in Grammar*: Ibadan, DLC, UI
Taiwo, O. 2008b. *Basic Grammar*: Ibadan, DLC, UI

# MÓDÙ 4: Ẹ̀PỌ́N AṢÀMÚPÉ NÍNÚ ÌHUN ÀPÓLÀ ÌṢE (APIṢ)

Ní módù yìí mà á tẹ̀síwájú láti máa kọ́ ọ ní ìhun àpólà ìṣe. Àfojúsùn módù yìí ni láti ṣàlàyé ẹ̀pọ́n aṣàmúpé nínú ìhun àpólà ìṣe. Àmúpé ni ọ̀rọ̀ tí ó jẹ yọ pẹ̀lú ọ̀rọ̀ mìíràn láti mú kí ìtumọ̀ ọ̀rọ̀ náà pé. Àwọn àpólà tí wọ́n máa ń ṣe iṣẹ́ ẹ̀pọ́n aṣàmúpé nínú ìhun àpólà ìṣe ni Àpólà Orúkọ (APOR), Àpólà Aṣàmúpé (APAM) àti Apólà Aṣẹ̀pọ́n (APEP). Ní ìgbà mìíràn, àpólà àmúpé máa ń ju ẹyọkan lọ nínú àpóla ìṣe. Èyí níi ṣe pẹ̀lú irú ọ̀rọ̀ ìṣe tí ó jẹ́ orí nínú àpóla ìṣe náà. Àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe kan wà tí wọ́n máa ń gba Àpólà Orúkọ (APOR) bíi àbọ̀ wọn, tí àwọn mìíràn sì ń gba Apólà Aṣẹ̀pọ́n (APEP) bíi àbọ̀ wọn. Àmọ, àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe kan tún wà tí wọ́n máa ń gba àpapọ̀ Àpólà Orúkọ (APOR) àti Apólà Aṣẹ̀pọ́n (APEP) ní àbọ̀ wọn.

Bí ọ̀rọ̀ bá rí báyìí, báwo ni á ṣe fihàn nínú àwòrán atọ́ka-igi pé ọ̀rọ-ìṣe tó jẹ́ orí ní àmúpé méjì? Ní àtijọ ni èyí fẹ́ lọjú díẹ̀, àmọ́ ìmọ̀ tuntun jẹ́ kí ó ye wa pé àwọn àpólà ìṣe (APIṢ) tí o bá ní àmúpé méjì báyìí gbọ́dọ̀ ní APIṢ méjì nínú àwòrán atọ́ka-igi. Ọ̀kan tí IṢ kékeré ṣe orí fún àti èkejì tí IṢ ńlá ṣe orí fún. Mà á máa ṣàlàyé síwájú sí i bí a ṣe ń lo APIṢ méjéèjì yìí ní abala ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí.

Ní mòdú yìí, wà á kọ́ nípa àwọn àpólà tí wọ́n máa ń ṣe iṣẹ́ àmúpe fún ọ̀rọ̀-ìṣe nínú ìhun àpólà ìṣe. Lẹ́yìn náà mà á kọ́ ọ bí àwọn ẹ̀pọ́n inú àpólà ìṣe ṣe tẹ̀lé ara wọ́n nínú ìhun àpólà ìṣe. Àwọn àkòrí wọ̀nyí ni o máa kà ní módù yìí:

Ìpín 1: Àpólà Orúkọ (APOR) àti Àpólà Aṣàmúpé (APAM) gẹ́gẹ́ Ẹ̀pọ́n Aṣàmúpé
Ìpín 2: Apólà Aṣẹ̀pọ́n (APEP) gẹ́gẹ́ bi Àmúpé IṢ nínú APIṢ
Ìpín 3: Àpapọ̀ APOR àti APEP Alàbọ̀ gẹ́gẹ́ bí Àmúpé
Ìpín 4: Tẹ̀lẹ́ǹtẹ̀lé Ẹ̀pọ́n nínú Ìhun Àpólà Ìṣe

**ÌPÍN 1:** **ÀPÓLÀ ORÚKỌ (APOR) ÀTI ÀPÓLÀ AṢÀMÚPÉ (APAM) GẸ́GẸ́ BÍ ÈPỌ́N AṢÀMÚPÉ**


**1.0** Ìfáárà
**2.0** Èròǹgbà àti Àfojúsùn
**3.0** Ìbéèrè Ìṣáájú
**4.0** Àkóónú Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
**4.1** Àpólà orúkọ (APOR) àti àpólà aṣàmúpé (APAM) gẹ́gẹ́ èpọ́n aṣàmúpé
**5.0** Ìsọníṣókí
**6.0** Iṣẹ́ Ṣíṣe
**7.0** Ìwé Ìtọ́kasí/Àwọn Ìwé Fùn Kíkà


## 1.0 ÌFÁÁRÀ
Yàtọ̀ sí èpọ́n aṣàfikún tí ó wà nínú ìhun àpólà ìṣe, irúfẹ́ èpọ́n mìíràn tó wà niínú ìhun àpólà ìṣe ni èpọ́n àmúpé. Èpọ́n àmúpé yìí máa ń jẹyọ tààrà tẹ̀lé ọ̀rọ̀ ìṣe. Ní ìpín yìí, mà á ṣàlàyé àpólà orúkọ (APOR) àti àpólà aṣàmúpé (APAM) gẹ́gẹ́ èpọ́n aṣàmúpé.

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN
Lẹ́yìn tí ó bá ti ka ìpín yìí tán, wà á lè dá èpọ́n aṣàmúpé mọ̀ nínú ìhun àpólà ìṣe, wà á sì le fi hàn nínú àwòrán atọ́ka igi.

## 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢÁÁJÚ
Kọ àpẹẹrẹ àpólà ìṣe tí ó ni ìhun èpọ́n aṣàmúpé, kí o sì fi hàn nínú àwòrán atọ́ka igi

## 4.0 ÀKÓÓNÚ ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́
### 4.1 Àpólà orúkọ (APOR) àti àpólà aṣàmúpé (APAM) gẹ́gẹ́ èpọ́n aṣàmúpé
Nínú ìhun àpólà ìṣe, àwọn ìsọ̀rí-ọ̀rọ̀ kan wà tí wọ́n gbọ́dọ̀ jẹ yọ tẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí láti mú kí ìtumọ̀ rẹ̀ pé. Irú àwọn ìsọ̀rí-ọ̀rọ̀ tí wọ́n mú ìtumọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí pé yìí ni a mọ̀ sí èpọ́n aṣàmúpé.

1a. Olú san ***owó ọkọ̀ nàà***
b. Ọmọ nàà pa ***eku yẹn***
d. Ọmọ nàà ta ***gìtá***

Àwọn àpólà orúkọ tí mo kọ ní àkọhàn-adẹ̀gbẹ́ nínú àwọn gbólóhùn òkè wọ̀nyí jẹ́ èpọ́n aṣàmúpé fún àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí tí wọ́n jẹ́ yọ tẹ̀lé. Àwọn ni wọ́n mú ìtumọ̀ àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí nàà pé. Àbùdá àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe bíi ***san, pa,*** àti ***ta*** ni pé wọ́n gbọ́dọ̀ yan àpólà orúkọ àbọ̀ tí ó gbọ́dọ̀ jẹ yọ tẹ̀lé wọn, láìjẹ́ bẹ́ẹ̀, gbólóhùn tí wọ́n bá ti jẹ yọ kò ní ṣe é gbà.

Àwọn IṢ kan máa ń gba APOR gẹ́gẹ́ bí àmúpé, àwọn kan sì máa ń gba APAM.

2a Adé [**gbọ́ ọ̀rọ̀ mi].**
b. Ó [**dára pé mo gbàgbọ́ nínú Jésù]**

Ní àpẹẹrẹ òkè wọ̀nyí, APIṢ ni mo kọ ní àkọhàn tí mo sì tún fi sínú àkámọ́ onígun. Ní (2a) àti (2b), IṢ gba àmúpé kọ̀ọ̀kan. IṢ ***gbọ́*** gba APOR ***ọ̀rọ̀ mi*** gẹ́gẹ́ bí àmúpé, APOR yìí sì ni arábìnrin IṢ ni (2a). Ní (2b), APAM, ***pé mo gbàgbọ́ nínú Jésù*** ni àmúpé fùn IṢ ***dára,*** àti arábìnrin rẹ̀. Àwòrán atọ́ka-igi ìsàlẹ̀ wọ̀nyí (3), ni mo fi fi ìrísí àwọn APIṢ tí ó wà ní (2) hàn.

3a




b.




Ṣàkíyèsí pé ní àwòrán atọ́ka-igi (3a), IṢ, ***gbọ́,*** tí ó jẹ́ ìpele akérépin, gba APOR, ***ọ̀rọ̀ mi*** gẹ́gẹ́ bí àbọ̀, òun sì ni àmúpé rẹ̀. Àwọn méjèèjì pa pọ̀ di IṢ$^{I}$, ìpele abàárín. Nítorí pé APIṢ yìí kò ní asọdọ̀tọ̀, ìpele abàárín yìí kò ní arábinrin, òun nìkan ni ó di APIṢ, tíi ṣe ìpele agajù. Bẹ́ẹ̀ náà ni ọ̀rọ̀ rí fún IṢ ***dára*** ní (3b) nítorí pé, IṢ, ***dára,*** tí ó jẹ́ ìpele akérépin, gba APAM, ***pé mo gbàgbọ́ nínú Jésì*** gẹ́gẹ́ bí àmúpé rẹ̀. Àwọn méjèèjì pa pọ̀ di IṢ$^{I}$, ìpele abàárín. Nítorí pé APIṢ yìí náà kò ní asọdọ̀tọ̀, ìpele abàárín yìí kò ní arábinrin, òun nìkan ni ó di APIṢ, tíi ṣe ìpele agajù.

**ÌGBÉLÉWỌ̀N AKẸ́KỌ̀Ọ́**

Gbìyànjú láti ya àwórán atọ́ka-igi fún àpólà ìṣe méji tí ó ni ìhun Àpólà orúkọ (APOR) gẹ́gẹ́ bí ẹ̀pọ́n asàmúpé.

## 5.0 ÌSỌNÍṢÓKÍ

Ní ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, mo ṣàlàyé àpólà orúkọ (APOR) àti àpólà aṣàmúpé (APAM) gẹ́gẹ́ ẹ̀pọ́n aṣàmúpé fún ọ̀rọ̀ ìṣe. Mo sì fi hàn nínú àwòrán atọ́ka igi. Ẹ̀pọ́n asàmúpé máa ń papọ̀ mọ́ ọ̀rọ̀ ìṣe aṣorí IS láti di ìpele abàárín IS[I] nínú àwòrán atọ́ka igi.

## 6.0 IṢẸ́ ṢÌṢE

Kọ àpẹẹrẹ àpólà ìṣe márùn-ún tí ó ni ìhun àpólà aṣàmúpé (APAM) gẹ́gẹ́ bí ẹ̀pọ́n asàmúpé.

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ/ÀWỌN ÌWÉ FÙN KÍKÀ


Awóbùlúyì, O. 1978. *Essentials of Yorùbá Grammar,* Ìbàdàn: UPL.

Awobuluyi, O. 1988. *Èdè Ìperí Yorùbá*: *Apá kejí*, Lagos: NERDC

Awóbùlúyì, O. 2001a. "Arọ́pò–Orúkọ Kúkúrú Ẹni–Kẹ́ta Ẹyọ Aṣolùwà" *Yorùbá*, Vol. 2, No. 1 pp 1-8

Awóbùlúyì, O. 2001b. "Òte–Ìlò Àwọn Arọ́pò–Orúkọ Kúkúrú" Bébà tí a kà ní Àpérò Ẹgbẹ́ Onímọ̀ ÈdèYorùbá: Yunifásítì ìlú Eko.

Awobuluyi, O. 2008. *Ẹ̀kọ́ Íṣẹ̀dá-Ọ̀rọ̀ Yorùbá*, Akurẹ: Montem Paperbacks

Awobuluyi, O. 2013. *Ẹ̀kọ́ Gírámà Èdè Yorùbá*, Oshogbo: Montem Paperbacks

Bámgbóṣé, Ạ. 1967. *A Short Yorùbá Grammar,* Ìbàdàn: HEB.

Bámgbóṣé, Ạ. 1990. *Fonọ́lọ́jì àti Gírámà Yorùbá*. Ìbàdàn: UPL.

Oyetade, S.O. 1995. *Yorùbá Grammar I*. Ibadan, Centre for External Studies, UI.

Táíwò, O. 2003. Tense and Aspect in Ào. Nínú Ndimele O.M (olótùú) *Languages and Linguistics in Nigeria.* A Festscrist in Honour of Kay williamson.

Taiwo, O. 2007. Short Subject Pronoun in the Ào dialect of Yorùbá. *JOLAN: Journal of Linguistic Association of Nigeria (JOLAN)* No 10 o.i. 67 – 86

Taiwo, O. 2008a. *Basic Concepts in Grammar*: Ibadan, DLC, UI

Taiwo, O. 2008b. *Basic Grammar*: Ibadan, DLC, UI

## ÌPÍN 2: ÀPÓLÀ AṢẸ̀PỌ́N (APEP) GẸ́GẸ́ BI ÀMÚPÉ IṢ NÍNÚ APIṢ


**1.0** Ìfáárà
**2.0** Èròǹgbà àti Àfojúsùn
**3.0** Ìbéèrè Ìṣáájú
**4.0** Àkóónú Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
**4.1** APEP aláìlábọ̀ gẹ́gẹ́ bi àmúpé IṢ nínú APIṢ
**4.2** APEP alàbọ̀ gẹ́gẹ́ bí àmúpé IṢ nínú APIṢ
**5.0** Ìsọníṣókí
**6.0** Iṣẹ́ Ṣíṣe
**7.0** Ìwé Ìtọ́kasí/Àwọn Ìwé Fùn Kíkà


### 1.0 ÌFÁÁRÀ

Ní ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tó kọjá, mo ṣàlàyé àpólà orúkọ (APOR) àti àpólà aṣàmúpé (APAM) gẹ́gẹ́ ẹ̀pọ́n aṣàmúpé. Mà á tẹ̀síwájú ní ìpín yìí láti ṣàlàyé àpólà aṣẹ̀pọ́n alàbọ̀ àti aláìlábọ̀ gẹ́gẹ́ bi àmúpé nínú àpólà ìṣe.

Commented [O.J79]: aṣamúpé

### 2.0 ÈRÒŇGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN

Lẹ́yìn tí ó bá ti ka ìpín yìí tán, wà á lè mọ àpólà aṣẹ̀pọ́n tí ó ń ṣe àmúpé nínú ìhun àpólà ìṣe, wà á sì le fi hàn nínú àwòrán atọ́ka igi.

### 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢÁÁJÚ

Fi àpẹẹrẹ ṣe ìyàtọ̀ láàárin àpólà aṣẹ̀pọ́n tí ó ń ṣe àmúpé àti èyí ti ó ń ṣe àfikún nínú ìhun àpólà ìṣe.

### 4.0 ÀKÓÓNÚ ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

#### 4.1 APEP Aláìlábọ̀ gẹ́gẹ́ bi Àmúpé IṢ nínú APIṢ

Àwọn IṢ kan wà tí wọ́n máa ń gba Àpólà Aṣẹ̀pọ́n (APEP) aláìlàbọ̀ gẹ́gẹ́ bí àmúpé. Kànńpá ni irú àwọn àmúpé bẹ́ẹ̀ nínú ìhun APIṢ nítorí pé IṢ tí ó jẹ́ orí nínú ìhun APIṢ kò lè dá wà láì gba APEP bẹ́ẹ̀. Àpẹẹrẹ wọn ni mo fi hàn ní ìsàlẹ̀ yìí.

4a Ọbẹ̀ náà [**ta sánsán**]
b Aṣọ náà [**bẹ́ yòò]**
d. Ọmọ náà [**já fáfá**].

Ní (4a), IṢ ***ta*** gba APEP ***sánsán*** bì àmúpé nínú APIṢ, bàkan náà, IṢ ***bẹ́*** gba APEP ***yòò*** gẹ́gẹ́ bi àmúpé nínú APIṢ ní (4b), ní ìparí, IṢ ***já*** gba APEP ***fáfá*** ní àmúpé. Gẹ́gẹ́ bí mo ṣe ṣàlàyé ṣáájú, kòṣeémánìí ni àwọn APEP wọ̀nyí fún IṢ, bí wọn kò bá sí nínú IṢ níbi tí wọ́n ti jẹ yọ, ìsọ àìṣeégbà ni yóò fún wa. Ìrísí wọn ni mo fi hàn ní ìsàlẹ̀ yìí.

5




Ní àwòrán atọ́ka-igi (5), IṢ, tí ó jẹ́ ìpele akérépín pa pọ̀ mọ́ arábìnrin tíi ṣe APEP, àwọn méjèèjì sì di ìpele abàárín, IṢI, ìpele abàárín yìí kò ní arábìnrín, nítorí kò sí asọdọ̀tọ̀ nínú ìhun APIṢ yìí, òun nìkan ni ó di ìpele agajù tíi ṣe APIṢ.

**ÌGBÉLÉWỌ̀N AKẸ́KỌ̀Ọ́**

Gbìyànjú láti ya àwórán atọ́ka-igi fún àpólà ìṣe méji tí ó ni ìhun APEP Aláìlábọ̀ gẹ́gẹ́ bi Àmúpé.

### 4.2 APEP Alàbọ̀ gẹ́gẹ́ bí àmúpé IṢ nínú APIṢ

Àwọn IṢ kan wà tí wọ́n gbọ́dọ̀ yan Àpólà Aṣèpọ́n alàbọ̀ gẹ́gẹ́ bí àmúpé nítorí pé kànńpá ni APEP jẹ́ fún irú wọn. Irú àwọn IṢ bẹ́ẹ̀ ni ***já, kú, gbé*** àti ***mọ*** ní àwọn àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ wọ̀nyí.

6a Akitiyan rẹ̀ [**já sí asán].**
b. Ó ti [**já sí ọ̀nà]**.
d. Owó náà [**kú sí àpò kan]**.
e. Ọ̀gá wa ń [**gbé ní Ìbàdàn]**.
ẹ Ó **[mọ ní Èkó níkan]**

Ní àwòrán atọ́ka-igi (7) ní ìsàlẹ̀ yìí, IṢ, tí ó jẹ́ ìpele akérépín pa pọ̀ mọ́ arábìnrin tíi ṣe APEP, àwọn méjèèjì sì di ìpele abàárín, IṢI, ìpele abàárín yìí kò ní arábìnrín, nítorí kò sí asọdọ̀tọ̀ nínú ìhun APIṢ méjèèjì, ìpele abàárín nìkan ni ó di ìpele agajù tíi ṣe APIṢ.

7a



b




**ÌGBÉLÉWỌ̀N AKẸ́KỌ̀Ọ̀**

Gbìyànjú láti ya àwórán atọ́ka-igi fún àpólà ìṣe méji tí ó ni ìhun APEP Alábọ̀ gẹ́gẹ́ bi Àmúpé.

## 5.0 ÌSỌNÍṢÓKÍ

Ní ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, mo ṣàlàyé àwọn ọ̀rọ̀ ìṣe kan wà tí wọ́n máa ń gba Àpólà Aṣèpọ́n (APEP) yálà alábọ̀ tàbí aláìlàbọ̀ gẹ́gẹ́ bí àmúpé. Kànńpá sì ni irú àwọn àmúpé bẹ́ẹ̀ nínú ìhun àpólà ìṣe yìí  Mo tẹ̀síwájú láti fi ìrísí irúfẹ́ àwọn àpólà ìṣe bẹ́ẹ̀ hàn nínú àwòrán atọ́ka

## 6.0 IṢẸ́ ṢÌṢE

Kọ àpẹẹrẹ àpólà ìṣe márùn-ún tí ó ni ìhun Àpólà Aṣèpọ́n (APEP) gẹ́gẹ́ bíi àmúpé, kí o sì fi hàn nínú àwòrán atọ́ka igi.

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ/ÀWỌN ÌWÉ FÙN KÍKÀ

Awóbùlúyì, O. 1978. *Essentials of Yorùbá Grammar*, Ìbàdàn: UPL.

Awobuluyi, O. 1988. *Èdè Ìperí Yorùbá*: *Apá kejí*, Lagos: NERDC

Awóbùlúyì, O. 2001a. "Arọ́pò–Orúkọ Kúkúrú Ẹni–Kẹ́ta Ẹyọ Aṣolùwà" *Yorùbá*, Vol. 2, No. 1 pp 1-8

Awóbùlúyì, O. 2001b. "Òte–Ìlò Àwọn Arọ́pò–Orúkọ Kúkúrú" Bébà tí a kà ní Àpérò Ẹgbẹ́ Onímọ̀ ÈdèYorùbá: Yunifásítì ìlú Eko.

Awobuluyi, O. 2008. *Ẹ̀kọ́ Íṣẹ̀dá-Ọ̀rọ̀ Yorùbá*, Akurẹ: Montem Paperbacks

Awobuluyi, O. 2013. *Ẹ̀kọ́ Gírámà Èdè Yorùbá*, Oshogbo: Montem Paperbacks

Bámgbóṣé, Ạ. 1967. *A Short Yorùbá Grammar*, Ìbàdàn: HEB.

Bámgbóṣé, Ạ. 1990. *Fonọ́lọ́jì àti Gírámà Yorùbá*. Ìbàdàn: UPL.

Oyetade, S.O. 1995. *Yorùbá Grammar I*. Ibadan, Centre for External Studies, UI.

Táíwò, O. 2003. Tense and Aspect in Ào. Nínú Ndimele O.M (olótùú) *Languages and Linguistics in Nigeria*. A Festscrist in Honour of Kay williamson.

Taiwo, O. 2007. Short Subject Pronoun in the Ào dialect of Yorùbá. *JOLAN: Journal of Linguistic Association of Nigeria (JOLAN)* No 10 o.i. 67 – 86

Taiwo, O. 2008a. *Basic Concepts in Grammar*: Ibadan, DLC, UI

Taiwo, O. 2008b. *Basic Grammar*: Ibadan, DLC, UI

**ÌPÍN 3:** **ÀPAPỌ̀ ÀPÓLÀ ORÚKỌ (APOR) ÀTI ÀPÓLÀ AṢẸ̀PỌ́N (APEP) ALÀBỌ̀ GẸ́GẸ́ BÍ ÀMÚPÉ**


**1.0** Ìfáárà
**2.0** Èròǹgbà àti Àfojúsùn
**3.0** Ìbéèrè Ìṣáájú
**4.0** Àkóónú Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
**4.1** Àpapọ̀ APOR àti APEP alàbọ̀ gẹ́gẹ́ bí àmúpé
**5.0** Ìsọníṣókí
**6.0** Iṣẹ́ Ṣíṣe
**7.0** Ìwé Ìtọ́kasí/Àwọn Ìwé Fùn Kíkà


## 1.0 ÌFÁÁRÀ

Ní ìgbà mìíràn, àpólà ìṣe lè ní àpapọ̀ àpólà orúkọ APOR àti àpólà aṣẹpọ́n APEP gẹ́gẹ bíi àmúpé, nítorí irúfẹ́ ọ̀rọ̀-ìṣe tó jẹ́ orí nínú àpólà ìṣe bẹ́ẹ̀. Kànńpá ni irú àwọn àmúpé méjèèjì yìí sì máa ń jẹ́ ní irú àpólà ìṣe bẹ́ẹ̀. Ní ìpín yìí, mà á ṣàlàyé ìrísí àpólà ìṣe ní ibi tí àpólà orúkọ APOR àti àpólà aṣẹpọ́n APEP ti jẹ́ àmúpé.

## 2.0 ÈRÒŃGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN

Lẹ́yìn tí ó bá ti ka ìpín yìí tán, wà á lè mọ ìhun àpólà ìṣe tí ó ní àpólà orúkọ APOR àti àpólà aṣẹpọ́n APEP ti jẹ́ àmúpé, wà á sì le fi wọ́n hàn nínú àwòrán atọ́ka igi.

Commented [O.J80]: ti ó jẹ́

## 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢÁÁJÚ

Gbìyànjú láti kọ àpẹẹrẹ àpólà ìṣe tí ó ní àpapọ̀ àpólà orúkọ APOR àti àpólà aṣẹpọ́n APEP gẹ́gẹ bíi àmúpé.

## 4.0 ÀKÓÓNÚ ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

### 4.1 Àpapọ̀ APOR àti APEP Alàbọ̀ gẹ́gẹ́ bí Àmúpé

Àwọn IṢ kan wà tí wọ́n máa ń gba àpapọ̀ Àpólà Orúkọ (APOR) àti Àpólà Aṣẹ̀pọ́n (APEP) alàbọ̀ gẹ́gẹ́ bí àmúpé. Kànńpá ni irú àwọn àmúpé tí ó jẹ́ APOR àti APEP bẹ́ẹ̀ nínú ìhun APIṢ nítorí pé IṢ tí ó jẹ́ orí nínú ìhun APIṢ kò lè dá wà láì gba àwọn àpólà méjèèjì. Àpẹẹrẹ wọn ni mo fi hàn ní ìsàlẹ̀ yìí.

8a Wọ́n [**kò mí ní ọ̀nà]**
b Ayé kò [**fẹ́ ẹni fún ire]**
d. Adé [**fi ọ̀bẹ sí àpò]**
e. Ọpẹ́ [**kọ èyìn sí mi]**
ẹ O [**ṣá mi ní àdá]**

Commented [O.J81]: Ẹ̀wẹ̀, gbogbo àwọn àpẹẹrẹ yẹn (ní ọ̀nà abbl.) ni wọ́n jẹ́ APAT kí wọn tó ṣìṣẹ́ àpọ́nlé

.Ní (8a-ẹ), APIṢ ni mo kọ ní àhọ̀hàn tí mo sì tún fi sí àkámọ́ onígun, IṢ kọ̀ọ̀kan nínú wọn gba àmúpé méjì méjì, tíí ṣe APOR àti APEP.

Ní àwòrán atọ́ka-igi (9) ní ìsàlẹ̀, mo fi ìrísí àwọn APIṢ tí ó wà ní àpẹẹrẹ (8) hàn. Ìrísí kan náà ni wọ́n ní, fún ìdí èyí, mo fi ìrísí àpẹẹrẹ (8a) hàn láti dúró fún àwọn ìyókù.

9.




Tí o bá ṣàkíyèsí àwòrán òkè yìí dáadáa, wà á rí i pé APIṢ méjì ni ó ní, APIṢ kékeré áti APIṢ. Ìmọ̀ tuntun jẹ́ kí ó ye wa pé àwọn APIṢ tí o bá ní àmúpé méjì báyìí gbọ́dọ̀ ní IṢ kékeré àti IṢ. IṢ yìí ni a gbé, fún ìdí kan tàbí òmíràn, lọ sí IṢ kékeré.

A wá lè ṣàlàyé ìrísí APIṢ tí ó ní àmúpé méjì báyìí: IṢ, ***kò,*** tí ó jẹ́ ìpele akérépin, gba APEP gẹ́gẹ́ bí àmúpé rẹ̀, àwọn méjèèjì sí pa pọ̀ di IṢ$^{I}$, tí ó jẹ́ ìpele abàárín. IṢ$^{I}$ yìí gba APOR gẹ́gẹ́ bí asọdọ̀tọ̀ rẹ̀, àwọn méjèèjì sì pa pọ̀ dí APIṢ, ìpele agajù. IṢ kékeré gba APIṢ gẹ́gẹ́ bí àmúpé rẹ́, ṣùgbọ́n IṢ kékeré jẹ́ afarasin, a wá gbé IṢ, ***kò,*** láti àyè rẹ́, ibi tí ó ti gba APEP gẹ́gẹ́ bí àmúpé, a sì wa so ó mọ̀ IṢ kékeré. Lẹ́yìn ìsomọ́ yìí, òun àti APIṢ wá pa pọ̀ di ÌṢ$^{I}$, ìpele abàárín kékeré, èyí kò ní asọdọ̀tọ̀ kankan, òun nìkan ni ó di APIṢ kékeré agajù.

**ÌGBÉLÉWỌ̀N AKẸ́KỌ̀Ọ̀**

Gbìyànjú láti ya àwórán atọ́ka-igi fún àpólà ìṣe méji tí ó ni àpapọ̀ APOR àti APEP Alàbọ̀ gẹ́gẹ́ bí Àmúpé.

## 5.0 ÌSỌNÍṢÓKÍ

Ní ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, mo ṣàlàyé àwọn àpólà ìṣe kan wọ́n máa ń ní àpapọ̀ àpólà orúkọ APOR àti àpólà aṣẹpọ́n APEP gẹ́gẹ bíi àmúpé, nítorí irúfẹ́ ọ̀rọ̀-ìṣe tó jẹ́ orí nínú àpólà ìṣe bẹ́ẹ̀. Àti pé Kànńpá ni irú àwọn àmúpé méjèèjì yìí sì máa ń jẹ́ ní irú àpólà ìṣe bẹ́ẹ̀. Mo ìrísí àpólà ìṣe yìí hàn nínú àwòrán atọ́ka. Láti fi àmúpé méjèèjì yìí hàn nínú àwòrán atọ́ka igi, ìmọ̀ tuntun jẹ́ kí ó ye wa pé APIṢ méjì ni ó gbọ́dọ̀ ní, iyẹn APIṢ kékeré áti APIṢ ńlá.

Commented [O.J82]: kan tí wọ́n

Commented [O.J83]: Mo fi irísí

## 6.0 IṢẸ́ ṢÌṢE

Gbìyànjú láti fi ìhun àpólà ìṣe inú gbólóhùn ìsàlẹ̀ yìí hàn nínú àwòrán atọ́ka igi.

Ayé kò [**fẹ́ ẹni fún ire]**

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ/ÀWỌN ÌWÉ FÙN KÍKÀ

Awóbùlúyì, O. 1978. *Essentials of Yorùbá Grammar*, Ìbàdàn: UPL.
Awobuluyi, O. 1988. *Èdè Ìperí Yorùbá*: *Apá kejí*, Lagos: NERDC

Awóbùlúyì, O. 2001a. “Arọ́pò–Orúkọ Kúkúrú Ẹni–Kẹ́ta Ẹyọ Aṣolùwà” *Yorùbá*, Vol. 2, No. 1 pp 1-8
Awóbùlúyì, O. 2001b. “Òte–Ìlò Àwọn Arọ́pò–Orúkọ Kúkúrú” Bébà tí a kà ní Àpérò Ẹgbẹ́ Onímọ̀ ÈdèYorùbá: Yunifásítì ìlú Eko.
Awobuluyi, O. 2008. *Ẹ̀kọ́ Íṣẹ̀dá-Ọ̀rọ̀ Yorùbá*, Akurẹ: Montem Paperbacks
Awobuluyi, O. 2013. *Ẹ̀kọ́ Gírámà Èdè Yorùbá*, Oshogbo: Montem Paperbacks
Bámgbóṣé, Ạ. 1967. *A Short Yorùbá Grammar,* Ìbàdàn: HEB.
Bámgbóṣé, Ạ. 1990. *Fonọ́lọ́jì àti Gírámà Yorùbá*. Ìbàdàn: UPL.
Oyetade, S.O. 1995. *Yorùbá Grammar I*. Ibadan, Centre for External Studies, UI.
Táíwò, O. 2003. Tense and Aspect in Ào. Nínú Ndimele O.M (olótùú) *Languages and Linguistics in Nigeria.* A Festscrist in Honour of Kay williamson.
Taiwo, O. 2007. Short Subject Pronoun in the Ào dialect of Yorùbá. *JOLAN: Journal of Linguistic Association of Nigeria (JOLAN)* No 10 o.i. 67 – 86
Taiwo, O. 2008a. *Basic Concepts in Grammar*: Ibadan, DLC, UI
Taiwo, O. 2008b. *Basic Grammar*: Ibadan, DLC, UI

## ÌPÍN 4: TẸ̀LÉǸTẸ̀LÉ Ẹ̀PỌ́N NÍNÚ ÌHUN ÀPÓLÀ ÌṢE


**1.0** Ìfáárà
**2.0** Èròǹgbà àti Àfojúsùn
**3.0** Ìbéèrè Ìṣáájú
**4.0** Àkóónú Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
**4.1** Tẹ̀léǹtẹ̀lé ẹ̀pọ́n nínú ìhun àpólà ìṣe
**4.2** Ìrísí APIṢ ọlọ́rọ̀-ìṣe ẹlẹ́là
**5.0** Ìsọníṣókí
**6.0** Iṣẹ́ Ṣíṣe
**7.0** Ìwé Ìtọ́kasí/Àwọn Ìwé Fùn Kíkà


### 1.0 ÌFÁÁRÀ

Ní àwọn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ mélòó kan tó kọjá, mo tẹnpẹlẹ mọ́ ìhun àpólà ìṣe, tí mo sì ṣàlàye àwọn ẹ̀pọ́n inú àpólà ìṣe náà lẹ́ṣẹẹṣẹ. Ohun tí a ṣàkíyèsí ni pé àwọn ẹ̀pọ́n inú ọ̀rọ̀ ìṣe yìí ní bí wọ́n ṣe tẹ̀lé ara wọn. Ní ìpín yìí, mà á ṣàlàyé bí àwọn ẹ̀pọ́n inú ìhun àpólà ìṣe ṣe tẹ̀lé àra wọn. Mà á tún ṣàlàyé ìrísí àpólà ìṣe tí ó ní ọ̀rọ̀ ìṣe ẹlẹ́là.

Commented [O.J84]: mo

### 2.0 ÈRÒǸGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN

Lẹ́yìn tí ó bá ti ka ìpín yìí tán, wà á lè mọ bí àwọn ẹ̀pọ́n inú ìhun àpólà ìṣe ṣe tẹ̀lé àra wọn. Wà á tún mọ ìrísí àpólà ìṣe tí ó ní ọ̀rọ̀ ìṣe ẹlẹ́là.

### 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢÁÁJÚ

Kọ àpẹẹrẹ àpólà ìṣe tí ó ní ọ̀rọ̀ ìṣe ẹlẹ́là.

### 4.0 ÀKÓÓNÚ ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

### 4.1 Tẹ̀léǹtẹ̀lé Ẹ̀pọ́n nínú Ìhun Àpólà Ìṣe

Àwọn àlàyé àti ìjírọ̀rọ̀ tí mo ṣe wọ́nyí fi àwọn àkíyèsí wọ́nyí hàn nípa bí àwọn ẹ̀pọ́n ṣe máa ń jẹ yọ tẹ̀lé ara nínú ìhun àpólà ìṣe:

- Àpólà aṣẹ̀pọ́n aláìlàbọ̀ ni ó máa ń kọ́kọ́ jẹ yọ nínú ìhun àpólà ìṣe gẹ́gẹ́ bí ẹ̀pọ́n aṣàfikún aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe, lẹ́yìn náà ni àpólà aṣẹ̀pọ́n alàbọ̀ aṣàfikún aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe máa jẹ yọ ṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí táárá.
- Ẹ̀pọ́n aṣàmúpé máa ń jẹ yọ tẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí agbàmúpé tàárà nínú ìhun àpólà ìṣe.
- Bí ẹ̀pọ́n aṣàmúpé bá jẹ́ APOR àti APEP, APOR ni ó máa kọ́kọ́ jẹ yọ tẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí agbàmúpé tàárà, lẹ́yìn náà ni APEP yóò jẹ yọ tẹ̀lé APOR.
- Àpólà aṣẹ̀pọ́n, APEP, aṣàfikún aṣáájú ọ̀rọ̀-ìṣe tàbí atẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe lè jẹ́ méjì tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ nínú ìhun àpólà ìṣe.

Ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí aláìgbàmúpé kìí gba ẹ̀pọ́n aṣàmúpé nínú ìhun àpólà ìṣe.

Commented [O.J85]: tàárà

### ÌGBÉLÉWỌ̀N AKẸ́KỌ̀Ọ́

Gbìyànjú láti ṣàlàyé bí àwọn ẹ̀pọ́n inú àpólà ìṣe ṣe tẹ̀lé ara wọn.

### 4.2 Ìrísí APIṢ Ọlọ́rọ̀-Ìṣe Ẹlẹ́là

Àwọn Ọ̀rọ̀-Ìṣe (IṢ) ẹlẹ́là ni Ọ̀rọ̀-Ìṣe (IṢ) tí a máa ń pín níyà láti ki àbọ̀ tí ó gbà bọ̀ ní àárín. Àpẹẹrẹ irú IṢ bẹ́ẹ̀ ni ***bà... jẹ́, gbà... gbọ́, rẹ́... jẹ, yí...po, pa...tì, bá...mu, pa...dà,*** abbl. Díẹ̀ lára àpẹẹrẹ APIṢ tí Ọ̀rọ̀-Ìṣe (IṢ) ti jẹ yọ ni wọ́n ní ìsàlẹ̀ yìí.

10a. Ó [**ba iṣu náà jẹ́**]
b. Ọkọ̀ yẹn ti [**pa àwọ̀ dà**]
d. Olú kò [**gba Òjó gbọ́**]
e. O [**rẹ́ ọmọ náà jẹ**]

Commented [O.J86]: iṣẹ́

Ìrísí àwọn APIṢ tí mo fi sí ìkámọ́ ní àpẹẹrẹ òkè wọ̀nyí fara jọ ìrísí APIṢ tí ó gba àmúpé méjì. Ṣùgbọ́n ìyàtọ̀ tí ó wà láàárín wọn ni pé, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ìhun wọn ní APIṢ kékeré àti APIṢ, IṢ kékeré àti IṢ ni wọ́n ní wúnrẹ̀n afarahàn alâìfarasin, yàtọ̀ sí ibi tí IṢ kékeré ti ní wúnrẹ̀n afarasin.

11a




b




**ÌGBÉLÉWỌ̀N AKẸ́KỌ̀Ọ́**
Kọ àpẹẹrẹ ọ̀rọ̀-ìṣe ẹ̀lẹ́là tí o mọ̀.

## 5.0 ÌSỌNÍṢÓKÍ

Onírúurú ni ẹ̀pọ́n tí ó wà nínú ìhun àpólà ìṣe. Àmọ́ bí wọ́n ti tó yìí, ó ní bí wọ́n ṣe tẹ̀lé ara wọn. Ní ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, mo ṣàlàyé bí àwọn ẹ̀pọ́n inú ìhun àpólà ìṣe ṣe tẹ̀lé àra wọn. Mo tún ṣàlàyé ìrísí àpólà ìṣe tí ó ní ọ̀rọ̀ ìṣe ẹlẹ́là. Ìlànà APIS méjì (ìyẹn APIṢ kékeré áti APIṢ ńlá) náà ni a lò láti fi ìhun àpólà ìṣe ọlọ́rọ̀ ìṣe ẹlẹ́là hàn.

## 6.0 IṢẸ́ ṢÌṢE

Gbiyànjú láti fi ìhun àpólà ìṣe inú gbólóhùn ìsàlẹ̀ yìí hàn nínú àwòrán atọ́ka igi.

Bàbá [**rẹ́ ọmọ náà jẹ**]

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ/ÀWỌN ÌWÉ FÙN KÍKÀ

Awóbùlúyì, O. 1978. *Essentials of Yorùbá Grammar,* Ìbàdàn: UPL.
Awobuluyi, O. 1988. *Èdè Ìperí Yorùbá*: *Apá kejí*, Lagos: NERDC
Awóbùlúyì, O. 2001a. "Aró̩pò–Orúko̩ Kúkúrú E̩ni–Ké̩ta E̩yo̩ As̩olùwà" *Yorùbá,* Vol. 2, No. 1 pp 1-8
Awóbùlúyì, O. 2001b. "Òte–Ìlò Àwo̩n Aró̩pò–Orúko̩ Kúkúrú" Bébà tí a kà ní Àpérò E̩gbé̩ Onímò̩ ÈdèYorùbá: Yunifásítì ìlú Eko.
Awobuluyi, O. 2008. *È̩kó̩ Ís̩è̩dá-Ò̩rò̩ Yorùbá*, Akure̩: Montem Paperbacks
Awobuluyi, O. 2013. *È̩kó̩ Gírámà Èdè Yorùbá*, Oshogbo: Montem Paperbacks
Bámgbó̩s̩é, A̩. 1967. *A Short Yorùbá Grammar,* Ìbàdàn: HEB.
Bámgbó̩s̩é, A̩. 1990. *Fonó̩ló̩jì àti Gírámà Yorùbá*. Ìbàdàn: UPL.
Oyetade, S.O. 1995. *Yorùbá Grammar I*. Ibadan, Centre for External Studies, UI.
Táíwò, O. 2003. Tense and Aspect in Ào. Nínú Ndimele O.M (olótùú) *Languages and Linguistics in Nigeria.* A Festscrist in Honour of Kay williamson.
Taiwo, O. 2007. Short Subject Pronoun in the Ào dialect of Yorùbá. *JOLAN: Journal of Linguistic Association of Nigeria (JOLAN)* No 10 o.i. 67 – 86
Taiwo, O. 2008a. *Basic Concepts in Grammar*: Ibadan, DLC, UI
Taiwo, O. 2008b. *Basic Grammar*: Ibadan, DLC, UI

## MÓDÙ 5: ÌHUN ÀPÓLÀ AṢẸ̀PỌ́N (APEP) ÀTI ÌHUN ÀPÓLÀ APÀRÍSÍDÀ (APAPR)

Àfojúsùn módù yìí ni láti ṣàlàyé ìhun Àpólà Aṣẹ̀pọ́n (APEP) àti Ìhun Àpólà Apàrísídà (APAPR). Ó ti ń kà nípa Àpólà Aṣẹ̀pọ́n (APEP) ní àwọn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ àtẹ̀yìnwá nígbà tí mò ń ṣàlàyé ẹ̀pọ́n nínú àpólà ìṣe, nítorí náà, kò jẹ́ tuntun sí ọ. Àmọ́, ni módù yìí mà á ṣàlàyé ìhun Àpólà Aṣẹ̀pọ́n (APEP) gan-an fún ọ. Láìṣe-àni-àni, Ọ̀rọ̀-aṣẹ̀pọ́n ni orí nínú àpólà aṣẹ̀pọ́n. Ọ̀rọ̀-aṣẹ̀pọ́n tí ó jẹ́ orí yìí sì lè gbá àbọ̀ tàbí kí ó dá wà láì gba àbọ̀ nínú ìhun àpólà rẹ.

Commented [O.J87]: Ọ̀rọ̀-àpọ́nlé

Àpólà Apàrísídà (APAPR) ni óṣeése kí ó ṣàjòjì sí ọ nítorí mi ò tíì mẹ́nu bà á nínú ìwé yìí. Àpólà Apàrísídà (APAPR) ni ó dúró gẹ́gẹ́ bí gbólóhùn. Ní ìgbà tí à ń ṣàlàyé ìhun àpólà lóríṣiríṣi, gbogbo wọn ni wọ́n ní orí, àti pé orúkọ orí wọn ni a fi ń pe àpólà kọ̀ọ̀kan. Báwo ni ti gbólóhùn yó ṣe wá máa yàtọ̀?. Níwọ̀n ìgbà tó jẹ́ pé ìlànà kòsí bi ọ̀bọ ṣe ṣe orí tí ìnàkí kò ṣe ni a fẹ́ gùn lé, ó jásí pé gbólóhùn náà yẹ kó ní orí. Ohun tí ó bí Àpólà Apàrísídà (APAPR) nìyí. Àwọn onímọ̀ fi yé wa pé Ọ̀rọ̀-Apàrísídà (APR) ló ń kó ipa pàtàkì láti so APOR áti APIṢ pọ̀ di gbólóhùn. Nítorí náà, ọ̀rọ̀-apàrísídà (APR) ni orí gbólóhùn, ti a sì wá àgbékalẹ̀ odidi gbólóhùn bíi Àpólà Apàrísídà (APAPR). Ní mòdú yìí, mà á ṣàlàyé Ọ̀rọ̀-Apàrísídà (APR), mà á sì ṣàlàyé fọ́nrán-Ìhun Àpólà Apàrísídà (APAPR).

Ní ṣókí, ní mòdú yìí, wà á kọ́ nípa àwọn Ọ̀rọ̀-Aṣẹ̀pọ́n (EP) àti bí a ṣe ń lo òun àti àbọ̀ rẹ gẹ́gẹ́ bíi Àpólà Aṣẹ̀pọ́n (APEP). Lẹ́yìn náà wà á kọ́ àwọn Ọ̀rọ̀-Apàrísídà (APR) ní èdè yorùbá, wà á tún kọ́ nípa fọ́nrán-ìhun Àpólà Apàrísídà (APAPR) àti bí a ṣe n lo Àpólà Apàrísídà (APAPR) fún gbólóhùn ní àwòrán atọ́ka-igi. Àwọn àkòrí wọ̀nyí ni o máa kà ní módù yìí:

Ìpín 1: Ọ̀rọ̀-Aṣẹ̀pọ́n (EP)
Ìpín 2: Àpólà Aṣẹ̀pọ́n (APEP)
Ìpín 3: Ọ̀rọ̀-Apàrísídà (APR)
Ìpín 4: Fọ́nrán-Ìhun Àpólà Apàrísídà (APAPR)

### ÌPÍN 1: Ọ̀RỌ̀-AṢẸ̀PỌ́N (EP)

**1.0** Ìfáàrà
**2.0** Èròǹgbà àti Àfojúsùn
**3.0** Ìbéèrè Ìṣáájú
**4.0** Àkóónú Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
**4.1** Oríki ọrọ̀-Aṣẹ̀pọ́n (EP)
**4.2** Ọ̀rọ̀-aṣẹ̀pọ́n (EP) agbàbọ̀
**4.3** Ọ̀rọ̀-aṣẹ̀pọ́n aláìgbàbọ̀
**5.0** Ìsọníṣókí
**6.0** Iṣẹ́ Ṣíṣe
**7.0** Ìwé Ìtọ́kasí/Àwọn Ìwé Fùn Kíkà


## 1.0. ÌFÁÁRÀ

Ní ìdánilẹ́kọ̀ọ́ àtẹ̀yìnwá, a rí i pé àpólà aṣẹ̀pọ́n máa ń jẹyọ nínú àpólà ìṣe. Ọ̀rọ̀-aṣẹ̀pọ́n ni orí inú àpólà aṣẹ̀pọ́n. Àmọ́, oríṣirísi ni ọ̀rọ̀-aṣẹ̀pọ́n nínú èdè Yorùbá. Àwọn ọ̀rọ̀-aṣẹ̀pọ́n kan wà tí wọ́n jẹ́ agbàbọ̀, àwọn yòókù sì jẹ́ aláìgbàbọ̀. Ní ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, mà á ṣàlàyé ọ̀rọ̀-aṣẹ̀pọ́n àti àwọn ẹ̀yà rẹ̀ tí ó wà nínú èdè Yorùbá.

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN

Lẹ́yìn tí ó bá ti ka ìpín yìí tán, wàá lè mọ ọ̀rọ̀-aṣẹ̀pọ́n àti àwọn ẹ̀yà rẹ̀ tí ó wà nínú èdè Yorùbá.

## 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢÁÁJÚ

Kọ òrò aṣẹ̀pọ́n márùn-un tí o mọ̀.

## 4.0 ÀKÓÓNÚ ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

### 4.1 Oríki Ọ̀rọ̀-Aṣẹ̀pọ́n (EP)

Ọ̀rọ̀-Aṣẹ̀pọ́n (EP) jẹ́ ìsọ̀rí-ọ̀rọ̀ tí ó wà lára àwọn ìsọ̀gbè nínú ìhun àpólà ìṣe, àpólà tí àwọn ọ̀rọ̀-aṣẹ̀pọ́n ti jẹ́ orí ni Àpólà Aṣẹ̀pọ́n (APEP). A lè lo àwọn àpólà aṣẹ̀pọ́n gẹ́gẹ́ bí ẹ̀pọ́n aṣàfikún aṣáájú tàbí atẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí, bákan náà, a lè lò wọ́n gẹ́gẹ́ bí ẹ̀pọ́n aṣàmúpé atẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe aṣorí pẹ̀lú. A lè ki ọ̀rọ̀-aṣẹ̀pọ́n gẹ́gẹ́ bí ***ọ̀rọ̀ tí ó ń pọ́n ọ̀rọ̀ tàbí ìsọ mìíràn nínú ẹ̀hun èdè Yorùbá.*** A máa ń lo ọ̀rọ̀-aṣẹ̀pọ́n aṣàfikún àti ọ̀rọ̀-aṣẹ̀pọ́n aṣàmúpé láti pọ́n ọ̀rọ̀-ìṣe nínú ẹ̀hun àpólà ìṣe. Ṣùgbọ́n a tún lè lo ọ̀rọ̀-aṣẹ̀pọ́n aṣàfikún láti pọ́n odindi gbólóhùn tàbí láti pọ́n ẹ̀yán nínú ìhun àpólà orúkọ.

### ÌGBÉLÉWỌ̀N AKẸ́KỌ̀Ọ́

Ki oríki ọ̀rọ̀-aṣẹ̀pọ́n

### 4.2 Ọ̀rọ̀-Aṣẹ̀pọ́n (EP) Agbàbọ̀

Ọ̀rọ̀-Aṣẹ̀pọ́n (EP) agbàbọ̀ ni wọ́n máa ń jẹ yọ tàbí tí a máa ń lò ṣáájú ọ̀rọ̀-orúkọ tàbí arọ́pò orúkọ láti ṣàfihàn àyè, ipò, ìgbà tàbí ọ̀nà tí a ń gbà ṣe ǹǹkan. Èyí túmọ̀ sí pé ọ̀rọ̀ tí ó ní àbùdá pé ó máa ń jẹ yọ ṣáájú ọ̀rọ̀-orúkọ (tàbí arọ́pò orúko) ní ọ̀rọ̀ aṣẹ̀pọ́n agbàbọ̀ jẹ́. Ọ̀rọ̀-orúkọ tí ó tẹ̀lé ọ̀rọ̀-aṣẹ̀pọ́n agbàbọ̀ ni àmúpé fún ọ̀rọ̀ aṣẹ̀pọ́n náà. Dandan lówò orí túlàsì laṣọ ìbora ni àmúpé yìí jẹ́ fún irú ọ̀rọ̀-aṣẹ̀pọ́n bẹ́ẹ̀ ní èdè Yorùbá. Àpẹẹrẹ ọ̀rọ̀-aṣẹ̀pọ́n agbàbọ́ ní mo kọ ní àkọhàn-adẹ̀gbẹ nínú àwọn gbólóhùn ìsàlẹ̀ wọ̀nyí.

| | | |
|---|---|---|
| Ọpẹ́ ***bá*** Òjó se ọbẹ̀. | Ó ***fi*** ẹnu wa ọkọ̀. | Mo ***ti*** Ìbàdàn lọ ṣe iṣẹ́ oko |
| Ó lọ ***sí*** ilé. | Ó wà ***ní*** Ìbàdàn. | Ó kọrin ***pẹ̀lú*** túlàsì. |
| Ó ta aṣọ ***fún*** mi. | Pè é ***fún*** mi. | Ó ń sọ̀rọ̀ ***bí*** ọ̀dẹ̀. |
| Ó gbà ***torí*** owó. | Kò sí olùgbèjà ***àfi*** Olọ́run. | Mo máa dé ***títí*** ọ̀la |

**Commented [O.J88]:** Ǹjẹ́ kò ní í rúni lójú tí a bá pe àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyẹn ní ọ̀rọ̀-aṣẹ̀pọ́n agbàbọ́ nígbà tó jẹ́ wí pé ọ̀rọ̀-atọ́kùn pọ́nńbélé ni wọ́n?

Àwọn ọ̀rọ̀-aṣèpọ́n agbàbọ̀ tí wọ́n wà nínú àwọn àpẹẹrẹ òkè wọ̀nyí ni **sí, ní, pẹ̀lú, fún, bá, ti fi, bí, torí, àfi** àti **títí.** Púpọ̀ nínú àwọn ọ̀rọ̀-aṣèpọ́n agbàbọ̀ wọ̀nyí ni a máa ń pé ní ọ̀rọ̀-atọ́kùn. Ṣùgbọ́n gẹ́gẹ́ bí ìlò tàbí iṣẹ́ tí wọ́n ń ṣe nínú ẹhun, ọ̀rọ̀-aṣèpọ́n agbàbọ̀ ni a máa kà wọ́n sí.

Orísi ọ̀rọ̀-aṣèpọ́n agbàbọ̀ mìíràn ni ọ̀rọ̀ aṣèpọ́n alákànpọ̀. Àbùdá àwọn ọ̀rọ̀-aṣèpọ́n agbàbọ̀ wọ̀nyí ni pé wọ́n jẹ́ ìkànpọ̀ ọ̀rọ̀-aṣèpọ́n àti àbọ̀ rẹ̀.

Ó rí i ***nínú*** àwọn ilé ńlá ìsàlẹ̀ yìí.
Ó tí lọ ***síwájú (ṣáájú)*** yín.
Ó wà ***lẹ́yìn*** ilè yẹn.
Ó lọ ***síbí*** ayẹyẹ náà.
Kò sí ***lára*** àwọn akẹ́kọ̀ọ́ náà

Nínú àwọn gbólóhùn òkè wọ̀nyí, àwọn ọ̀rọ̀-aṣèpọ́n agbàbọ̀ ni mo kọ ní àkọhàn-adègbẹ́.

**ÌGBÉLÉWỌ̀N AKẸ́KỌ̀Ọ́**
Kọ àpẹẹrẹ ọ̀rọ̀-aṣèpọ́n (EP) agbàbọ̀

### 4.3 Ọ̀rọ̀-Aṣèpọ́n Aláìgbàbọ̀

Yàtọ̀ sí àwọn ọ̀rọ̀-aṣèpọ́n agbàbọ̀ tí mo ṣàlàyé lókè, àwọn ọ̀rọ̀-aṣèpọ́n mìíràn wà tí wọ́n máa ń dá wà láìgba jẹ́ pé ọ̀rọ̀ mìíràn jẹ yọ tẹ̀lé wọn gẹ́gẹ́ bí àbọ̀ wọn. Irú àwọn ọ̀rọ̀-aṣèpọ́n bẹ́ẹ̀ ni a ń pè ní ọ̀rọ̀-aṣèpọ́n aláìgbàbọ̀. Wọ́n lè pọ́n ọ̀rọ̀-ìṣe, ẹ̀yán tàbí odindi gbólóhùn gẹ́gẹ́ bí wọ́n ṣe jẹ yọ nínú àwọn gbólóhùn ìsàlẹ̀ wọ̀nyí.

Commented [O.J89]: láìjẹ́

Àgbàdo sísè náà gbóná **fòfò.**
Aṣọ náà pupa **fòò.**
Ọmọ náà ***ṣe*** sọ̀rọ̀ ***bẹ́ẹ̀.***
Ẹ máà ***wulẹ̀*** pè é, kò ní yọjú.
***Àní*** ọmọ náà ti dé
***Bẹ́ẹ̀ ni***, ẹ máa lọ
ọwọ́ tutù ***nini.***
ìjòyè mẹ́rin ***péré***

Ní àwọn àpẹẹrẹ òkè wọ̀nyí, àwọn ọ̀rọ̀-aṣèpọ́n ni **fòfò, fòò, ṣe, bẹ́ẹ̀** àti **wulẹ̀** pọ́n ọ̀rọ̀-ìṣe; **àní** àti **bẹ́ẹ̀ ni** jẹ́ ọ̀rọ̀-aṣèpọ́n tí wọ́n ń pọ́n odindi gbólóhùn nígbà tí ọ̀rọ̀-aṣèpọ́n **nini** àti **péré** pọ́n ẹ̀yán aṣàpèjúwe àti ẹ̀yán aṣòǹkà. Mo máa tẹ̀síwájú láti ṣàlàyé wọn báyìí.

**Ọ̀rọ̀-Aṣèpọ́n Aláìgbàbọ̀ Aṣèpọ́n Ọ̀rọ̀-Ìṣe**
Oríṣi ọ̀rọ̀-aṣèpọ́n aláìgbàbọ̀ aṣèpọ́n ọ̀rọ̀-ìṣe méjì ni a lè yà sọ́tọ̀. Àkọ́kọ́ ni àwọn ọ̀rọ̀-aṣèpọ́n aṣàmúpé tí wọ́n jẹ́ kànńpá fún ọ̀rọ̀-ìṣe, ìkejì sì ni ọ̀rọ̀-aṣèpọ́n aṣàfikún tí wọn kìí ṣe kànńpà, ṣùgbọ́n tí wọ́n jẹ́ ìwọ̀fún fún ọ̀rọ̀-ìṣe

Commented [O.J90]: kì í

Àwọn ọ̀rọ̀-ìṣe agbàmúpé kan máa ń gba ọ̀rọ̀-aṣèpọ́n gẹ́gẹ́ bí àmúpé. Dandan lọwọ́-orí, túlàsí laṣọ ìbora ni ọ̀rọ̀-aṣèpọ́n jẹ́ fún ọ̀rọ̀-ìṣe bẹ́ẹ̀. Bí ọ̀rọ̀-ìṣe tí a ń sọ yìí kò bá gba ọ̀rọ̀-aṣèpọ́n gẹ́gẹ́ bí àmúpé, ìtumọ̀ irú ọ̀rọ̀-ìṣe náà yòó yàtọ̀ sí èyí tí a ní lọ́kàn tàbí kí ọ̀rọ̀-ìṣe náà máà ní ìtumọ̀ rárá. Àpẹẹrẹ ọ̀rọ̀-aṣèpọ́n bẹ́ẹ̀ ni ***sánsán, yòò*** àti ***fáfá*** gẹ́gẹ́ bí wọ́n ṣe jẹ yọ nínú àwọn gbólóhùn ìsàlẹ̀ wọ̀nyí.

Ọbẹ̀ náà ta ***sánsán.***
Aṣọ náà bẹ́ ***yòò.***

Ọmọ náà já ***fáfá.***

Àbùdá àwọn ọ̀rọ̀-aṣẹ̀pọ́n yìí ni pé wọ́n máa ń jẹ yọ tẹ̀lé ọ̀rọ̀-ìṣe tí wọ́n ń pọ́n nínú ìhun àpólà ìṣe. Àpẹẹrẹ àwọn ọ̀rọ̀-aṣẹ̀pọ́n tí wọ́n jẹ́ ìwọ̀fún fún ọ̀rọ̀-ìṣe ni wọ́n wà nínú àwọn gbólóhùn ìsàlẹ̀ wọ̀nyí.

a. Wọ́n ***tún*** pariwo sí i.
   Mo ti ***kọ́kọ́*** gbọ́ ariwo wọn.
   Ẹ ***pàpà*** fi ìyà jẹ é.
   Wọ́n ***kúkú*** sọ bẹ́ẹ̀.

b. Adé sùn ***fọnfọn.***
   Ó gun igi ***kìàkìà***
   Ọbẹ̀ náà dùn ***tó***
   Ìṣẹ̀lẹ̀ náà burú ***jáì***
   Mi ò gbọ́ ọ̀rọ̀ burúkú yẹn ***rí***

d. Mo ***kàn dédé*** gbọ́ tí wọ́n ń kan ilẹ̀kùn
   O ***gbọ́dọ̀ tètè*** parí iṣẹ́ yẹn.

**Ọ̀rọ̀-Aṣẹ̀pọ́n Aláìgbàbọ̀ Aṣẹ̀pọ́n Gbólóhùn**

Ẹyà ọ̀rọ̀-aṣẹ̀pọ́n aláìgbàbọ̀ mìíràn ni àwọn ọ̀rọ̀-aṣẹ̀pọ́n tí wọ́n máa ń pọ́n odindi gbólóhùn. Ìbẹ̀rẹ̀ gbólóhùn ni ọ̀pọ̀ àwọn ọ̀rọ̀-aṣẹ̀pọ́n gbólóhùn wọ̀nyí ti máa ń jẹ yọ. Àpẹẹrẹ wọn ni **àní, kódà, bẹ́ẹ̀ ni, yéèpà, *bẹ́ẹ̀ kọ́,* ẹn ẹn,** abbl., gẹ́gẹ́ bí wọ́n ṣe wà nínú gbólóhùn ìsàlẹ̀ wọ̀nyí.

***Àní*** ọmọ náà ti dé.
***Bẹ́ẹ̀ ni***, ẹ máa lọ.
***Kódà*** mo rí wọn.
***Ẹn ẹn*** kí lẹ fẹ́ ṣe fún mi?
***Yéèpà,*** àkàrà tú sépo.
***Bẹ́ẹ̀ kọ́,*** n ò fara mọ́ ọ̀rọ̀ yẹn.

Àmọ́ ṣá, a rí àwọn kan tí wọ́n máa ń jẹ yọ ní ìparí gbólóhùn. Àwọn ni **ṣá, kẹ̀, jàre, pàápàá, pẹ̀lú, mànà,** abbl., gẹ́gẹ́ bí wọ́n ṣe jẹ yọ nínú àwọn gbólóhùn ìsàlẹ̀ wọ̀nyí.

Ọmọ náà ti kú ***ṣá.***
Ẹ máà dá wọn lóhùn ***jàre.***
Mo gbọ́ ọ̀rọ̀ rẹ ***jàre.***
Ọpẹ́ sọ ọ̀rọ̀ náà fún mi **pẹ̀lú.**
Mo ti gbọ́ ***sẹ́.***
Bàbá rẹ̀ ti wẹ̀ ***pàápàá.***
Ó ṣe iṣẹ́ náà ***mànà.***
Ìyàwó rẹ̀ ti sá lọ ***kẹ̀***?
Ìyá àgbà ti kú ***kẹ̀***?

**Commented [O.J91]:** Ó dà bi ẹni wí pé **Bàbá rẹ̀ ti wẹ̀ *pàápàá*** kò já gaara. Ṣé báyìí: **Bàbá rẹ̀ *pàápàá* ti wẹ̀** kọ́ ló yẹ kó jẹ́?

Ó dàbí ẹni pé ìtẹnumọ́ ní a máa ń lo àwọn ọ̀rọ̀-aṣẹ̀pọ́n gbólóhùn wọ̀nyí fún nínú gbólóhùn gẹ́gẹ́ bí àwọn àpẹẹrẹ òkè wọ̀nyí ṣe fi hàn. Àmọ́ ṣá, ó dàbí ẹni pé a lè lo **kẹ̀** fún ìbéèrè pẹ̀lú ìtẹnumọ́ tí a lò ó fún. Èyí ni ó fojú hàn ní àwọn àpẹẹrẹ méjì tí wọ́n gbẹ́yìn lókè.

Ẹ̀yà ọ̀rọ̀-asẹ̀pọ́n gbólóhùn mìíràn ni àwọn tí wọ́n lè jẹ yọ ní ìbẹ̀rẹ̀ tàbí ní ìparí gbólóhùn. Ìyẹn ni pé, ó ṣe é ṣe kí a lo irú àwọn ọ̀rọ̀-asẹ̀pọ́n gbólóhùn ní ìbẹ́rẹ́ gbólóhùn tàbí kí á lò wọ́n ní ìparí gbólóhùn. Àpẹẹrẹ wọn ni wọ́n wà nínú àwọn gbólóhùn ìsàlẹ̀ wọ̀nyí.

***Síbẹ̀/Síbẹ̀síbẹ̀*** Olúwa ń bẹ pẹ̀lú mi.
Olúwa ń bẹ pẹ̀lú mi ***síbẹ̀/síbẹ̀síbẹ̀.***

***Jọ̀ọ́/jọ̀wọ́*** gbọ́ ọ̀rọ̀ ẹnu mi.
Gbọ́ ọ̀rọ̀ ẹnu mi ***jọ̀ọ́/jọ̀wọ́***

**Ọ̀rọ̀-Asẹ̀pọ́n Aláìgbàbọ̀ Asẹ̀pọ́n Ẹ̀yán**
Àwọn ọ̀rọ̀-asẹ̀pọ́n aláìgbàbọ̀ kan máa ń pọ́n ẹ̀yán asàpèjúwe àti ẹ̀yán asọ̀ǹkà nínú àpólà orúkọ. Àpẹẹrẹ irú àwọn ẹ̀pọ́n bẹ́ẹ̀ ni **péré, fíofío, níní** àti **fòfò** gẹ́gẹ́ bí wọ́n ṣe jẹ yọ nínú àwọn gbólóhùn ìsàlẹ̀ wọ̀nyí.

àgbàdo gbígbóná ***fòfò***
Omi tutù ***nini***
ilé gíga ***fíofío***
ìyàwó kan ***ṣoṣo***
iṣu méjì ***péré***

Ní àwọn àpẹẹrẹ mẹ́ta àkọ́kọ́, àwọn ọ̀rọ̀-asẹ̀pọ́n **fòfò, nini** àti **fíofío** ń pọ́n àwọn ẹ̀yán asàpèjúwe **gbígbóná, tútú** àti **gíga.** Ní àwọn àpẹẹrẹ méjì ìgbẹ̀yìn, àwọn ọ̀rọ̀-asẹ̀pọ́n **ṣoṣo** àti **péré** ń pọ́n àwọn ẹ̀yán asọ̀ǹkà **kan** àti **méjì.**

Ní ìgùnlẹ̀, àwọn ẹ̀yà ọ̀rọ̀-asẹ̀pọ́n tí mo jírórò lé lórí ni mo fi hàn ní àwòrán ìsàlẹ̀ yìí.

**Ẹ̀yà Ọ̀rọ̀-Asẹ̀pọ́n**




**ÌGBÉLÉWỌ̀N AKẸ́KỌ̀Ọ̀**
Kọ àpẹẹrẹ oríṣi ọ̀rọ̀-asẹ̀pọ́n (EP) aláìgbàbọ̀ tí o mọ̀.

**5.0 ÌSỌNÍṢÓKÍ**

Ọ̀rọ̀-aṣẹ̀pọ́n ni ọ̀rọ̀ tí ó ń pọ́n ọ̀rọ̀ tàbí ìsọ mìíràn nínú ẹ̀hun èdè Yorùbá. Ọ̀rọ̀-aṣẹ̀pọ́n ni orí inú àpólà aṣẹpọ́n. Ọ̀rọ̀-aṣẹ̀pọ́n lè jẹ́ agbàbọ̀ tàbí aláìgbàbọ̀. A lè lo Ọ̀rọ̀-Aṣẹ̀pọ́n Aláìgbàbọ̀ láti pọ́n ọ̀rọ̀ ìṣe, odidi gbólóhùn tàbí ẹ̀yán lé nínú ẹ̀hun èdè Yorùbá.

**6.0 IṢẸ́ ṢÌṢE**

Kọ òrò-aṣẹ̀pọ́n agbàbọ̀ tàbí aláìgbàbọ̀ márùn-un márùn-un tí o mọ̀

**7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ/ÀWỌN ÌWÉ FÙN KÍKÀ**


Awóbùlúyì, O. 1978. *Essentials of Yorùbá Grammar,* Ìbàdàn: UPL.

Awobuluyi, O. 1988. *Èdè Ìperí Yorùbá*: *Apá kejí*, Lagos: NERDC

Awóbùlúyì, O. 2001a. "Arọ́pò–Orúkọ Kúkúrú Ẹni–Kẹ́ta Ẹyọ Aṣolùwà" *Yorùbá,* Vol. 2, No. 1 pp 1-8

Awóbùlúyì, O. 2001b. "Òte–Ìlò Àwọn Arọ́pò–Orúkọ Kúkúrú" Bébà tí a kà ní Àpérò Ẹgbẹ́ Onímọ̀ ÈdèYorùbá: Yunifásítì ìlú Eko.

Awobuluyi, O. 2008. *Ẹ̀kọ́ Íṣẹ̀dá-Ọ̀rọ̀ Yorùbá,* Akurẹ: Montem Paperbacks

Awobuluyi, O. 2013. *Ẹ̀kọ́ Gírámà Èdè Yorùbá*, Oshogbo: Montem Paperbacks

Bámgbóṣé, Ạ. 1967. *A Short Yorùbá Grammar,* Ìbàdàn: HEB.

Bámgbóṣé, Ạ. 1990. *Fonọ́lọ́jì àti Gírámà Yorùbá*. Ìbàdàn: UPL.

Oyetade, S.O. 1995. *Yorùbá Grammar I*. Ibadan, Centre for External Studies, UI.

Táíwò, O. 2003. Tense and Aspect in Ào. Nínú Ndimele O.M (olótùú) *Languages and Linguistics in Nigeria.* A Festscrist in Honour of Kay williamson.

Taiwo, O. 2007. Short Subject Pronoun in the Ào dialect of Yorùbá. *JOLAN: Journal of Linguistic Association of Nigeria (JOLAN)* No 10 o.i. 67 – 86

Taiwo, O. 2008a. *Basic Concepts in Grammar*: Ibadan, DLC, UI

Taiwo, O. 2008b. *Basic Grammar*: Ibadan, DLC, UI

## ÌPÍN 2: ÀPÓLÀ AṢẸ̀PỌ́N (APEP)

**1.0** Ìfáárà
**2.0** Èròǹgbà àti Àfojúsùn
**3.0** Ìbéèrè Ìṣáájú
**4.0** Àkóónú Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
**4.1** Àpólà aṣẹ̀pọ́n (APEP)
**4.2** Àpólà aṣẹ̀pọ́n alábọ̀
**4.3** Àpólà aṣẹ̀pọ́n aláìlábọ̀
**5.0** Ìsọníṣókí
**6.0** Iṣẹ́ Ṣíṣe
**7.0** Ìwé Ìtọ́kasí/Àwọn Ìwé Fún Kíkà

### 4.0 ÀKÓÓNÚ ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

### 4.1 Àpólà Aṣẹ̀pọ́n (APEP)

Àpólà aṣẹ̀pọ́n (APEP) ni àpólà tí ọ̀rọ̀-aṣẹ̀pọ́n jẹ́ orí rẹ̀. Àwọn ọ̀rọ̀-aṣẹ̀pọ́n kan kò lè dá wà nínú àpólà aṣẹ̀pọ́n, wọ́n gbọ́dọ̀ gba àpólà orúkọ gẹ́gẹ́ bí àbọ̀, àmọ̀ àwọn kan máa ń dá wà láì gba àbọ̀. Fún ìdí èyí, oríṣi àpólà aṣẹ̀pọ́n méjì ni a lè yà sọ́tọ̀. Àwọn ni àpólà aṣẹ̀pọ́n alábọ̀ àti àpólà aṣẹ̀pọ́n aláìlábọ̀.

**ÌGBÉLÉWỌ̀N AKẸ́KỌ̀Ọ̀**

Ki oríkì àpólà aṣẹ̀pọ́n (APEP)

### 4.2 Àpólà Aṣẹ̀pọ́n Alábọ̀

Àpólà aṣẹ̀pọ́n alábọ̀ ni àwọn kan ń pè ní àpólà atọ́kùn. Ìsògbè tí ó wa nínú ìhun àpólà aṣẹ̀pọ́n ni àpólà orúkọ, ọ̀ranyán sì ni ìsògbè yìí. Àpẹẹrẹ àpólà aṣẹ̀pọ́n ní a kọ ní àkọhàn ní àwọn gbólohùn ìsàlẹ̀ wọ̀nyí.

Olú **bá ọmọ náà** ra aṣọ **ní ọjà.**
Wọ́n pè é **fún mi**
Ò **bá mi** fi ọkọ̀ **ti ibi** kó iṣu náà lọ **sí ọjà.**
Ó wà **lọ́hùn-ún yẹn**.
Ó **fi ẹnu** wa ọkọ̀.
Ó ń rì **bí ọba.**
Ó rí i **nínú ilé yìí.**
Mo ra aṣọ náà **fún wọn**
Ọmọ náà ń sọ̀rọ̀ **pẹ̀lú ẹ̀rù.**
Ó tí lọ **síwájú (ṣáájú) yín.**
A kọrin **[pẹ̀lú agidi] [nínú ilé ìjọ́sìn]**
Mo lè ṣe báyìí **di ọ̀la**.
Olùgbèjà kan kò sí **àfi Ọlọ́run.**

Àwọn tí mo kọ ní àkọhàn nínú àwọn gbólóhùn àpẹẹrẹ òkè wọ̀nyí ni àpólà aṣẹ̀pọ́n alábọ̀. Ìrísí kan náà wọ́n ní, ìyẹn orí àti àpólà orúkọ àmúpé tí ó jẹ́ arábìnrin fún orí gẹ́gẹ́ bí mo ṣe fi hàn ní ìsàlẹ̀ yìí.

Commented [O.J92]: Ìrísí kan náà **ni** wọ̣n ní







**ÌGBÉLÉWỌ̀N AKẸ́KỌ̀Ọ́**
Kọ àpẹẹrẹ Àpólà Aṣẹ̀pọ́n Alábọ̀ márùn-ún

### 4.3 Àpólà Aṣẹ̀pọ́n Aláìlábọ̀

Ní ti àpólà aṣẹ̀pọ́n aláìlábọ̀, ọ̀rọ̀-aṣẹ̀pọ́n tí ó jẹ́ orí níkan ni ó wà nínú ìhun rẹ̀, kò sí àbọ̀ tàbí wúnrẹ̀n mìíràn. Àpẹẹrẹ díẹ̀ ni ó wà ní ìsàlẹ̀ yìí.

> Adé sùn ***fọnfọn.***
> Ó ké ***tagbára tagbára.***
> Wọ́n ti ***bábá*** ṣe ìpinnu náà.
> Ọmọ náà ***tètè*** dàgbà.
> O ***gbọ́dọ̀ tètè*** parí iṣẹ́ yẹn.
> Obìnrin náà ***wà túbọ̀*** tẹsẹ̀ mọ́ ìrìn rẹ̀.
> Wọ́n ***mà lè tètè*** wáà.
> Kò ***tiẹ̀ lè nìkan*** gbé ẹrù yẹn.

Àpólà aṣẹ̀pọ́n aláìlábọ̀ ni ó wà nínú àwọn àpẹẹrẹ òkè wọ̀nyí, àwọn ni mo kọ ní àkọhàn-adẹ̀gbẹ́. Ìrísí kan náà ni wọ́n ní, gẹ́gẹ́ bí mo ṣe fi hàn ní ìsàlẹ̀ yìí.

APEP
|
EP[I]
|
EP
|
bàbà/fọnfọn/tagbára tagbára /gbọ́dọ̀ /tètè /túbọ̀

**ÌGBÉLÉWỌ̀N AKẸ́KỌ̀Ọ́**

Kọ àpẹẹrẹ Àpólà Aṣẹ̀pọ́n aláìlábọ̀ márùn-ún

## 5.0 ÌSỌNÍṢÓKÍ

Ọ̀rọ̀-aṣẹ̀pọ́n ni orí inú àpólà aṣẹpọ́n. Àwọn ọ̀rọ̀-aṣẹ̀pọ́n kan kò lè dá wà nínú àpólà aṣẹ̀pọ́n, àfi bí wọ́n bá gba àpólà orúkọ gẹ́gẹ́ bí àbọ̀. Àmọ̀ àwọn kan máa ń dá wà láì pọn dandan ki wọ́n gba àbọ̀.

## 6.0 IṢẸ́ ṢÌṢE

Kọ àpólà aṣẹ̀pọ́n alábọ̀ tàbí aláìlábọ̀ márùn-un márùn-un kí o sì gbìyànjú láti fi hàn nínú àwòrán atọ́ka igi.

Commented [O.J93]: fi wọ́n hàn

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ/ÀWỌN ÌWÉ FÙN KÍKÀ


Awóbùlúyì, O. 1978. *Essentials of Yorùbá Grammar,* Ìbàdàn: UPL.

Awobuluyi, O. 1988. *Èdè Ìperí Yorùbá*: *Apá kejí*, Lagos: NERDC

Awóbùlúyì, O. 2001a. "Arọ́pò–Orúkọ Kúkúrú Ẹni–Kẹ́ta Ẹyọ Aṣọlùwà" *Yorùbá,* Vol. 2, No. 1 pp 1-8

Awóbùlúyì, O. 2001b. "Òte–Ìlò Àwọn Arọ́pò–Orúkọ Kúkúrú" Bébà tí a kà ní Àpérò Ẹgbẹ́ Onímọ̀ ÈdèYorùbá: Yunifásítì ìlú Eko.

Awobuluyi, O. 2008. *Ẹ̀kọ́ Íṣẹ̀dá-Ọ̀rọ̀ Yorùbá*, Akurẹ: Montem Paperbacks

Awobuluyi, O. 2013. *Ẹ̀kọ́ Gírámà Èdè Yorùbá*, Oshogbo: Montem Paperbacks

Bámgbóṣé, Ạ. 1967. *A Short Yorùbá Grammar*, Ìbàdàn: HEB.

Bámgbóṣé, Ạ. 1990. *Fonọ́lọ́jì àti Gírámà Yorùbá.* Ìbàdàn: UPL.

Oyetade, S.O. 1995. *Yorùbá Grammar I.* Ibadan, Centre for External Studies, UI.

Táíwò, O. 2003. Tense and Aspect in Ào. Nínú Ndimele O.M (olótùú) *Languages and Linguistics in Nigeria.* A Festscrist in Honour of Kay williamson.

Taiwo, O. 2007. Short Subject Pronoun in the Ào dialect of Yorùbá. *JOLAN: Journal of Linguistic Association of Nigeria (JOLAN)* No 10 o.i. 67 – 86

Taiwo, O. 2008a. *Basic Concepts in Grammar*: Ibadan, DLC, UI

Taiwo, O. 2008b. *Basic Grammar*: Ibadan, DLC, UI

**ÌPÍN 3: ỌRỌ̀-APÀRÍSÍDÀ (APR)**


**1.0** Ìfáárà
**2.0** Èròǹgbà àti Àfojúsùn
**3.0** Ìbéèrè Ìṣáájú
**4.0** Àkóónú Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
**4.1** Ọ̀rọ̀-apàrísídà (APR)
**4.2** Ìrísí àpólà ìyísódì (APOD)
**4.3** Ìrísí àpólà àsìkò (APKO)
**4.4** Ìrísí àpólà ibá-ìṣẹ̀lẹ̀ (APIB)
**5.0** Ìsọníṣókí
**6.0** Iṣẹ́ Ṣíṣe
**7.0** Ìwé Ìtọ́kasí/Àwọn Ìwé Fùn Kíkà


## 1.0. ÌFÁÁRÀ

Bí mo ti ṣe ṣàlàyé ìhun àwọn àpólà lórísirísi ní àwọn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tó kọjá, ìbéèrè tí ó lè wá sí ọkàn ni pé, báwo ni ìhun gbólóhùn yó ṣe rí?, àti pé bí gbogbo àpólà ti ní orí, kí ni yó jẹ́ orí fún gbólóhùn.? Àwọn onímọ̀ fi yé wa pé ọ̀rọ̀-apàrísídà (APR) ni orí gbólóhùn. Ọ̀kọ̀ọ̀kan ọ̀rọ̀-apàrísídà yìí ní àpólà tirẹ̀ èyí tí wọ́n ti jẹ́ orí. Ní ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, mà á ṣàlàyé àwọn ọ̀rọ̀-apàrísídà (APR) lẹ́sẹẹsẹ, mà á sì fi ìrísi àpólà wọn hàn ní àwórán atọ́ka-igi.

## 2.0 ÈRÒǸGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN

Lẹ́yìn tí ó bá ti ka ìpín yìí tán, wà á lè mọ àwọn ọ̀rọ̀-apàrísídà, wà á sì tún le fi fi ìrísi àpólà wọn hàn ní àwórán atọ́ka-igi.

## 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢÁÁJÚ

Dárúkọ àwọn ọ̀rọ̀-apàrísídà tí o mọ.

## 4.0 ÀKÓÓNÚ ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

### 4.1 Ọ̀rọ̀-Apàrísídà (APR)

Ní ìtúpalẹ̀ ìhun àwọn àpóla tí a ti yẹ̀ wò, ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn ni wọn ní orí tí a sì yà sọ̀tọ́ gedegbe. Ọ̀rọ̀-Apàrísídà (APR) **(Inflection (I** tàbí **Infl)** ni àwọn onímọ̀ yà sọ̀tọ̀ gẹ́gẹ́ bí orí gbólóhùn. Ìdí tí èyí fi rí bẹ́ẹ̀ ni pé Ọ̀rọ̀-Apàrísídà (APR) yìí ní ipa pàtàkì tí ó ń kó nínú APOR àti APIṢ, òun ni ó so àwọn méjèèjì pọ̀.

Àwọn Ọ̀rọ̀-Apàrísídà (APR) ní èdè Yorùbá ni atọ́ka ìyísódì (OD), atọ́ka Àsìkò (KO) àti atọ́ka Ìba-Ìṣẹ̀lẹ̀ (IB). Ìdí tí a fi ń pè wọ́n ní Ọ̀rọ̀-Apàrísídà (APR) ni pé ìrísí wọn máa ń yí pa dà nínú ẹ̀hun fún ìdí kan tàbí òmíràn.

**ÌGBÉLÉWỌ̀N AKẸ́KỌ̀Ọ̀**

Dárúkọ àwọn Ọ̀rọ̀-Apàrísídà (APR) ní èdè Yorùbá

### 4.2 Ìrísí Àpólà Ìyísódì (APOD)

Nínú ìhun tí àpólà ìyísódì (APOD) bá ti jẹ yọ, atọ́ka ìyísódì (OD) ni ó jẹ́ orí, òun níkan ni ó sì máa ń wà nínú APOD. Ìyẹn ni pé, OD ni ó jẹ́ kànńpá kò sì ní ìsọmọgbè. Nínú àwọn gbólóhùn ìsàlẹ̀ yìí, àwọn atọ́ka ìyísódì (OD) ni mo kọ ní àkọhàn.

1a. Adé **kìí** jẹ ẹ̀bà
b. Ìyábọ̀ **kò** ní wá sí ìpàdé

Commented [O.J94]: Ṣé wúnrẹ̀n apàrísídà méjì kọ́ níyí: **kì** àti **í**? Ṣe wúnrẹ̀n ibá ìṣẹ̀lẹ̀ kọ́ nìyí: **í**?

d. Olú **kọ́** ni ò sọ bẹ́ẹ̀
e. **Máà** jókòó sí ibẹ̀ yẹn

Ìrísí kan náà ni àwọn APOD tí wọ́n wà nínú àwọn àpẹẹrẹ òkè wọ̀nyì. Òun ni mo sì fi hàn ní ìsàlẹ̀ yìí

2



**ÌGBÉLÉWỌ̀N AKẸ́KỌ̀Ọ́**
Gbìyànjú láti fi ìrísí Àpólà Ìyísódì (APOD) hàn nínú àwòrán atóka-igi

### 4.3 Ìrísí Àpólà Àsìkò (APKO)

Atọ́ka Àsìkò (KO) nìkan ni ó máa ń wà nínú ìhun Àpólà Àsìkò (APKO), kànńpá sì ni ó jẹ́ nínú gbogbo gbólóhùn àfi gbólóhùn àṣẹ nìkan ni ó lè máà ní atọ́ka àsìkò (KO). Ní èdè Yorùbá, oríṣi àsìkò méjì ni a máa ń yà sọ́tọ̀, àwọn ni *àsìkò ọjọ́ ìwájú* àti *àsìkò afànámọ́nìí*. Atọ́ka àsìkò ọjọ́-ìwájú ni *à, yóò, ní, máa*, ṣùgbọ́n àsìkò afànámọ́nìí kò ní atọka gẹ́gẹ bí ó ṣe wà nínú gbólóhùn wọ̀nyí.

3a. Olú **à/yóó/máa** sùn sí Èkó.
b. Olú kò **ní** sùn sí Èkó.
d. Olú sanra.
e. Olú jẹ iṣu.
ẹ. Olú sùn sí Èkó.

Gbólóhùn àkọ́kọ́, (3a), fi hàn pé ìṣẹ̀lẹ̀ tí a ń sọ nípa rẹ̀ kò í tíì wáyé, ìyẹn ìṣẹ̀lẹ̀ ọ̀jọ́-ìwájú, atọ́ka àsìkò ọ̀jọ́ ìwájú tí ó wa nínú ẹ̀hun náà ni ó ń ṣe àfihàn èyí. Gbólóhùn kejì, (3b), jẹ́ kí a mọ̀ pé ìṣẹ̀lẹ̀ kò lè wáyé, atọ́ka ìyísódì ***kò,*** àti akọ̀ka àsìkò ọjọ́-iwájú, ***ní,*** ni ó jẹ́ kí a mọ èyí. Àwọn gbólóhùn mẹ́ta yóòkù ń sọ nípa ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó ń ṣẹ̀lẹ̀ lọ́wọ́ tàbí èyí tí ó ti kọjá. Ní ibi tí atọ́ka àsìkò ti fara sin, bí ó ṣe wà ní àpẹẹrẹ (3d-ẹ) lókè, àmì yìí, **ø,** tí ó dúró fún òfo tàbí ìfarasin, ni a máa ń lò fún un.

Ìrísí Àpólà Àsìkò (APKO) tí ó wà ní (3a) àti (3b) ni mo fi hàn ní (4a), mo sì fi àwọn tí ó wà ní (3d-ẹ) hàn ní (4b) ìsàlẹ̀ yíí.

4a



b


**ÌGBÉLÉWỌ̀N AKẸ́KỌ̀Ọ́**
Gbìyànjú láti fi ìrísí Àpólà Àsìkò (APKO) hàn nínú àwòrán atóka-igi

### 4.4 Ìrísí Àpólà Ibá-Ìṣẹ̀lẹ̀ (APIB)

Atọ́ka Ibá-ìṣẹ̀lẹ̀ (IB) nìkan ni ó máa ń wà nínú ìhun Àpólà Ibá-Ìṣẹ̀lẹ̀ (APIB). Ibá-Ìṣẹ̀lẹ̀ (IB) ni ìsọ̀rí gírámà tí ó ń ṣàlàyé tàbí sọ bóyá ìṣẹ̀lẹ̀ kan ti parí tàbí kò ì tíì parí. Èyí túmọ̀ sí pé oríṣi ibá-ìṣẹ̀lẹ̀ méjì ni a lè yà sọ́tọ̀, àwọn ní ibá-ìṣẹ̀lẹ̀ aṣetán àti ibá-ìṣẹ̀lẹ̀ àìṣetán. Ṣùgbọ́n a tún máa ń sọ nípa Ibá-Ìṣẹ̀lẹ̀ (IB) àdáwà ní ibi tí kò ti sí atọ̀ka ibá-ìṣẹ̀lẹ̀ nínú ẹ̀hun. Àpẹẹrẹ wọn wa nínú gbólóhùn ìsàlẹ̀ yìí.

5a Olú **tí** lọ.
b. Olú **ń** lọ.
d. Olú **máà ń** gba ibí kọjá.
e. Olú gba ibí kọjá.
ẹ. Olú lọ.

Commented [O.J95]: Ṣé kì í ṣe IB bárakú ni (5d)?

Gbólóhùn àkọ́kọ́ (5a) sọ nípa ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó ti parí, nígbà tí gbólóhùn méjì tí ó tẹ̀lé e, (5b) àti (5d), ń sọ nípa ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó ń lọ lọ́wọ́ àti/tàbí èyí tí ó máa ń ṣẹlẹ̀ ní gbogbo ìgbà. Gbólóhùn méjì tí ó gbẹ̀yìn, (5e) àti (5ẹ), kò ní atọ̀ka ibá-ìṣẹ̀lẹ̀, àwọn ni a mọ̀ sí ibá-ìṣẹ̀lẹ̀ àdáwà, àmì yìí, **ø,** tí ó dúró fún òfo tàbí ìdáwà, ni a máa ń lò fún òun náà.

Ìrísí Àpólà Ibà-Ìṣẹ̀lẹ̀ (APIB) tí ó wà ní (5a) dè (5d) ni mo fi hàn ní (6a), mo sì fi àwọn tí ó wà ní (5e) àti (5ẹ) hàn ní (6b) ìsàlẹ̀ yìí.

6a



b



**ÌGBÉLÉWỌ̀N AKẸ́KỌ̀Ọ́**
Gbìyànjú láti fi ìrísí Àpólà Ibá-Ìṣẹ̀lẹ̀ (APIB) hàn nínú àwòrán atóka-igi

### 5.0 ÌSỌNÍṢÓKÍ

Àwọn Ọ̀rọ̀-Apàrísídà (APR) ní èdè Yorùbá ni atọ́ka ìyísódì (OD), atọ́ka Àsìkò (KO) àti atọ́ka Ìba-Ìṣẹ̀lẹ̀ (IB). Ọ̀kọ̀ọ̀kan ọ̀rọ̀-apàrísídà yìí ní àpólà tirẹ̀ èyí tí wọ́n ti jẹ́ orí. Ìyẹn ni pé, nínú ìhun àpólà ìyísódì (APOD), atọ́ka ìyísódì (OD) ni orí, Atọ́ka Àsìkò (KO) ni orí nínú ìhun àpólà àsìkò, atọ́ka Ìba-Ìṣẹ̀lẹ̀ (IB) ni orí nínú ìhun àpólà Ìba-Ìṣẹ̀lẹ̀.

**6.0 IṢẸ́ ṢÌṢẸ**

Kọ àwọn ọ̀rọ̀-apàrísídà tí o ti kọ́, kí o sì fi ìhun àpólà wọn hàn ní àwòrán atọ́ka-igi.

**7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ/ÀWỌN ÌWÉ FÙN KÍKÀ**


Awóbùlúyì, O. 1978. *Essentials of Yorùbá Grammar,* Ìbàdàn: UPL.

Awobuluyi, O. 1988. *Èdè Ìperí Yorùbá*: *Apá kejí*, Lagos: NERDC

Awóbùlúyì, O. 2001a. "Arọ́pò–Orúkọ Kúkúrú Ẹni–Kẹ́ta Ẹyọ Aṣolùwà" *Yorùbá*, Vol. 2, No. 1 pp 1-8

Awóbùlúyì, O. 2001b. "Òte–Ìlò Àwọn Arọ́pò–Orúkọ Kúkúrú" Bébà tí a kà ní Àpérò Ẹgbẹ́ Onímọ̀ ÈdèYorùbá: Yunifásítì ìlú Eko.

Awobuluyi, O. 2008. *Ẹ̀kọ́ Íṣẹ̀dá-Ọ̀rọ̀ Yorùbá*, Akurẹ: Montem Paperbacks

Awobuluyi, O. 2013. *Ẹ̀kọ́ Gírámà Èdè Yorùbá*, Oshogbo: Montem Paperbacks

Bámgbóṣé, Ạ. 1967. *A Short Yorùbá Grammar*, Ìbàdàn: HEB.

Bámgbóṣé, Ạ. 1990. *Fonọ́lọ́jì àti Gírámà Yorùbá*. Ìbàdàn: UPL.

Oyetade, S.O. 1995. *Yorùbá Grammar I*. Ibadan, Centre for External Studies, UI.

Táíwò, O. 2003. Tense and Aspect in Ào. Nínú Ndimele O.M (olótùú) *Languages and Linguistics in Nigeria.* A Festscrist in Honour of Kay williamson.

Taiwo, O. 2007. Short Subject Pronoun in the Ào dialect of Yorùbá. *JOLAN: Journal of Linguistic Association of Nigeria (JOLAN)* No 10 o.i. 67 – 86

Taiwo, O. 2008a. *Basic Concepts in Grammar*: Ibadan, DLC, UI

Taiwo, O. 2008b. *Basic Grammar*: Ibadan, DLC, UI

## ÌPÍN 4: FỌ́NRÁN-ÌHUN ÀPÓLÀ APÀRÍSÍDÀ (APAPR)

**1.0** Ìfáárà
**2.0** Èròǹgbà àti Àfojúsùn
**3.0** Ìbéèrè Ìṣáájú
**4.0** Àkóónú Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
**4.1** Fọ́nrán-ìhun àpólà apàrísídà (APAPR)
**4.2** Ìrísí àpólà apàrísídà (APAPR)
**5.0** Ìsọníṣókí
**6.0** Iṣẹ́ Ṣíṣe
**7.0** Ìwé Ìtọ́kasí/Àwọn Ìwé Fùn Kíkà

### 1.0 ÌFÁÁRÀ

Bí mo ti ṣe ṣàlàyé ní àwọn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tó kọjá pé ọ̀rọ̀-apàrísídà (APR) ni orí gbólóhùn. Ìdí ni pé Ọ̀rọ̀-Apàrísídà (APR) yìí ní ipa pàtàkì tí ó ń kó nínú APOR áti APIṢ, òun ni ó so àwọn méjèèjì pọ̀ láti di gbólóhùn. Ní ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, mà á ṣàlàyé fọ́nrán-Ìhun Àpólà Apàrísídà (APAPR), àti bí a ṣe ń lò ó fún gbólóhùn ní àwórán atọ́ka-igi.

### 2.0 ÈRÒǸGBÀ ÀTI ÀFOJÚSÙN

Lẹ́yìn tí ó bá ti ka ìpín yìí tán, wà á lè mọ fọ́nrán-Ìhun Àpólà Apàrísídà (APAPR), àti bí a ṣe ń lò ó fún gbólóhùn ní àwórán atọ́ka-igi.

### 3.0 ÌBÉÈRÈ ÌṢÁÁJÚ

Kí ni àkóónú Ìhun Àpólà Apàrísídà (APAPR).

### 4.0 ÀKÓÓNÚ ÌDÁNILẸ́KỌ̀Ọ́

#### 4.1 Fọ́nrán-Ìhun Àpólà Apàrísídà (APAPR)

Gẹ́gẹ́ bí mo ṣe mẹ́nu bà á ṣáájú, Àpólà Apàrísídà (APAPR) ni àpólà tí a máa ń lò fún odidi gbólóhùn. Ọ̀rọ̀-Apàrísídà (APR) ni a sì gbà pé ó jẹ́ orí fún gbólóhùn nítorí pé òun ní orí fún APAPR. Ìmọ̀ yìí yàtọ̀ sí ìmọ̀ àtijọ́ tí ó máa ń lo àrokò GB gẹ́gẹ́ bí orí fún gbólóhùn. Ara ìdí tí GB fi kúnà láti jẹ́ orí fún gbólóhùn ni pé kò sí ohun kan ní GB tí a lè rí gẹ́gẹ́ bí orí. Ṣùgbọ́n àwọn ọ̀rọ̀-apàrísídà bíi atọ́ka ìyísódì, atọ́ka àsìkò àti atọ́ka ibà-ìṣẹ̀lẹ̀ jẹ́ ìsọ̀rí gírámà tí ó sọ nípa APOR, tí ó jẹ́ olùwà gbólóhùn, àti APIṢ, tí í ṣe kókó gbólóhùn, àwọn ni wọ́n sì so wọ́n pọ̀. Ìrísí APAPR ni mo fi hàn ní ìsàlẹ̀ yìí.

7




APR, ọ̀rọ̀-apàrísídà, tí ó jẹ́ orí nínú ìhun APAPR lè jẹ́ àpapọ̀ àpólà ìyísódì, àpólà àsìkò àti atọ́ka ibà-ìṣẹ̀lẹ̀, ó sì lè jẹ́ àpólà àsìkò àti ọ̀kan nínú àpólà ìyísódì àti àpólà ibà-ìṣẹ̀lẹ̀ tàbí kí ó jẹ́ àpólà àsìkò nìkan. Ìhun oríṣiríṣi APR ni mo fi hàn ní ìsàlẹ̀ yìí.

8a



b.




d.




e.




**ÌGBÉLÉWỌ̀N AKẸ́KỌ̀Ọ́**

Gbìyànjú láti fi àwọn àkóónú fọ́nrán-Ìhun Àpólà Apàrísídà (APAPR) hàn lókọ̀ọ̀kan

## 4.2 Ìrísí Àpólà Apàrísídà (APAPR)

Ní báyìí tí a ti ṣàfihàn APOR, APIṢ àti APAPR, tí a sì ti ìrísí ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn hàn nínú àwòrán atọ́ka-igi, mo máa tẹ̀síwájú láti fi ìrísí àwọn gbólóhùn kan hàn.

9a. Àkẹ́kọ̀ọ́ sìnńtáàsì wọ̀nyí ti jókòó sí kíláàsì
b. Ọmọ tí mo bí ti di àgbà.
d. Mi ò tíì gbọ́ pé Olú ti dé
e. Òun gan-an yóò fẹ́ jẹ iṣu sísè.
ẹ. Ẹ máà dá mi dá iṣẹ́ yìí
f. Adẹ wá ṣùgbọ́n Òjó ti lọ

Gbólóhùn (9a) jẹ́ gbólóhùn abọ́dé tàbí gbólóhùn ẹlẹ́yọ ọ̀rọ̀-ìṣe, gbólóhùn (9b) àti (9d) jẹ́ gbólóhùn àfibọ̀, gbólóhùn (9e) àti (9ẹ) jẹ́ gbólóhùn ọlọ́rọ̀-ìṣe àsínpọ̀, gbólóhùn (9f) sì jẹ́ gbólóhùn alákànpọ̀. Mo máa tẹ̀síwájú láti fi ìrísí (9a) àti (9b) hàn ní (10)

10a




b




**ÌGBÉLÉWỌ̀N AKẸ́KỌ̀Ọ́**

Gbìyànjú láti fi ìhun gbólóhùn kan tó wù ọ́ hàn yìí ní àwòrán atọ́ka-igi.

## 5.0 ÌSỌNÍṢÓKÍ

Àpólà Apàrísídà (APAPR) ni àpólà tí a máa ń lò fún odidi gbólóhùn. Ọ̀rọ̀-Apàrísídà (APR) ni a sì gbà pé ó jẹ́ orí fún gbólóhùn nítorí pé òun ní orí fún APAPR. Nínú Ìrísí APAPR ní àwòrán akọ́ka-igi APR (ọ̀rọ̀-apàrísídà) tí ó jẹ́ orí nínú ìhun APAPR lè jẹ́ àpapọ̀ àpólà ìyísódì, àpólà àsìkò àti atọ́ka ibà-ìṣẹ̀lẹ̀, ó sì lè jẹ́ àpólà àsìkò àti ọ̀kan nínú àpólà ìyísódì àti àpólà ibà-ìṣẹ̀lẹ̀ tàbí kí ó jẹ́ àpólà àsìkò nìkan.

## 6.0 IṢẸ́ ṢÍṢE

Gbìyànjú láti fi ìhun gbólóhùn ìsálẹ̀ yìí ní àwòrán atọ́ka-igi.

Adẹ wá ṣùgbọ́n Òjó ti lọ

## 7.0 ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ/ÀWỌN ÌWÉ FÙN KÍKÀ

Awóbùlúyì, O. 1978. *Essentials of Yorùbá Grammar,* Ìbàdàn: UPL.
Awobuluyi, O. 1988. *Èdè Ìperí Yorùbá*: *Apá kejí*, Lagos: NERDC
Awóbùlúyì, O. 2001a. "Arọ́pò–Orúkọ Kúkúrú Ẹni–Kẹ́ta Ẹyọ Aṣolùwà" *Yorùbá,* Vol. 2, No. 1 pp 1-8
Awóbùlúyì, O. 2001b. "Òte–Ìlò Àwọn Arọ́pò–Orúkọ Kúkúrú" Bébà tí a kà ní Àpérò Ẹgbẹ́ Onímọ̀ ÈdèYorùbá: Yunifásítì ìlú Eko.
Awobuluyi, O. 2008. *Ẹ̀kọ́ Íṣẹ̀dá-Ọ̀rọ̀ Yorùbá*, Akurẹ: Montem Paperbacks
Awobuluyi, O. 2013. *Ẹ̀kọ́ Gírámà Èdè Yorùbá*, Oshogbo: Montem Paperbacks
Bámgbóṣé, Ạ. 1967. *A Short Yorùbá Grammar*, Ìbàdàn: HEB.
Bámgbóṣé, Ạ. 1990. *Fonọ́lọ́jì àti Gírámà Yorùbá.* Ìbàdàn: UPL.
Oyetade, S.O. 1995. *Yorùbá Grammar I.* Ibadan, Centre for External Studies, UI.
Táíwò, O. 2003. Tense and Aspect in Ào. Nínú Ndimele O.M (olótùú) *Languages and Linguistics in Nigeria.* A Festscrist in Honour of Kay williamson.
Taiwo, O. 2007. Short Subject Pronoun in the Ào dialect of Yorùbá. *JOLAN: Journal of Linguistic Association of Nigeria (JOLAN)* No 10 o.i. 67 – 86
Taiwo, O. 2008a. *Basic Concepts in Grammar*: Ibadan, DLC, UI
Taiwo, O. 2008b. *Basic Grammar*: Ibadan, DLC, UI

**ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ**

Ajọ́ågọ́lọ, T.O. 2005. *Negation in the Ào Dialect of Yorùbá.* PhD Thesis, University of Ibadan, Ibadan, Nigeria
Awóbùlúyì, O. 1978. *Essentials of Yorùbá Grammar,* Ìbàdàn: UPL.
Awobuluyi, O. 1988. *Èdè Ìperí Yorùbá*: *Apá kejí*, Lagos: NERDC
Awóbùlúyì, O. 2001a. "Arọ́pò–Orúkọ Kúkúrú Ẹni–Kẹ́ta Ẹyọ Aṣolùwà" *Yorùbá,* Vol. 2, No. 1 pp 1-8
Awóbùlúyì, O. 2001b. "Òte–Ìlò Àwọn Arọ́pò–Orúkọ Kúkúrú" Bébà tí a kà ní Àpérò Ẹgbẹ́ Onímọ̀ ÈdèYorùbá: Yunifásítì ìlú Eko.
Awobuluyi, O. 2008. *Ẹ̀kọ́ Íṣẹ̀dá-Ọ̀rọ̀ Yorùbá*, Akurẹ: Montem Paperbacks
Awobuluyi, O. 2013. *Ẹ̀kọ́ Gírámà Èdè Yorùbá*, Oshogbo: Montem Paperbacks
Bámgbóṣé, Ạ. 1967. *A Short Yorùbá Grammar*, Ìbàdàn: HEB.
Bámgbóṣé A. 1984. *Èdè ìperí Yorùbá: Apá kìíní*, Lagos: NERDC
Bámgbóṣé, Ạ. 1990. *Fonọ́lọ́jì àti Gírámà Yorùbá*. Ìbàdàn: UPL.
Comrie, Bernard. (1981). Language universals and linguistic typology: syntax and morphology (2nd ed). University of Chicago Press, Chicago
Dryer, M. S. (2013). Order of Subject, Object and Verb. In M. S. Dryer & M. Haspelmath (eds), *The World Atlas of Language Structures Online*.
https://www.englisch-hilfen.de › grammar
*https://en.wikipedia.org › wiki › Word_order*
*https://englishsentences.com*
*https://www.toppr.com › guides › english › sentences*
*https://www.really-learn-english.com › word-order-in-english*
Malmkjaer, K. (Olótùú). 1999. *The Linguistic Encyclopeadia.* London & New York: Routledge.
Mario Pel. 1966. *Glossary of Linguistic Terminology*. New York & London. Columbia University Press
Táíwò, O. 2003. Tense and Aspect in Ào. Nínú Ndimele O.M (olótùú) *Languages and Linguistics in Nigeria.* A Festscrist in Honour of Kay williamson.
Taiwo, O. 2007. Short Subject Pronoun in the Ào dialect of Yorùbá. *JOLAN: Journal of Linguistic Association of Nigeria (JOLAN)* No 10 o.i. 67 – 86
Taiwo, O. 2008a. *Basic Concepts in Grammar*: Ibadan, DLC, UI
Taiwo, O. 2008b. *Basic Grammar*: Ibadan, DLC, UI
Taiwo, O. 2009. *Elementary Grammar*: Ibadan, DLC, UI
Taiwo, O. 2010. *Transformational Grammar I*: Ibadan, DLC, UI
Taiwo, O. 2011. *Mofoloji: Àtúnṣe kejì*. Ibadan: Ibadan, Universal Akada Books Limited.
Taiwo, O. 2014a. The morpho-syntactic interaction and the derivation of nominal compounds in Yorùbá. *International Journal of Language Studies* Vol. 8 No 1 o.i. 67- 92
Taiwo, O. 2014b *Àgbéyẹ̀wò Gírámà Yorùbá Àtijọ́*: Ibadan, DLC, UI
Taiwo, O. 2014d *Fonọ́lọ́jì Yorùbá*: Ibadan, DLC, UI
Taiwo, O. 2015. Fífi iye hàn nínú ẹ̀hun èdè Yorùbá. Bébà tí a kà ni Àpérò Ẹgbẹ́ Onímọ̀ Édé Yorùbá: Yunifásítì Adekunle Ajasin, Akungba Akoko
Táíwò, O. (2018a). Ọ̀ṣuwọ̀n fún dídá Ọ̀rọ̀-ìṣe mọ̀ ní èdè Yorùbá. Bébà tí a kà ní IBALSG Colloquim, Yunifásítì Ìbàdàn. January 2018
Táíwò, O. (2018b). Àgbéyẹ̀wò Oríkì Ọ̀rọ̀-ìṣe èdè Yorùbá. Bébà tí a kà ní IBALSG Colloquim, Yunifásítì Ìbàdàn. July 2018
Táíwò, O. (2018d). Ẹ̀pọ́n nínú Ìhun Àpólà-ìṣe èdè Yorùbá. Bébà tí a kà ní IBALSG Colloquim, Yunifásítì Ìbàdàn. July 2018
Taiwo, O. (Ó ń bọ̀ lọ́nà). *Gírámà*
Taiwo, O. àti Ọlakolu, T. 2010. Ọ̀rọ̀- ìṣe Alákànpọ̀ ní Èdè Yorùbá. *Research in African Languages*

*and Linguistics (RALL)* Vol. 10 o.i. 90-112
Taiwo, O. àti Adekunle, T. 2012. Àgbéyẹ̀wò Oríkì Ọ̀rọ̀ Orúkọ ní èdè Yorùbá. *Ago-Iwoye Journal of Languages and Literary Studies* Vol.3. o.i. 18-38
Tomlin, Russel S. (1986). *Basic Word Order: Functional Principles*. London: Croom Helm.
Yusuff, Ọ. 1995. *Gírámà Yorùbá Àkọ̀tun: Ní Ìlànà Ìṣípayà Onídàrọ,* Ijebu-ode: Ṣebiotimọ Publications.